Bodleian Libraries
UNIVERSITY OF OXFORD

This book is part of the collection held by the Bodleian Libraries
and scanned by Google, Inc. for the Google Books Library Project.

For more information see:

http://www.bodleian.ox.ac.uk/dbooks

This work is licensed under a Creative Commons Attribution-NonCommercial-ShareAlike 2.0 UK: England & Wales (CC BY-NC-SA 2.0) licence.

M.adl.a. 72 E. 63

15

# IWE ERẸ

## (PLAY)

## *TI JULIUS CAESAR*

TI SHAKESPEARE KỌ

TI A YIPADA SI EDE YORUBA

LATI ỌWỌ

ALUFA E. T. JOHNSON,
ỌGA AGBA ILE-IWE
NEW HIGH CLASS SCHOOL,

EKO, NIGERIA,

LAGOS.

"TIKA-TORE" PRESS.

m. adds. 72 e. 4

BODLEIAN 18 MAR 1981 LIBRARY

# PREFACE.

THIS book is a translation with a purpose for we sometimes learn by imitation. To imitate we must bring the object to be imitated down to our own level. As Africans we have abundant materials for novels and plays but we have not yet the knowledge nor the patience, if even we have the knowledge, to put it up in order to bring it to the recognised standard. Hence our plays do not interest and amuse. That this is so, is evident from a question raised sometime in one of our local journals when there appeared to be some rage for staging original native plays. The question was "Why African plays fail to interest?" I was once present in a School-y rd where some youngmen and women resorted to in order to arrange for the staging of an original play. Instead of considering aforehand what the nature and contents of this new play is to be and applying to it the principles of play-wrighting they (the actors and their friends) came in with a lot of materials to start a hawking business in a village market. This was to be the first scene of the first Act. Business was immediately set in motion. Impromptu conversation started between the actors, and I believe, was taken down in script and so on until that Scene was said to be completed. The actors themselves knew not where they were at the end of the several Acts and of the play as a whole. But there was a safety valve on the day of their final showing to the public—they concluded the play with the coronation ceremony of a King when there was plenty of gongings, drumming and noise making and the satisfaction that a really enjoyable time was spent.

I have now to state what a play is. A play is a form of human amusement presented on a stage to interest spectators. The stage itself is expected to be a microcosm—a little world in a way with its own peculiar inhabitants and their relations in imitation of the world of affairs both in purpose, intention and action. (When in action a play is called a drama) hence no play can be said to be successfully written which does not represent one phase, at least, of our human life in a scale however small, and no playwright can be termed successful who does not make his character or characters reveal some aspect or aspects of our human nature. So that a playwright must of necessity be a student of human nature and that true to life.

Of the chief *elements of a play* one is *Characterisation.* This is the peopling of his little world with men and women for the purpose of action. It is this, that is scientifically called *Characterisation* or the creation of Characters, historical or fictitious. The relation between the characters themselves is presented in the form of a story or stories if necessary. The different parts of one story or the conjunctions of one story with another story or stories is termed *Plotting.* In their diversity these stories or part of a story must have unity. Each part of this unified plot must have tying or untying forces which are called Complications or Resolutions and this leads to what is called *interest.* There is also the element of *suspense, anticipation, climax, hedging, accidents* and a few others.

To understand fully what a play is like and to do justice to a playwright we must consider in detail and almost at the cost of repetition a few of these elements of a play and their application. As God made the world and peopled it with human beings so a playwright created his own world and peopled it with human beings and creatures of his own creation. (I use this figure with all reverence). As in the world of reality these men and creatures live and move and have their being so in the playwright's world his men and creatures *live in their own* atmosphere (*Setting*) move and have their being. It will be too long for the purpose of a preface, to dilate on the elements of complication and Resolution, Interest and Incident, Hedging and Suspense, *et cetera* for the purpose of making analogies, suffice it to say that we have their counterparts in the world of nature and the chief object of which is to enable the writer or reader to *Prophesy* in its narrowest sense and to ANTICIPATE. Herein lies the esence of Prophecy. In this direction we Africans as a people are much lacking. A few other but minor contributions the study or writing of a play make to the progress of a people are the Linguistic contributions for :—

1. It increases their vocabulary.

2. It leads to the revival of obscure and otherwise obsolete terms and clothes them with new life.

3. It assists in the comparison of words in one language with words in another. In my search for a Yoruba word to give an appropriate rendering of the English word "Ambition" in the sentence "Yet Brutus says he was ambitious" it dawned upon my mind that Shakespeare's English is Renaisance English and I had to seek aid in that direction. Immediately I called up or drew together the different figures in it and the Yoruba word "Iwọra" presented itself.

4. By means of the utterance of actors you are able to deduce their national and individual philosophy so as to enter into their soul or take a guage of their mentality

*e.g.* Cassius plays throughout the role of an instigator (or to borrow a figure from Mechanical Science or an illustration from the workshop) the role of an initial force in a collectivity of human momentums and Brutus though coming out in many parts with a noble soul towards his friend Caesar yet for the purpose of this murder advances the theory of "potential danger" against him.

... ............."And, since the quarrel

> Will bear no colour for the thing he is,
> Fashion it thus; that what he is, augmented,
> Would run to these and these extremities:
> And therefore think him as a serpent's egg,
> Which, hatch'd, would, as his kind, grow mischievous,
> And kill him in the shell." *Act. 2 Sc. 1 Lines 28-34.*

It is necessary for us (Natives) to study closely these and suchlike points in staging any native play. By imitation I here mean that we study intelligently these writings and apply their principles of work to ours.

It only remains for me now to express my obligations to two of my old pupils who by this time last year waited to assist me in the translation both in season and out of season. They are now Messrs. Ọlatunji Adeṣọla and Alfred Joshua.

In the spelling of the names I retain the English form to make it an easy matter for non-English readers to be familiar with them when seen in Eng. script. Caesar is still spelt Caesar and not Kesari as in the Yoruba version of the Bible.

Act 1 to 3 describe the plot up to the death of Caesar; Acts 4 and 5 the Battles and the Nemesis that follows. The whole play is a play of Nemesis and this certainly is the philosophy at the back of it as a whole.

E. T. JOHNSON.

# INTRODUCTION

## ( Yoruba ).

---

JULIUS CAESAR ni oruko Balogun nla kan ni Romu niwọn ọdun marundinladọta ka to bi Kristi. Orukọ rẹ ni Shakespeare ( Gẹsi oloye nla ati ọmọwe kan ni England ) fi sọ iwe ere rẹ ti a yipada si ede Yoruba yi. Nitori Julius Caesar jẹ ọkan ninu awọn enia pataki ti a fi itan rẹ kun itan awọn ti a sọ sinu iwe yi ni a ṣe npe iwe na ni Julius Caesar. O ṣi le jẹ pe a pe iwe yi ni Julius Caesar nitori on ni awọn ẹgbẹ rẹ gun lọbẹ pa, ti oku rẹ si nro to si yọ si Brutus ọrẹ rẹ ti o fi ọbẹ gun un gbẹhin. Caesar tabi "Kesari" ti a kọ orukọ rẹ ninu Bibeli Mimọ jẹ ọmọ ẹgbọn rẹ obinrin lakoko yi, aṣẹ rẹ kalẹ ni Romu bi aṣẹ Ọba, agbara rẹ tilẹ fẹrẹ mulẹ ju ti Ọba lọ. O ṣẹgun o si gba ilu pupọ fun awọn ara ilu rẹ, ṣugbọn nitori ohun ti oju awọn ara Romu ti ri wọn ko fẹ gbọ orukọ Ọba si eti. Fun ọdun pupọ awọn agbagba Romu lo nṣe itọju ilu wọn fun ara wọn. O wa di akoko kan Julius Caesar wa ri pe fun alafia ati ilọsiwaju Romu o yẹ ki wọn ni Ọba. Ilu da si meji nipa oye yi, Caesar si jẹ pataki ati olori awọn to nfẹ ki ilu ni Ọba ; ati jubẹ lọ ki on papa jẹ Ọba na. Nitori eyi ni awọn ẹgbẹ rẹ ṣe dide si wọn sin gun lọbẹ pa ninu ajọ Igbimọ ni ọjọ kan. Itan iku rẹ yi ati ogun ti o ti idi rẹ bẹ silẹ ati bi Ẹsan ti mu gbogbo awọn to gun lọbẹ pa tabi pataki ninu wọn ni Oyinbo Gẹsi yi ti a npe ni Shakespeare ẹniti o mọwe to si loye iwa ẹda pupọ lori, kọ silẹ fun ere ṣiṣe ati fun idaraya nigbati ọwọ ba dilẹ ati fun ẹkọ Igbẹsan lati ọdọ Ọlọrun wa. Bi ọwọ ba sọwọ pọ Ẹlẹṣẹ ki yio lọ laijiya.

Ṣugbọn Shakespeare ṣe ayipada diẹ ninu itan aiye Caesar ki o ba le ni igbadun diẹ ki o si ba le fa iwa ẹda yọ ninu rẹ. Caesar ti inu iwe ko nṣe olokunrun rara, akin ọkunrin ni ati alagbara julọ. Ṣugbọn Caesar ti inu iwe Shakespeare jẹ ojo enia, adẹbọ, olokunrun ati akuwarapa.

Ọkan ninu awọn enia ti orukọ wọn goke ninu iwe ere Shakespeare yi ni Brutus. Ọkunrin yi jẹ ẹniti Caesar fẹran pupọ o si fi si ipo ọla, o si bu ọla pupọ fun un. O dapọ mọ awọn ọlọtẹ lati pa ọrẹ rẹ, ọbẹ tirẹ lo si gbẹhin lara Caesar—Iyanu na pọ fun Caesar to fi kigbe wipe BRUTUS, IWỌ KẸ, o si ṣubu o ku loju kanna.

Cassius tun ni alagba ati ọlọla kan, ẹniti ohun rẹ si dunlẹ ni Romu : enia pẹpẹrẹ ni, on ni o si kọ mu imọran ati pa Caesar jade. On ati Caesar ti ni asọ diẹ, ki o to to akoko yi o si ni ijowu rẹ lọkan pupọ. Ẹ o ri ka bi Brutus ti jẹwọ pe Caesar ko ṣẹ, ṣugbọn ki wọn ba ni ẹjọ ijare lati pa, o ni ki wọn ro

Caesar bi ẹnipe ẹyin ejo ni to le ṣika lọla, ki wọn kuku pa ninu ẹyin. Apẹrẹ awawi ẹda ni eyi to mu mi niran owe Gẹsi kan to wipe "*Call a dog a bad name and hang him*" sọ aja lorukọ buruku kan ko ba le fokun fun lọrun pa.

Awọn miran ta tun darukọ wọn sinu iwe yi na ni Portia aya Brutus obinrin ti ẹwa rẹ rekọja ti awọn ẹgbẹ rẹ to si fẹran ọkọ rẹ de gere tobẹ ti o pa ara rẹ nigbati o ro pe o ti ku.

Calpurinia ni aya Caesar papa. O la ala pe nwọn gun ọkọ on lọbẹ loru mọju. O fẹran ọkọ rẹ pupọ ṣugbọn ko to ti Portia fun ọkọ rẹ.

Octavius Caesar ni ọmọ Ẹgbọn Caeser. O ti lọ si idalẹ nigbati gbogbo iyọnu wọnyi bẹrẹ ni Romu ṣugbọn o de si asiko wa ba iyọnu na, on ni o si gba ipo rẹ ti o di ọba kini ti a npe ni Augustus Caesar.

Mark Antony jẹ ọrẹ Caesar ati alagba kan ni Romu. Ọlọgbọn wẹrẹwẹrẹ enia ni. On lo kọ ru awọn enia si Brutus ati awọn Ọlọtẹ yoku. On ati Lepidus ati Octavius Caesar lo pin Ijọba Romu sọnọ mẹta ti o si njọba lori idamẹta tirẹ fun igba diẹ.

Caius Ligarius, ọkunrin olokunrun kan ti amodi ti jẹ lara papọ. O fun gbo o. Eyi fihan oniruru enia to wa ninu ọtẹ yi ati bi Cassius ti mu ki irira Caesar kun ọkan awọn enia gbogbo.

A o fimọ bayi. Awọn yoku ati ipa ti wọn ko ninu itan ere yi ẹ o ma ka a fun ara yin. Pataki ohun ti a fo sẹhin ni ilana ti Yoruba yi ni itumọ oniruru ọkan ẹda ti iru iwe yi ma ntọka si. Iru itọka bayi ni eko ti awọn ọkawe ma nfẹ lati ri ninu iwe "play" tabi ere ṣiṣe ba wọnyi. Nitori eyi ni awọn to nkọ iru iwe wọnyi ṣe nṣe akiyesi ẹda daradara ti wọn si ma nmu itan wọn rin lọna bẹ. O nfẹ ka ronu ṣe eto rẹ ni kiko ki ṣe ti iru eyi ti mo ṣe akiyesi ni sa kan ti awọn kan to fẹ kọ ere apilẹkọ ṣe ti wọn pejọ pelu ohun elo wọn ti nwọn nrin sọtun sosi, ti akọwe wọn nkọ eyiti nwọn ba nsọ silẹ l'oniruru, lẹhin ijọ melo kan ti ere ya ti nwọn ko gangan ati ilu oniruru lọ fi joye nibẹ. Kini awọn to lọgbọn iru ere yi ti nwọn si ma gbadun rẹ ti wi? Nwọn ni ko nilari

A kọ awọn orukọ to wa ninu iyipada yi gẹgẹbi a ti npe wọn ni ede Gẹsi ki o ba le rọrun fun wọn bi nwọn ba fẹ ka niti Gẹsi Caesar ki ṣe Kesari ṣugbọn Siza.

Mo ni lati ṣe idupẹ pupọ lọwọ awọn meji wọnyi Ọlatunji Adeṣọla ati Alfred Joshua awọn ọmọ ile iwe ni "High Class School" nidayi eṣi ti nwọn duro ti mi giri lati yi iwe yi pada si Yoruba, nigbati gbogbo awọn ti mo bẹ kọ patapata.

Apapọ ẹkọ ti ere yi kọ ni nipe Igbẹsan wa laiye yi dajudaju. Eyiti a o tun kọ ni yio ṣe apẹrẹ itumọ ọkan ẹda bi ara ti ma pa alara ninu aiye wa yi ti konko a si ma dun gbaro-gbaro.

E. T. J.

## Ere Kini. Iran Kini.

*Flavius ati Marullus ni Aṣoju awọn oṣiṣẹ ( Workmen ) ni ilu.*

---

*Larin ila Rome ni Falvius, Marullus ati awọn oṣiṣẹ ilu gbe duro pọ*

*Flavius* :—Ẹ gb'ọna ile yin lọ, ẹnyin oku ọlẹ wọnyi; ẹ kọja lọle.
Oni ha nṣe ọjọ ariya bi? Kinla! ẹ ko mọ pe bi oṣiṣẹ ẹ ko ni lati ma ṣanwọ rin laimu irinṣẹ nyin dani.
Iwọ fọhun, iṣẹ kili iwọ nṣe?

Oṣiṣẹ Kini :—Emi lẹ mbawi; Gbẹnagbẹna ni mi.

*Mar* :—Bantẹ awọ gbẹnagbẹna rẹ ati igi ọsunwọn ( Rulu ) rẹ da? Kini ha mu ọ wọ aṣọ isalẹ apoti rẹ?
Iwọ nkọ, iṣẹ kini iwọ nṣe?

Oṣiṣẹ Keji :—Ka sọ totọ alagba, bi a ba ma fi iṣẹ mi we ti oniṣe finifini, alugbagba ni mi.

*Mar* :—Ṣugbọn iṣẹ wo ni o nṣe? Da mi lohun tara.

Oṣiṣẹ Keji :—Ni iṣẹ lẹwi ti mo nṣe; mo rope mo le sọ fun ọ pe mo nsọ ogbologbo atẹsẹ bata di titun.

*Mar.* :—Ani iṣẹ wo ni o nṣe? Iwọ ọmọ buruku yi, iwọ nkankinkan yi iṣẹ kini t'rẹ ẹ?

Oṣiṣẹ Keji :—Jọwọ, mo bẹ ọ Ọga, maṣe binu si mi; ṣugbọn bi inu ba si bi ọ ma lẹ ọ.

*Mar.* :—Kili itumọ ede rẹ ni? Wa lẹ mi; iwọ ọyaju yi.

Oṣiṣẹ Keji :—Itumọ rẹ ni pe ma lu ọ gbagba.

*Flavius* :—O ye mi, iṣẹ alugbagba ni o nṣe tabi bẹ kọ?

Oṣiṣẹ Keji :—Bo ti ri gan nini. Ohun ti mo fi nṣiṣẹ jẹun ni olulu Emi ko nyọjusi iṣẹ on'ṣẹ kan, ibaṣe t'ọkunrin ibaṣe t'obinrin; olulu mi ni mo nla ni ọrọ; oniṣegun gbogbo bata ni mo nṣe. Bi ara bata ko ba da, ma wo san. Gbogbo ẹnikẹni ti o ba si ntẹ awọ bata mọlẹ ni o ngbadun iṣẹ ọwọ mi.

*Flavius*:—Kini ha mu ọ ti o ko fi lọ si ibi iṣẹ rẹ loni? Kini ha ṣe ti o nko awọn enia wọnyi tirẹ kakiri bayi?

Oṣiṣẹ Keji:—Alagba, otitọ ọrọ na gan ni eyi, lati gbo wọn ni bata, ki nba le ri iṣẹ pupọ ṣe. Ṣugbọn olori gbogbo rẹ ni pe a nṣe ariya loni lati lọ pade Caesar, ki a si ba a yọ ninu fukẹ iṣẹgun rẹ ti o nfẹ ṣe.

*Mar.*:—Kini ẹ ha nyọ le lori? Ilu melo lo gba fun Romu? Ọba melo lo mu lẹru wa sile to fi nṣe fukẹ wọlu?

Ẹnyin kukute igi wọnyi; ẹnyin okuta, ẹnyin nkan kinkan, agọ bi ọbọ; ẹnyin ọlọkan lile wọnyi, ẹny'n oku ika ara Romu.

Ẹ ko tun mọ Pompey mọ? Igba pupọ pupọ ha kọ ni ẹ ngun ori ogiri ati oke giga ati ile o'odi nla?

Ti ẹ nwọju lori tawa ati ferese ati lori oke garẹti;

Pẹlu awọn ọmọ wẹwẹ nyin lọwọ nyin, ti ẹ ti njoko nibẹ

Tọsan toru titi ẹ o fi ri ikọja Pompey ni ita Romu

Ti ẹ ba si ti ri yiyi kẹkẹ rẹ lokere,

Iho ayọ nla kọ ni ẹ nho?

Tobẹ ti odo Tiber fi ngbọn de isalẹ rẹ, fun ariwo ohun nyin lati kotokoto rẹ wa;

Ẹ ko ha lọ wọ aṣọ isalẹ apoti yin loni?

Ẹ ko ha si nṣe ariya bi?

Ẹ ko ha si ngbọn ododo si oju ọna, lati ṣe ẹyẹ fun ẹniti o nṣe ọṣọ fukẹ lori ẹjẹ Pompey na?

Ẹ ba ara nyin lọ le.

Ẹ sare lọ si ile nyin, ki ẹ si kunlẹ lori ekun nyin, ki ẹ si kepe awọn oriṣa nyin lati dawọ ajakalẹ arun ni duro, ti aimore nyin yio mu wa.

*Flavius*:—Ẹ tuka lọle nyin, ẹnyin ara ilu mi; ati nitori ẹṣẹ nyin yi.

Ẹ pe gbogbo awọn oṣiṣẹ ẹgbẹ nyin jọ, ẹ ko wọn lọ si eti odo Tiber ( Tayiba )

Ki ẹ le da omije oju nyin si inu omi rẹ,

Titi ti ibi afẹsẹwọ yio fi kun akunya.

( *Gbogbo awọn oṣiṣẹ wọnyi tuka* ).

Njẹ o ri bi agidi ọkan wọn ti yi pada,

Ẹbi wọn pa wọn lẹnu mọ patapata,

Wọn si nyọ lọ. Gbọna apa ọhun lọ si Capitol, emi yio gba ibi yi, ja gbogbo panti to wa lara ere Caesar kuro. Ti wọn fi ṣe ọṣọ si lara.

***Mar.***:—A ha gbọdọ ṣe eyi? Ma gbagbe pe oni ni ọdun " Lupacal."

*Flavius*:—Eyini ko kan; maṣe jẹki ẹyẹ iṣẹgun ki o wa lara awọn ere fun Caesar,

Emi na yio gba ihin gba ọhun, ngo si le awọn enia wọnni pada,

Ki iwọ na si ṣe bẹ gẹgẹ ni ibiti o ba ri pe wọn ṣu si;

Bi a ba le tu awọn iyẹ titun Caesar wọnyi kuro,

Ki yio le fo ju bi o ti yẹ lọ.

Bi bẹkọ yio fo ga ju ibiti oju le de lọ,

Ti yio si fi ibẹru si gbogbo wa lara.

## Ere Kini. Iran Keji.

*Caesar* :—Calpurnia !

*Casca* :—Arere o, Caesar nsọrọ.

*Caesar* :—Calpurnia !

*Calpurnia* :—Emi re o, Oluwa mi.

*Caesar* :—Duro si ọgangan Antonius, nigbati o ba nsure rẹ, Antonius !

*Antony* :—Caesar, oluwa mi.

*Caesar* :—Ma ṣe gbagbe ninu isure rẹ, Antonius, lati fọwọ kan Calpurnia. Nitori awọn alagba wa nsọ pe awọn agan ti awọn elere ba fọwọkan ninu ere didara yi yio gbọn agan wọn nu.

*Antonius* :—Emi yio ranti. Nigbati Caesar ba wipe eyi ni ṣiṣe, o ti di ṣiṣe nini.

*Caesar* :—Ẹ ṣe kalọ. Ki a ma fi aṣẹ kankan silẹ laiṣẹ.

*Alafose* :—Caesar !

*Caesar* :—Tani pe ẹ ?

*Casca* :—Jẹki gbogbo ohun pa ; Ẹ jẹ ka gbohun o.

*Caesar* :—Tani oluwarẹ to wa ninu agbo to npe orukọ mi ? Mo gbọ ohun kan to nlu goro ju gbogbo ohun elo orin lọ, to nkigbe pe Caesar : ma sọrọ ẹnu rẹ, Caesar ti yi pada lati gbọ.

*Alafose* :—Caesar ! Ṣọra rẹ ni ọjọ kẹdogun oṣu March.

*Caesar* :—Tani oluwarẹ ?

*Brutus* :—Alafọṣẹ kan lo nkilọ fun ọ pe ki o ṣọra rẹ ni ọjọ kẹdogun oṣu March.

*Caesar* :—Ẹ jẹki o duro niwaju mi : ẹ jẹki nri oju rẹ.

*Cassius* :—Ọmọkunrin yi kuro larin ero : wo Caesar loju.

*Caesar* :—Ewo lo ha wi fun mi nisisiyi? Tun sọ lẹkan si.

*Soothsayer* :—Ṣọra rẹ ni ọjọ kẹdogun oṣu March.

*Caesar* :—Alala, jẹki a fi silẹ, ma ba ara rẹ lọ.

(*Fere dun, gbogbo enia lọ afi Cassius ati Brutus*).

*Cassius* :—Iwọ ki yio ha lọ wo awọn ere yi?

*Brutus* :—Emi kọ.

*Cassius* :—Mo bẹ ọ : jọ lọ.

*Brutus* :—Ere ko wa ara mi. Iru ẹmi ọyaya ti Antony ni ko si ni ara mi. Ma jẹki emi da ọ duro lati tẹ ifẹ rẹ lọrun, Cassius. Emi yio fun ọ ni aye lati lọ.

*Cassius* :—Brutus, mo nṣe akiyesi rẹ ni titun yi pe, emi ko ri ifẹ ati oju rere rẹ ni, ti o ma fi nwo mi latijọ; ọwọ lile ati ifẹ tutu lo fi mba ọrẹ rẹ ti o fẹran rẹ pupọ lo nisisiyi.

*Brutus* :—Cassius, ki a ma tan ara wa jẹ, bi oju mi ba yipada si ẹnikẹni, Cassius, mọ pe ibinu si ara mi lo mu ki oju mi koro si ẹlomiran. Nitotọ inu mi ko dun si ara mi ni titun yi; ṣugbọn eyini jẹ mọ ohun ti o kan ara mi papa nikan lo mu mi lati ma huwa bayi. Nitorina, ki ẹnyin ọrẹ mi ma binu rara, papa Cassius iwọ ọkan ninu wọn. Ki o ma ṣiro ainani mi si ohunkohun ju pe ọkan Brutus papa lo mba ara Brutus ninu jẹ, to si jẹki oju rẹ koro si ẹlomiran.

*Cassius* :—Njẹ Brutus, mo ṣe aṣiro ohun ti o nfarada, eyi to ti mu mi fi ọkan tẹ ero pupọ mọlẹ, awọn ero nlanla. Wa sọ fun mi Brutus mi, iwọ ha le fi oju ara rẹ ri oju rẹ?

*Brutus* :—Nda o, Cassius, nda o Oju ko le ri ara rẹ daradara, a fi ninu ohun to ba ndan, tabi ninu ohun miran.

*Cassius*:—Bẹ gẹgẹ lori: o si jẹ ohun ẹdun pupọ Brutus ti o ko ni iru jigi yi ti yio fi iri oju rẹ totọ han ara rẹ ti iwọ yio fi le ri baibai iyi ara rẹ.

*Brutus*:—Eredi ariwo nla yi? Ẹru ba mi pe awọn enia yan Caesar bi ọba wọn.

*Cassius*:—A! Ẹru eyi ha mba ọ? Bi bẹni, iwọ yio ha mu mi ro pe iwọ ko fẹ ki Caesar jọba.

*Brutus*:—Emi ko fẹ ẹ bẹ rara Cassius. Pẹlu gbogbo rẹ mo fẹran Caesar pupọ. Ṣugbọn kini ṣe ti o fi da mi duro pẹ bayi nihin? Kini ohun pataki ti o fẹ sọ fun mi? Bi o ba ṣe pe ohun ti yio mu anfani wa fun gbogbo ilu wa yi ti ṣiṣe rẹ yio mu anfani ilu wa lọwọ kan, tabi iku ọmọ ilu lọwọ keji. Emi ki yio bikita eyikeyi nitori ki awọn irunmọlẹ ṣe bẹ gẹgẹ si mi. Bi emi ko ba fẹran anfani ilu ju bi mo ti bẹru iku lọ.

*Cassius*:—Mo mọ pe bẹ gan ni tirẹ ri Brutọsi (Brutus). Gẹgẹbi mo ti mọ iwa rẹ si, ki nma ba ọrọ bọ: Ọla tabi Iyin ni pataki ọrọ mi.

Emi ko mọ bi iwọ ati awọn enia yoku ti nro ti aiye wa yi si,

Ṣugbọn fun ti ara mi, o san fun mi ki nku,

Ju ki nwa laye labẹ ibẹru enia bi emi papa.

Bi a ti bi ẹru la bi ọmọ: bi a ti bi Caesar la bi temi tirẹ.

Awa mejeji ti njẹun, a si le fi ara da otutu bi Ceasar.

O mu mi ranti ọjọ kan ti otutu mu ti iji nja,
Ti omi odo Tiber si nja ti o si nru bolẹ.

Caesar pe mi wipe Kasiọsi njẹ o le ba mi so iṣan omi riru yi, ki o si jẹ ki a sọda si odi keji.

Tohun tẹnu yi mo bẹ sinu iṣan na temi ti ihagaga mọra mi.

Mo si ni ki o ma tẹle mi.

Bẹ gẹgẹ lo si ṣe, ṣugbọn a nso tipatipa :

Bi o ti nru to bẹ ni a nfi igboya bi si apakan, Ṣugbọn ki a to sọda si odi keji ti a ifi ẹnu da. Ceasar kigbe soke pe, Cassius gba mi o, bi bẹ kọ ma ri.

Emi na bi Aeniasi Oluṣẹdalẹ wa ti gbe arugbo baba rẹ Anchises si ejika rẹ jade kuro ninu ewu ina.

Bẹni mo gbe Caesar, ti o ti rẹ, jade kuro ninu igbi odo Tiber.

Ọkunrin yi ni o wa di oriṣa, ti emi Cassius si di enia yẹpẹrẹ.

Ti mo si ni lati wolẹ bi Caesar ba ṣeṣi ṣẹju si mi.

Ni sa kan ti otutu mu u ni Spain ti amodi otutu na wa lara rẹ,

Mo ṣe akiyesi bi o ti ngbọn, nitotọ oriṣa yi ngbọn, Ete ojo yi funfun gbo o ; ati oju rẹ ti ndẹruba gbogbo aiye ma yipada o ; Mo gbọ bi o ti ngbin fikanfikan Ani ahọn rẹ ni, ti o fi npaṣẹ pe ki awọn ara Rome fi iye silẹ.

Ki nwọn si kọ awọn ọrọ on si inu iwe wọn ;

Ahọn na ni o nfi nsọ pe "Fun mi ni omi diẹ mu Titinius," bi olokunrun ọmọbinrin. O jẹ ohun iyalẹnu fun mi Ẹnyin Oriṣa, pe iru enia alailera bayi di aṣiwaju gbogbo wa ni Romu l'aiye yi.

Ti o si nikan gba ọla ati ẹbun rẹ.

*Brutus* :—Ariwo miran ni nwọn tun pa yi.

Mo mọ pe gbogbo atẹwọ ti nwọn pa yi, lori Oye ati Ọla titun

Ti nwọn gbe fun Caesar ni.

*Cassius*:—A! Arakunrin, ọkunrin yi dakata lori aiye kekere wa yi

Gẹgẹbi ere Colossus; awa si di enia yẹpẹrẹ.

Ti a nrin ni abẹ ẹsẹ rẹ nla, ti a nyọju fofofo.

Lati ri ara wa bi sare oku ti a ntẹ mọlẹ.

Ẹda papa lo ni kadara ara rẹ lọwọ.

Ẹbi na, Brutus, ki ṣepe bi a ti yan ni;

Ṣugbọn lọwọ arawa lo tẹ si ti a fi di ọmọ abẹ.

"Brutus" ati "Caesar" kinni wa ninu orukọ Caesar yẹn?

Bawo ni orukọ yẹn ti ṣe le dun ju tirẹ lọ?

Kọ wọn pọ. Tirẹ na dara bakanna.

Pe wọn wo, tirẹ na dun lẹnu bakanna.

Wọn nwọn wo, o tẹwọn bakanna. Fi nwọn ṣepe fun enia, orukọ tirẹ yio ba enia lẹru were-were bi ti Caesar. Njẹ mo fi gbogbo awọn oriṣa aiye yi bu pe kinni Caesar wa yi njẹ ti o fi di emọ bayi.

A! Iran wa yi ẹtẹ ba a. Romu ọmọ ọlọla ti tan ninu rẹ.

Nigbawo ni akoko na tun de lẹhin ikun omi nla ni?

Ti a tun gburo pe enia kan pere lo tun ku laiye.

Nigbawo ni awọn opitan Romu tun le sọ fun ni pe, enia kanṣoṣo pere ni odi rẹ yi ka; afi nisisiyi;

Ṣugbọn Romu ha ni ilu yi nitotọ, o ha ni aye to nisisiyi? Nigbati o jẹpe enia kanṣoṣo pere ni a ngbẹ orukọ rẹ?

A! Iwọ ati emi ti gbọ bi awọn baba wa ti sọ pe,

Brutus kan ti wa nigba atijọ ti ko jẹ gba
Ki Eṣu papa wa gbilẹ bi Ọba ni Romu.

*Brutus* :—Niti-fifẹ mo mọ pe o fẹ mi ; mo si nri
Firifiri ohun to fẹ sun mi si.
Gẹgẹbi mo ba ti nro ọrọ yi si ati akoko igba yi si, a o ma tun u sọ, ki nṣe nisisiyi
Tifẹtifẹ ni mo bẹ ọ ma ṣe ti sọ si. Ohun ti o wi ma fi si ero,
Ohun ti o ba fẹ sọ ma fi suru gbọ ọ, ma wa akoko lati gbọ,
Ati lati fi esi si ohun ribiribi ti o sọ yi,
Titi igbana ka ma run ọrọ na lẹnu. O san ki Brutus jẹ ara oko
Ju pe ko pe ara rẹ li ojulowo ọmọ Romu lọ.
Ki igba ṣi ma lo wa bi o ti nlo wa nisisiyi lọ na

*Cassius* :—Inu mi dun gidigidi nitoripe ọrọ bi ere ti mo sọ yi ka Brutus lara pupọ bi aṣara okan.

*Brutus* :—Wọn ti pari ere, Caesar si npada bọ.

*Cassius* :—Bi wọn ba nkọja, ko fa Casca leti aṣọ, on a si sọ pẹlu ikara ohun pataki to ṣẹlẹ loni fun ọ.

[ *Caesar tun wọle lọ t'on ti awọn Ero rẹ.* ]

*Brutus* :—Emi yio ṣe bẹ, ṣugbọn kiyesi, Cassius, oju Caesar tubọ nkoro si,
Awọn ti o nbọ lẹhin rẹ si dabi awọn ọmọ t'a ba wi.
Ẹrẹkẹ Calpurnia funfun. Oju Cicero si pọn wo bi ina. Gẹgẹbi iti ma pọn bi ina
Ni Capitol ; ati bi ti olofintoto nigbati nwọn ba mu u binu ni ajọ igbimọ.

*Cassius* :—Casca yio sọ bi ọrọ na ti jẹ fun wa.

*Caesar* :—Antony!

*Antony* :—Caesar?

*Caesar* :—Jẹki awọn ti o sanra yi mi ka. T'oju wọn kunna, ti irun wọn ko di koko, ti wọn ko si fi alalẹ ṣaisun.

Ẹ ko ri Cassius to wa lọhun ni
Bi o ti gbẹ to si ri ṣoṣogiro, o ronu pupọ ju!
Oni jamba enia ni iru awọn enia bẹ.

*Antony* :—Maṣe bẹru rẹ, Caesar ki ṣe oni jamba ọmọluwabi, ara Romu ni, o si ni inu rere.

*Caesar* :—Iba dun mọ mi bi o tunbọ sanra ju yi lọ; ṣugbọn nko bẹru rẹ.

Bi o ba ṣe pe Caesar jẹ ẹniti ẹru le ba,
Nko mọ ẹniti nba sa fun ju.

Cassius pẹpẹrẹ ni lọ. O kawe ju, o ni akiyesi pupọ.

Iṣe ẹni ni a fi mọ iwa ẹni; ki lọ sibi ere ṣiṣe bi rẹ Antony,

Ki fẹ gb'orin s'eti. Agbara ni fi r'ẹrin, a si rin musẹ bi ẹniti o nfi ara rẹ ṣ'ẹsin

A si wo ohun ti iba pa a lẹrin bi nkan bintin.

Ọkan iru enia bayi ki balẹ, bi wọn ba ri ẹni ti o ju awọn papa lọ.

'Tori eyi ni jamba wọn fi pọ. O ṣe ohun irọrun fun mi lati sọ ohun ti enia ni lati bẹru ju ohun ti emi ni lati bẹru lọ. Nitori nko fi ẹkan ṣai jẹ Caesar; Ma bọ lọwọ ọtun mi nitoripe eti yi di. Ki o si sọ fun mi nitotọ iru enia wo l'o ro o si.

*Fere dun, Caesar ati awọn ara rẹ jade.*

*Casca* :—O fa mi li aṣọ lẹkan, o ha ni ọrọ ba mi sọ ni ?

*Brutus* :—Bẹni, Casca : sọ ohun ti o ti ṣẹlẹ loni fun wa ti o mu Caesar fajuro bayi ?

*Casca* :—Kinla ! Mo ṣebi o wa lọdọ rẹ, tabi bẹ kọ ?

*Brutus* :—Bi o ba ṣe bẹni, Casca, emi ko ni bi ọ li ohun ti o ti ṣẹlẹ.

*Casca* :—Ha a ! ade ni wọn fi lọ ọ ; nigbati wọn si fi lọ ọ O fi ẹhin ọwọ ṣi kuro li ori rẹ bayi : eyi li o mu awọn Enia pariwo.

*Brutus* :—Kini padi ariwo ori ekeji ?

*Casca* :—Ṣebi fun nkan kan na ni.

*Cassius* :—Ẹmẹta ni nwọn pariwo ; kili ariwo ikẹhin fun ?

*Casca* :—E ṣe ẹwẹ, fun nkan kan yi na ni.

*Brutus* :—Njẹ ẹmẹta ni nwọn fi ade lọ ?

*Casca* :—Mo bura bi bẹ kọ ; ẹmẹta ni o si ti si apakan, ṣugbọn o ṣi nfa ọwọ rẹ sẹhin diẹdiẹ. Awọn enia a si ho ge e soke bi o ba ti fi ọwọ ti i.

*Cassius* :—Ṣugbọn tani tilẹ nfi ade lọ ọ ?

*Casca* :—O wi kọ, Antony ni.

*Brutus* :—Farabalẹ Casca ; ki o si sọ fun wa bi nwọn ti ṣe.

*Casca* :—Kuku ni ki nwa pokun so ; ju pe ki nwa sọ bi nwọn ti ṣe.

Nwọn ntan ara wọn jẹ ni. Emi ko ṣe akiyesi rẹ ;

Mo kan ri Mark Antony bo ti nfi ade lọ Caesar (ko tilẹ nṣe ade totọ, ṣugbọn ara awọn ade kekeke ni, bi ade kan bayi ṣa ni) bi mo ti wi lẹkan. O yẹ ti lẹkini, ṣugbọn mo ro pe iba fi tayọtayọ gba a. Lori ẹkeji o vẹ ẹ ti ; ṣugbọn o fa tikọ lati fi ọwọ rẹ gbe e kuro, o si dabi eni pe ko fẹ gbe kuro lori mọ ;

ani nwọn tun fi lọ ọ lẹrinkẹta (o tun fi ọwọ ti i kuro lori ẹkẹta) ṣugbọn lori gbogbo kikọ rẹ yi ni o mu ki awọn enia ma pariwo, ti nwọn si fi ọwọ wọn pakura yẹn patẹwọ tobẹ ti nwọn fi nju fila otutu olorun wọn soke. Ēmi buruku wọn pọ tobẹ nitori Caesar kọ ade ti o fi fẹ fun Caesar lọrun pa.

Nitori ti o ṣubu o si daku; ṣugbọn ni temi,

Ẹru ba mi lati rẹrin ki emi na ma ba fa orun buburu ẽmi wọn si imu.

## ERE KINI. IRAN KEJI.

*Cassius*:—Ṣugbọn farabalẹ mo bẹ ọ, kinla! Caesar daku?

*Casca*:—O ṣubu larin ọja, o nyọ ifofo lẹnu, ko si le sọrọ.

*Brutus*:—O da bi enipe warapa nba ja.

*Cassius*:—Agbẹdọ; warapa ko ba Caesar ja, ṣugbọn iwọ ati emi ati Casca olotọ enia yi ni warapa nbaja.

*Casca*:—Nko mọ nkan to ro to fi wibẹ, ṣugbọn eyi ti o da mi loju ni pe Caesar ṣubu.

Bi ko ba jẹ pe bi awọn enia jatijati wọnyi ti npatẹwọ ti wọn si npariwo ge,

Gẹgẹbi o ti tẹ wọn lọrun si, tabi ko jẹ didun inu wọn, bi wọn ti nṣe fun awọn ti o nṣire ni ile ere,

Ki ẹ pe mi ni opurọ.

*Brutus*:—Kilo tiwi nigbati oju rẹ walẹ?

*Casca*:—Gba mi gbọ, ki o to ṣubu, nigbati o ri pe inu awọn enia dun

Si kikọ ti o kọ ade; mo ri ti o tu kotu awọtẹlẹ rẹ, ti o si yọ ọrun rẹ sita pe ki wọn ge e.

Bi mo ba jẹ ọyawọ enia ni ti mo si gba ọrọ rẹ gbọ, awọn enia iba ti pa mi danu. Bẹ lo si kuwarapa lọ fã;

Nigbati oju rẹ walẹ, o wipe, bi on ba ti ṣi nkankan ṣe,

Tabi ti on ba ti ṣi ọrọ kan sọ,

On fẹ ki awọn Janmọ gba pẹ ailera on ni. Awọn iya agba mẹta tabi mẹrin kan ti wọn wa nibiti mo gbe duro si

Wipe, "O maṣe o! ẹru 're, wọn si dariji tọkantọkan, ṣugbọn a ko le ka tiwọn yẹn si rara.

Bi Caesar gun iya wọn lọbẹ pa bi wọn ti ma wi gan na nini.

*Brutus*:—Lẹhin na kọ lo wa jade pẹlu oju fifa ro?

*Casca*:—Bẹni.

*Cassius*:—Njẹ Cicero fọ ohun si?

*Casca*:—Bẹni, on nsọ ede Heleni (Greek).

*Cassius*:—Kili o nsọ le lori?

*Casca*:—Eke enia ni ma jẹ, ti mba ni nkan to wi ye mi;

Nko ni to ẹniti o le wo ọ loju; ṣugbọn awọn ti o ye, ti nwọn si gbọ rẹrin,

Wọn si gbọn ori wọn; ṣugbọn niti emi, Heleni ni mo mọ si. Ẹ gbọ ohun miran to tun ṣẹlẹ; Nwọn yẹ Flavius ati Marullus loye nitoriti nwọn bọ ohun ẹṣọ ti nwọn fi kọ awọn ere Caesar lọrun.

O digboṣe; nwọn tun ṣe yẹyẹ miran ti nko ranti.

*Cassius*:—Ṣe wa wa ba mi jẹun lalẹ yi Casca?

*Casca*:—Emi ko ni le wa, nitoripe mo ti ṣe ileri lati lọ si ibikan lalẹ yi.

*Cassius*:—Ṣe wa wa ba mi jẹun lọsan ọla?

*Casca*:—Bẹni. Bi Ọlọrun ba dami si; bi ara rẹ ba gba a; ti onjẹ rẹ ba si ṣe jẹ.

*Cassius*:—O dara. Ma ma reti rẹ.

*Casca*:—Ma reti mi o. Ẹyin mejeji o digboṣe o.

*Brutus*:—Iru ọdẹ wo ni eleyi wa nya yi; o yara fafa nigbati o nlọ si Ile-iwe (school).

*Cassius*:—Bakanna lo nyara nisisiyi.

Bi ohun nla tabi ohun pataki kan ba wa ni ṣiṣe.

Ṣugbọn nisisiyi o mọmọ nfa kũn ni; iwa ara oko rẹ yi lo dabi ọbẹ si ọgbọn rẹ.

Ti o nmuni gbadun rẹ; to nmu ki ọrọ rẹ ma wun ni

Siwaju ati siwaju.

*Brutus*:—Bẹ gan lori. Nisisiyi, emi yio fi ọ silẹ lọ. Ni ọla, ti o ba fẹ bami sọrọ yi, emi yio wa ba ọ nile.

Tabi ti o ba fẹ wa bami nile, emi yio si duro dẹ ọ.

*Cassius*:—Bẹni nma ṣe, ko to to igbana ko fi ti ọrọ ilu wa yi si ero. (Brutus jade) A! Brutus, ọmọ enia ni ọ nitotọ; ṣugbọn mo wa ṣakiyesi pe

A le yi ọ lọkan pada. Nitorina lo yẹ pe ki ọmọluwabi ma ba ọmọluwabi ẹgbẹ rẹ rin.

Nitoripe ko si ẹda to le duro tobẹ ti ẹda ko le tan. Caesar ko fẹran mi rara, ṣugbọn o fẹran Brutus

Bi o ba ṣepe emi ni Brutus ati ki Brutus si jẹ Cassius, ko ni le tan mi. Emi a fi iwe fun ọpọlọpọ enia kọ lalẹ yi.

Ti nwọn yio ju si oju fereṣe rẹ, bi ẹnipe ọtọtọ enia ninu awọn bọkinni ilu lo kọ ọ.

Ti yio si jẹ iwe ti yio tọka si iru ọwọ nla ti Rome ni fun orukọ Brutus, ninu eyiti a o si tọka iwọra ti Caesar ni. Lẹhin na ki Caesar ko fo ko niṣo, bi ọwọ ko ni ba a, tabi bi oju rẹ ko ni ri mọmọ.

## Ere Kini. Iran Keta.

*Cicero* :—K' alẹ o Casca ; o ti sin Caesar dele ?

Kiniṣe ti o nmi hẹlẹhẹlẹ ti o si nranju bayi ?

*Casca* :—Njẹ ẹru ko ba ọ bi gbogbo agbaiye ati ọrun ti nmi bi ohun ti ko lẹsẹ nlẹ. Ha ! Cicero.

Mo ti nri iji nla nja nigbati atẹgun rẹ nla koko inu iroko.

Mo si ti ri okun ti nru ti o si nho pẹlu igbi rẹ ;

Ti o si ru soke bi eyiti o ma kan ọrun.

Ṣugbọn nko ri iru eyi ri afi ni alẹ yi, afi nisisiyi. Ti iji nja ti ọrun si nkan ina. O le jẹ pe ija igboro wa lọrun tabi li aiye yi. Bi bẹ kọ a jẹ pe awọn irunmọlẹ nbinu nitori ọyaju awọn ọmọ araiye.

Tabi awọn ọmọ araiye mu awọn irunmọlẹ binu tobẹ ti nwọn fẹ rọlu aiye. Kiniṣe ?

*Cicero*:—Hẹn : O tan tabi o ku, tabi o ju bẹ lọ ?

*Casca*:—Ọmọde kan, ẹru ni. Iwọ yio mọ ọ ti o ba ri.

O gbe ọwọ osi rẹ soke ti o gbina ti o si njo bi ogun ogunṣọ papọ.

Bẹni ọwọ rẹ ko jona ko si ni apa ina lara.

Lẹhinna, nko ti fa Ida mi yọ ni mo pade kiniwun kan leti Capitol, ti o ranju mọ mi.

Ti o si kun kọja mi lai pami lara.

Lori okiti kan, li awọn ọgọrun obinrin bi iwin ti ẹru ti fẹ paku, nbura pe nwọn ri enia pẹlu ina lara ti nwọn nrin soke sodo larin ita. Ati pe lana, Owiwi kan ba si orule ọja lọsan gangan.

O nhu, o si nhan. Nigbati ohun abami bayi ba papọ, ki ẹnikẹni ma sọ pe "Amuwa Ọlọrun ni nwọn jẹ."

Nitori mo gbagbọ pe ohun abami ni nwọn fun Ilu ti nwọn tọka si.

*Cicero* :—Nitotọ, akoko yi jẹ asiko ti o yatọ.

Ṣugbọn ẹnikẹni le tumọ nkan si bi o ti wu u. Li ọna ti o yatọ si bi nkan na ti ri.

Njẹ Caesar yio wa si Capitol lọla ?

*Casca* :—Yio wa : nitori o ranṣẹ si Anthony pe

Ki o ranṣẹ si iwọ Cicero pe on yio wa si ajọ lọla.

*Cicero* :—Njẹ, o darọ ni yẹn, Casca. Ko yẹ ki enia ma rin

Labẹ oju ọrun ti ko sunwọn yi.

*Casca* :—O digba o Cicero. ( Cicero jade lọ ).

*Cassius* :—Tani wa nibẹ ?

*Casca* :—Ara Rome kan ni.

*Cassius* :—Mo mọ ohun yi : ti Casca ni.

*Casca* :—O mọ ohun na nitotọ, Cassius ; iru alẹ wo leyi ?

*Cassius* :—Ko buru na fun ẹniti o ba nṣotọ.

*Casca* :—Tani mọ pe ọrun le dẹruba enia bayi ?

*Cassius* :—Awọn ti o mọ pe aiṣedede aiye wa ti pọ ni.

Ni ti emi mo ti rin kakiri igboro,

Mo si ti fi ara mi sọfa fun alẹ elewu yi.

Mo si ṣi aiya mi silẹ gbayawu fun ẹdun ara, bi o ti ri mi ti mo ṣe yi, Casca ;

Nigbati manamana ba si kọ mana, emi a si kọ aiya si ina rẹ, ( ki o ṣe ohun ti o le ṣe ).

*Casca* :—Ṣugbọn ki lo ṣe ti o nfi ara rẹ wewu ara bayi ?

Ipo ẹda ni lati bẹru ati lati ma gbọn nigbati awọn oriṣa nla ba nfọhun kikankikan lati ọrun wa bayi !

*Cassius* :—O ko tilẹ loye lori, Casca, o ko tilẹ ni ẹmi itara

Ti ara Rome ma ni lara? Bi o ba tilẹ ni, o nwo su bi ẹniti ara rẹ ko ya.

O si dabi ẹnipe ẹru mba ọ. O si nwo tiyanu-tiyanu

Lati mọ ohun to da ọrun ru. To ba ronu nitotọ lati mọ ohun to da nkan wọnyi silẹ,

Ki lo mu manamana wọnyi wa, kilo mu awọn oku ji dide,

Kilo mu gbogbo awọn ẹiyẹ ati ẹranko ṣọra, kilo sọ awọn agba di ope bi ọmọde, ti o si mu awọn ọmọde lati ronu bi agba,

Kiniṣe ti awọn nkan wọnyi si yapa kuro lọna wọn? Iwọ yio ri pe

Lati ọrun lati fun wọn lagbara yi lati fi wọn ṣe ohun ẹru ati ohun ikilọ

Fun ewu nlanla ti mbọ wa.

Casca : mo le darukọ ẹnikan fun ọ nisisiyi to dabi alẹ buburu yi

To nsan ara to nkọ manamana, to ṣi sare oku to si mbu ramuramu bi kiniwun

Ti o wa ni Capitol, ẹniti ko ni agbara kan ju ti enia lọ,

Ti ko si ni agbara lati da ohunkohun ṣe ju ti emi tirẹ lọ;

Sibẹsibẹ o ti di emọ

O si ti di ẹru gẹgẹ bi irikuri ti o yọ lalẹ yi.

*Casca* :—Ẹhẹn, Caesar lo ntọka si tabi bẹkọ Cassius?

*Cassius* :—Ẹnikẹni to wu ko jẹ, nitoripe awọn ara Rome to wa nisisiyi

Ni apa ati ẹsẹ gẹgẹbi awọn baba wa atijọ, ṣugbọn anu ṣe mi

Fun akoko ti a wa yi. Ọkan ti awọn baba wa ni ti ku ninu wa

Ọkan awọn iya wa lo ku ti a fi nṣe ibẹ loni; iya ati ifarada wa yi fi han pe obinrin ni gbogbo wa da.

*Casca* :—O ye mi; awọn agbagba fẹ fi Caesar joba lọla, Yio si ma de ade rẹ lori omi ati lori ilẹ nigba gbogbo lẹhin odi, a fi nihinyi—ni Italy.

*Cassius* :—Mo mọ ibiti ma ma san ida mi si wa yi o.

Cassius yio gba ara rẹ la lọwọ ẹru, nitori eyi ni ẹ ṣe nsọ alailera di alagbara, ẹnyin irunmọlẹ

Nitori eyi lẹ si ṣe nṣẹ apa awọn omuroro ọba Ile ti a fi okuta kọ tabi ogiri ti a fi idẹ ṣe tabi ile ailoju

Tabi ọja irin ko le da agbara tọkan duro. Ṣugbọn ẹniti aiye yi ba su ko le ṣe alairi ọna

Ti o fi fi silẹ. Ti eyi ba ye mi, ti gbogbo enia ba si mọ iru omuroro iwa ti mo nfi ara da

Mo le gba ara mi lọwọ aiye yi nigbati o ba wu mi.

*Casca* :—Emi na le ṣe bẹ pẹlu. Bẹ gẹgẹ ni gbogbo onde le fi ọwọ ara rẹ gba ara rẹ la kuro ninu ide.

*Cassius* :—Bi o ba jẹ bẹ lo ri, bawo ni Caesar ṣe di alaṣẹ? Anu rẹ ṣe mi. Mo mọ pe fun ti ara rẹ Caesar ki ba ti sọ ara rẹ di koriko

Bi ko ba ṣe pe o ri pe awọn ara Rome ti di Agbunrin. Awọn ti wọn ba fẹ ki ina tete gberan lo ma nfi koriko gbigbẹ da. Kini Romu wa da yi o? Iru iwọrọkun, panti ati wọlọwọlọ wo ni Rome yio da nigbati o ba di pe iru Caesar ndi nkan ni

Romu? Ṣugbọn ibinu kili o mu mi sọ yi? Boya mo tilẹ nsọ ọrọ yi loju ẹni to ti di ẹru ni. Bi o ba ṣe pe bẹni, esi ti fi ara rẹ, ṣugbọn mo ti dira tan f'ewu, emi ko si kọ iku.

*Casca*:—Casca li o mba sọrọ, iru Casca ki si ṣe ẹlẹnu foro;

Di mi lọwọ mu ki o si mu imọran wa bi awa yio ti ṣe gba ara wa silẹ lọwọ ibanujẹ wọnyi?

Ibikibi ti ẹ ba si rin jina de ẹsẹ mi yi yio de ibẹ.

*Cassius*:—Adehun kan ni a ṣe yi,

Casca, mo fẹ ki o mọ pe mo ti fi imọran yi

Lọ diẹ ninu awọn enia nla wa ni Romu lati ba mi dawọ le iṣẹ nla yi

To ni ewu ti o si ni iyi ninu. Mo si mọ pe awọn kan duro de mi ni ẹnu Iloro Pompey.

Nitoripe nisisiyi, tori ẹru alẹ yi

Ode a da pupọ, oju ọrun si buru gẹgẹ bi iṣẹ ti a ni lọwọ lati ṣe—iṣẹ ẹjẹ, iṣẹ ina ati iṣẹ to l'ẹru nla yi.

*Casca*:—Sun mọ'bi na, ẹnikan li o nrin pẹlu ikanju bọ yi.

*Cassius*:—Cinna ni; irin rẹ ni mo fi mọ ọ, ọkan ninu awọn ọrẹ wa ni. Cinna ma wolẹ, Cinna nibo lo nkanju lọ bayi?

*Cinna*:—Mo nwa ọ lọ ni. Tani yi? Njẹ Mettelus Cimber kọ yi?

*Cassius*:—On kọ. Casca ni; ọkan ninu ara wa ni

Ninu imọran ọtẹ yi. Njẹ wọn ko ha nduro de mi bi, Cinna?

Wi fun mi.

*Cinna*:—Inu mi dun fun eyi, iru alẹ buburu wo ni eyi?

Awọn meji tabi mẹta ninu wa ti ri irikuri.

*Cassius*:—Nję nwọn ko ha nduro de mi bi? Sọ fun mi.

*Cinna*:—Bẹni, nwọn nduro de ọ. A! Cassius, o ba ję le fa Brutus sinu imọ yi.

*Cassius*:—Ki ọkan balę Cinna mi. Gba iwe yi ki o fi si ori aga aṣaju (Brutus).

Nibiti Brutus ko ni ṣe alairi i, gba oju fereṣe ju sile rę.

Fi ate lę eyi mọ ara ere Brutus, nigbati o ba ṣe gbogbo iwọnyi tan,

Ki o pada wa si ẹnu iloro Pompey; nibiti iwọ yio ba gbogbo wa. Nję Decius Brutus ati Trebonius wa nibę?

*Cinna*:—Gbogbo wọn ni o wa nibę, afi Mettelus Cimber ti o wa ọ lọ sile.

O dara. Emi yio tete lọ ki nsi fi awọn iwe wọnyi si ibi ti ẹ wi.

*Cassius*:—Bi o ba ṣe eyi tan ki o wa ba wa ni ile ere Pompey.

Wa sunmọ ibi Casca, temi tirę yio lọ ri Brutus nile rę ki ilę to mọ; a ti gba idamẹta ninu ọkan rę tan;

Nigbati a ba tun sọlu, gbogbo rę yio ję tiwa.

*Casca*:—A! ifę rę pọ lọkan gbogbo enia; ati iru ohun ti nwọn iba ka bi aṣiṣe mọ wa lęsę nwọn a foju fo o da bi ohun rere fun Brutus: Bi ẹnipe iwo rę lasan nsọ ibi di rere.

*Cassius*:—Niti on papa ati iyi ara rę ati bi o ti yę ki o ję ọkan ninu wa lo ti wi ni Ę ję

Ki a ma lọ; nitoripe ọganjọ ti gan kọja,
ki ilę si to mọ, awa o lọ ji i loju orun a o si mọ inu rę.

## Ere Keji. Iran Kini.

*Brutus* :—Kini de, Lucius, kini de?

Emi ko le sọ bi ilẹ ti mọ to nisisiyi nipa wiwo ibiti irawọ rin de.

Lucius, mo npe ọ, dide, emi ibajẹ le ri enia bami wi

Pe mo ṣe nsun fọnfọn bi tirẹ yi, nigbawo ni wa dide?

Lucius dide. Kini ṣe ẹ Lucius? Nigbawo ni wa laju?

Mo npe ọ Lucius Kini ṣe ọ, ji kẹ!

*Lucius* :—O npe mi ni Ọga?

*Brutus* :—Lọ fi abẹla si ibiti mo nkawe;

Nigbati o ba si ti ṣe tan, ko wa pe mi nibi.

*Lucius* :—Mo gbọ, Ọga.

*Brutus* :—Ẹmi rẹ ni yio fi san gbese na; ni temi, ko ṣẹ mi rara

Ti nfi baja, afi lati gbeja ilu; o fẹ de ade; ọrọ na nini. Ṣugbọn ọmọ ti eyi ma bi ṣa la o mọ

Ti orun ba mu, Ejo Paramọlẹ a jade varun. Enia a si ni lati ma ṣọ ilẹ rin.

Ki a de ni Ade? Iyẹn ọkan. Eyini nipe, a tun bọ le loro

Ti yio le fi wu ni lewu nigbati o ba wu.

Aidara to wa ninu ipo nla ti alagbara nlo nipe, ti alagbara na ko ba lo anu pẹlu agbara ti a fi fun.

Ki a si sọ otitọ nipa ti Caesar,

Ko jẹ lo agbara rẹ lai tẹ ero bọ ọ.

Ṣugbọn a mọ pe ko si tabitabi pe iwa irẹlẹ dabi atẹgun fun ẹniti o nwa ọla;

Atẹgun to ma ndojukọ to ba ngun oke ọla lọ.

Ṣugbọn ti o ba ti de oke atẹgun yi, nigbana a kọ ẹhin rẹ si atẹgun yi.

A ma wo oju ọrun, a si ma fi ojukoju wo ipilẹ atẹgun ti o ba goke yi. Caesar le ṣe eyi, ki o ma ba le ṣe bẹ, ki a ti okere daduro.

Ati nitcripe a ko le ri ẹjọ kan ro mọ ọ li ẹsẹ.

Ki a ro ẹjọ mọ lẹsẹ bayi pe ti a ba fi silẹ pe ki o ma ba iwa yi lọ

Yio da oniruru nkan silẹ; nitorina, ki a ro o bi ẹyin ejo ti a ko ti pa pe ti o ba dọmọ yio huwa ti o buru bi ejo ẹgbẹ rẹ; nitorina ki a tokere pa ninu ẹyin.

*Lucius tun pada wa.*

*Lucius*:—Mo ti tan abẹla na si yara rẹ Ọga. Nigbati mo nfi ọwọ tarara fun iṣana mo ri iwe ti a fi edidi di bayi.

O si damiloju pe ko si nibẹ ki nto lọ sun.

*Brutus*:—Tun lọ dubulẹ ọmọde yi, ilẹ koyi ti mọ.

Ọla ha kọ ni ijọ kẹdogun March?

*Lucius*:—Emi ko mọ, Ọga.

*Brutus*:—Lọ wo iwe ọjọ oṣu ko wa sọ fun mi.

*Lucius*:—Emi o yara lọ Ọga

*Brutus*:—Imọlẹ awọn irawọ wọnyi mọlẹ tobẹ

Ti mo le fi ka iwe yi ninu rẹ

Brutus o nsun ni, (O ṣi iwe na o nka a)? Dide ki o rcnu ara rẹ; Rcmu yio ha............Sọrọ, ṣọwọ, gbẹsan. Brutus o nsun ni? Gbera.

Brutus, o nsun ni, laju rẹ, ko ba le mọ ara rẹ Romu yio ha...........S'ọkan, gbera, gbẹsan!

Brutus, o nsun ni, gbera nlẹ!

Wọn a si da ọrọ yi duro nibiti o ba gbe ka mi lara.

Romu yio ha...........Bayi ni ma fi ẹkun rẹ si ni kinikini.

Romu yio ha ma gbọn labẹ ọkunrin kan? Kinla! Romu?

Awọn baba nla mi lo le awọn Targuin junu kuro lode Romu.

Nigbati nwọn pe e l'ọba—sọrọ, ṣọwọ gbẹsan.

A ha mbẹ mi ni ki nsọrọ ki nsi gbọwọ?

A! Romu, mo ṣe leri yi fun ọ, bi emi yio ba gbẹsan, Brutus lo ma san ẹsan na ni asankun.

*Lucius pada de.*

*Lucius*:—Ọga! March ti lo ọjọ mẹdogun danu.

*Ẹnikan nkan lẹkun ninu ile.*

O dara, lọ si ẹnu ọna. Ẹnikan nkankun, lati gba ti Cassius ti ṣo mi si Caesar.

Orun ko kun mi.

Lati igbati ẹda ba ti bẹrẹ si ro ero buruku titi di igba to dawọle ni ṣiṣe.

Larin meji rẹ a dabi ẹnipe iwin kan ati awọn ohun elo rẹ ngbimọ pọ.

Ọkan ẹda a si dabi ijọba kekere kan to pin si meji ti nwọn si mba ara wọn ja. (Lucius tun wọ le).

*Lucius*:—Ọga, Cassius ana rẹ lo wa lẹnu ọna ti o ni on fẹ ri ọ.

*Brutus*.—On nikan ni?

*Lucius*:—Ndao; nwọn pọ nibẹ.

*Brutus* :—Nję o mǫ wǫn ?

*Lucius* :—Nko mǫ wǫn ; nwǫn fa akętę wǫn bo eti wǫn.

Nwǫn si fi aṣǫ wǫn bo idaji oju wǫn.
Ki nma ba le mǫ wǫn bi mo tilę ta wǫn lǫrę.

*Brutus*:—Jęki nwǫn wǫle ; awǫn ǫlǫtę alabamǫ mi ni wǫn.

Ha a ǫtę. Oju nti ǫ lati yǫju si gbangba li oru nigbati gbogbo ika nyǫju ;

Nibo ni iwǫ yio gbe ri koto ti o ṣokun to lati fi boju buburu bi'ru tirę lǫsan.

Maṣe yǫ ara rę lęnu, ǫtę. Ko si koto kan, ǫlǫtę.

Fi ęrin ati ǫyaya bo oju rę ; nitori bi o ba rin lǫna to yę, ǫrun apadi ko ni dudu to lati fi ibaję rę pamǫ. ( Cassius, Casca, Decius Cinna, Mettelus, Cimber ati Trebinius wǫle wa. )

*Cassius* :—Mo rope awa da orun mǫ ǫ loju ? Karǫ o Brutus ; nję a ko wa yǫ ǫ lęnu bayi ?

*Brutus* :—Mo ṣęṣę dide ni, ṣugbǫn mo ti ji tipę. Mo ha

mǫ awǫn ti o ba ǫ wa wǫnyi ?

*Cassius* :—Bęni, O mǫ wǫn nikankan ; ko si si ęnikan ninu wǫn ti ko mǫ ipo rę, o si wun olukuluku wǫn ki o mǫ orukǫ rere ti gbogbo awǫn Ǫlǫrǫ Romu fi npe ǫ. Trebonius ni eyi

*Brutus* :—Mo gba ǫ tǫwǫ tęsę.

*Cassius* :—Decius Brutus li eyi.

*Brutus* :—Mo gba ǫ bakanna.

*Cassius*:—Eleyi ni Casca, eleyi ni Cinna ati eleyi, Mettelus Cimber.

*Brutus*:—Mo ki gbogbo wǫn ; "ma a wǫle." Aniyan wo li o da orun mǫ yin loju ni ajin alę yi ?

*Cassius* :—Mo ha le ba ọ sọrọ kekere kan? (Brutus ati Cassius tẹ sẹhin).

*Decius* :—Apa ibi ni ila orun wa; ibi ha kọ ni ojumọ ti nmọ?

*Casca* :—Ndao.

*Cinna* :—Ṣe gafara fun mi Ọga, nibi ni; ati ila pupa tẹrẹtẹrẹ ti o wa ni oju ọrun wọnyi ni ikọ imọlẹ arọ.

*Casca* :—Ẹ o ri pe ẹyin mejeji li o ṣisọ; Ọkankan ti mo nọ ida mi si yi ni orun ti nyọ.

Ti ko si jina tobẹ si ọna Gusu, ti o si fi han ni pe ọdun ko ti lọ jina tobẹ, titi oṣu meji si a o ri imọlẹ, orun ti yio yọ lokere lọna ariwa. Orun papa yio si kan atari ganganran bi Capitol ti duro lọhun ni.

*Brutus* :—Gbogbo yin karikari ẹ gba mi lọwọ nikọkan.

*Cassius* :—Ki ẹ si jẹ ki a bura fun ara wa.

*Brutus* :—Ewọ; ki ẹnikẹni ma bura. Bi ohun ti oju ri yi.

Bi ọgbẹ ti ọkan wa gba yi, bi irikuri ti a nri nisisiyi.

Bi gbogbo wọnyi ko ba ka wa lara, ki a ṣi tuka na, ki olukuluku lọ le lọ fi ara lelẹ.

Ki iwa ika ni ilu yi tubọ ma gbilẹ siwaju titi.

Nwọn o ma pe wa pa ni kọkan. Ṣugbọn bi ohun ti oju nri wọnyi ba to, mo si ro pe nwọn to,

Lati mu ọkan ojo wa gbina ati lati fi okun lile sinu ọkan obinrin

Ti ko ni idaduro, nigbana ẹyin ara ilu mi kini ohun ti a nfẹ ko tun gun wa ni kẹṣẹ, bikoṣe ẹdun ọkan wa?

Adehun wo ni a tun nfẹ ju pe, eyi ti awa ara Romu ma nṣe; pe nigbati a ba sọrọ tan, ọrọ na ki iyẹ, a ki si i yẹhun.

Imulẹ wo ni a tun nfẹ jupe olododo enia ṣe ileri fun olododo enia wipe bayi li yio ri.

Bi ko ba ribẹ, a o ku ti. Ẹ jẹ ki awọn babalawo ati awọn ojo enia ma mulẹ;

Jẹki awọn ẹlẹtan ati awọn atokumaku enia ati awọn afiara da iya to da mọ iṣẹ.

Iru awọn wọnni ni awọn enia ko gbẹkẹle, ti nma bura on'ruru lati ba ṣika. Ẹ ma fi abawọn kabawọn kankan si ohun rere ti a dawọle yi, tabi lọ igboya ọkan ti a ni yi.

Lati rope ohun ti a fẹ dawọle tabi ohun ti a fẹ ṣe yi nfẹ imulẹ. Nigbati o jẹ pe ẹkan ẹjẹ kọkan ti o wa lara ọmọ Romu kankan bi ọmọluwabi yio jẹ bi iṣẹ ọmọ ale

Ti o ba lọ yẹ kinkin lara ileri ti o fi ẹnu ara rẹ ṣe.

*Cassius*:—Ṣugbọn ewo li ẹ ro nipa ti Cicero, tabi ki a lu lẹnu gbọ wo? Mo rope yio duro tiwa girigiri.

*Casca*:—Ẹ ma jẹ ki a fi si ẹhin.

*Cinna*:—Ki a ma ṣe eyini rara.

*Mettelus C*:—Ha a! Ẹ jẹ ka gba si awo, nitori ewu ori rẹ yio jẹki nwọn sọrọ wa daradara, yio si jẹ ki awọn enia ki o yin iṣẹ wa.

Nwọn o wipe imọran rẹ ni a ntẹle.

Nwọn ki yio si ro o iwa ọmọde ati iwa jagidijagan wa.

Nwọn a fi gbogbo rẹ kọ ọ lọrun bi alagba.

*Brutus*:—O! Ẹ ma ṣe darukọ rẹ rara; ẹ ma jẹ ki a ba ja, nitoripe ki i nọwo ninu ohun ti ẹlomiran ba da silẹ.

*Cassius*:—Njẹ ninu yẹn, ẹ fi si apakan.

*Casca*:—Totọ ni ko yẹ bi ẹniti a ba ba kẹgbẹ ninu ọran yi.

*Decius*:—Ṣe ki a ma fi ọwọ kan ẹnikan lẹhin Caesar?

*Cassius*:—Decius, ibere rẹ sunwọn; mo ro pe ko yẹ ki Caesar fi Mark Antony ọrẹ rẹ papa si aiye lọ. A o ri pe ọlọgbọn wẹrẹwẹrẹ enia ni Mark Antony,

O si mọ pe ọgbọn rẹ yi ti o ba joko ro daradara,

O le mu ki o gbamọran miran ti yio fi pa wa lara. Ki o ma ba ri bẹ, ẹ jẹki a yẹju awọn mejeji kuro lẹkan.

*Brutus*:—Eyi ni a pọju. A o di apania patapata;

Bi igbati a pania tan ti a tun nṣa awọn ẹya ara rẹ.

Nitoripe ẹya ara Caesar ni Antony jẹ. Caius,

Ẹ jẹki a jẹ arubọ ki a ma jẹ alapata; a ko ba Caesar papa ja.

Ṣugbọn ero ọkan rẹ la nbaja.

A ba jẹ le ri ero ọkan Caesar yi pa, ki a ma pa ara rẹ;

Ṣugbọn ewo ni ṣiṣe, Caesar ni lati san gbese na.

Ati pe ẹnyin ọrẹ mi, ẹ jẹki a pa bi ọkunrin ti pa ọkunrin

Ṣugbọn ki a ma fi ibinu pa. Ẹ jẹki a bu ẹran ara rẹ bi ẹran lẹkiri fun awọn irunmọlẹ,

Ki a ma si ṣe ṣa ara rẹ ni tonitoni bi ẹran ti a o fun aja; ki ẹ si jẹki ọkan wa ko ṣiṣẹ yi ki o si ba ọwọ wa wi

Gẹgẹbi awọn ọga alarekereke ti nran ọmọ wọn lọ ṣiṣẹ ika, lẹhin na wọn a ni nwọn nba wọn wi.

Eyi ni yio mu are ba ọran wa ti a ki yio pe wa ni onilara,

Iru ọran bayi yio si mu awọn ara ilu pe wa ni alatunṣe ki si ṣe apania.

Niti Mark Antony, ẹ mu tirẹ kuro; nitoripe on ko le ṣe ju ohun ti

Apa Caesar le ṣe lọ nigbati a ti ge ori rẹ.

*Cassius*:—Sibẹsibẹ ẹru rẹ nba mi,

Nitoripe ifẹ ijinlẹ tabi ifẹ atinuwa ti o ni si Caesar.

*Brutus*:—A! Cassius mi, ma ro gba bẹ lọ. Bi o ba fẹran Caesar gbogbo ohun ti o le ṣe, ara rẹ ni yio fi ṣe, eyini ni pe k'o ronu ku fun Caesar.

Ko tun le ṣe jubẹlọ; nitoripe Antony ko mọ ju pe ko sire lọ

Ati ko huwa ipa ati ki o kẹgbẹ lọ.

*Trebonius*:—Ko si ohun ti a o bẹru ninu iwa rẹ, nitoripe lẹhin ti Caesar ba ti ku tan, yio ma fi nkan wọnyi ṣe ẹrin rin ni.

(*Agogo lu*).

*Brutus*:—Duro; ka ago melo lo lu.

*Cassius*:—Agogo ti lu mẹta.

*Trebonius*:—A to tuka.

*Cassius*:—Ṣugbọn ko' daju bi Caesar yio wa si ajọ loni tabi ko ni wa? Nitoripe o di onifura pupọ nisisiyi, ero rẹ

Si yatọ si ti atijọ, o nwolẹ o ndifa o si ndẹbọ. O le jẹ pe awọn irikuri ti nwọn pe nwọn ri nisisiyi ati ẹru abami ti alẹ yi ati ajọ awọn babalawo rẹ, o le mu ki o ma wa si Capitol loni.

*Decius*:—Ma bẹru iyẹn bi o ba tilẹ tẹnu mọ pe on ko ni wa,

Ma fi ẹnu tan wa; nitoripe o fẹran lati gbọ pe a le fi ewe aba tan agbanrere mu, a si le fi jigin tan turuku mu.

Ati pe a si le wa koto mu erin, ati pe a si le fi wahala mu Kiniun de, a si le fi ẹtan mu enia.

Bi mo ba si wi fun pe o korira awọn ẹlẹtan a wi pe bẹni,

Ko ni mọ pe mo tunbọ ntan on ni. Fi iṣẹ yi le mi lọwọ, nitoripe mo le dari ọkan rẹ sibiti mo ro pe o tọ si, ma si mu wa si Capitol.

*Cassius*:—O ti o, gbogbo wa ni yio wa mu.

*Brutus*:—Niwọn agogo mẹjọ; ṣe ko ni kọja akoko na?

*Cinna*:—Ka fi si akoko na gan ki o ma si yẹ.

*Mettelus*:—Caius Ligarius ni Caesar s'inu pupọ nitori Caesar bawi

Nigbati o sọrọ Pompey daradara. O ya mi lẹnu pe

Ẹnikẹni ko ranti rẹ.

*Brutus*:—Nisisiyi, Mettelus pasẹ rẹ lọ,

O feran mi pupọ; mo si ti ba sọrọ nipa eyi, jẹ ko wa ri mi nisisiyi,

Emi yio si la ọran na ye e.

*Cassius*:—Ilẹ ma mọ wa, a o fi ọ silẹ Brutus;

Ẹnyin arabi ẹ tuka lọ le, ṣugbọn ki ẹ si niran adehun ti ẹ ṣe, ki ẹ si fihan pe ọmọ Romu ni nyin nitotọ.

*Brutus*:—Ẹnyin arabi, ẹ jẹki oju nyin gun regerege, ki ero nyin ma si yọ loju nyin, ki ẹ fi pamọ bi awọn elere wa ti nṣe. Ṣugbọn ki ẹ ma huwa la mọ arẹ bi ẹni

T'ọkan rẹ duro ṣinṣin gẹgẹ bi awọn elere wa ti nṣe

Ti wọn ko mọ arẹ, ti ọkan wọn le. Njẹ mo ki olukuluku nyin, o darọ o.

(*Wọn jade*).

Ọmọ mi, Lucius, o ti sun fọnfọn, eyini ko buru ma gbadun oju orun rẹ didun bi oyin lọ. Ko si ohunkohun tabi alakala l'ọkan tabi ara rẹ bi iru eyiti aniyan iṣẹ ma ko ba enia, eyi lo mu ọ sun fọnfọn bayi.

(*Portia w'ọgba*).

*Portia*:—Brutus oluwa mi.

*Brutus*:—Portia, kilode? Eṣe ti o fi dide ni akoko yi? Ko yẹ fun ọ lati fi ara rẹ gba otutu arọ yi nitoripe ara rẹ ko da.

*Portia*:—Ko yẹ fun iwọ na pẹlu, Brutus, o ti yọ kẹlẹkẹlẹ jade lori ibusun mi,

Ati lalẹ ana lakoko onjẹ alẹ, o dide lojiji lori onjẹ alẹ

O nrin soke sodo, o npoṣe, o si nkun, o si nkawọ gbenu;

Nigbati mo si bere pe "Kini ṣe o" o ranju mọ mi

O si nwo mi kọrọ, mo si tun bi ọ, nigbana ni o nfi ọwọ hari, o si fi ibinu jan ẹsẹ rẹ mọlẹ mọ mi lara.

Mo si tun ọ bi, o ko tilẹ da mi lohun, ṣugbọn o fi ibinu juwọ si mi, o si fi ọwọ juwe pe ki nfi ọ silẹ; mo si fi ọ silẹ, nitori nko fẹ ki ibinu rẹ tubọ pọ si

Ibinu ti o ti ru soke. Mo si ka si bi ẹnipe inu nbi ọ ni, bi inu ti ma nbi gbogbo ẹda nigba kọkan. Nkan na ko tilẹ jẹ ki o le jẹun, o ko le sọrọ, ko si jẹ ko le sun; bi o ba si gba ọ lara gẹgẹ bi o ti gba ọ li ọkan, nko ni mọ ọ mọ, Brutus mi.

Jọwọ oluwa mi, sọ ohun ti o nyọ ẹmi rẹ lẹnu fun mi.

*Brutus*:—Ara mi ko kan da ni, o tan.

*Portia*:—Ọlọgbọn enia ni Brutus, bi o ba jẹ pe ara rẹ ko da ṣa ni nitọtọ o mọ ohun ti a ṣe.

*Brutus*:—Bẹni: bẹ na ni mo ṣe; jọ, Portia mi lọ sun.

*Portia*:—Ara Brutus ko da? Ogun rẹ ha nipe ki o ma rin lai hamọra.

Ki o si ma fi ara gba iri arọ?

Kinla? Brutus ṣaisan lo ma jẹ ko yọ jade kuro ninu ibusun rẹ lati fi ara gba atẹgun buburu alẹ ana; atẹgun to nmu otutu ati lakuregbe sara? Ndao.

Arun buruku to nyọ ọ lẹnu, arun ọkan ni.

Arun to yẹ fun mi lati mọ ni iru ipo ti mo wa si ọ ni. Lori ekun mi ni mo fi ẹwa mi ni

Ti o ti ma nyin fa ọ mọra ati nipa ibura nla ti o ti ṣe fun mi nigbati a di ọkan ni igbeyawo pe iwọ yio ma fi inu rẹ han mi.

Ati emi yio fi temi han ọ,

Emi papa idaji ara rẹ.

Sọ fun mi ki li o ṣe ti ara rẹ koti i bayi ati iru ọkọnrin wo li awọn ni ti nwọn tọ ọ wa li alẹ yi? Nitori nwọn to mẹfa tabi meje kan ti nwọn fi aṣọ bo oju wọn ninu okunkun.

*Brutus*:—Dide lori ikunlẹ, Portia mi.

*Portia*:—Emi ki ba ti kunlẹ ti iwọ ba jẹ Brutus mi.

Nipa ibura ti a ṣe ni ọjọ igbeyawo, sọ fun mi Brutus bi a ba fi "afi" si pe aṣiri kan wa ninu rẹ ti nko gbọdọ mọ?

Mo ha jẹ ọkan pẹlu rẹ ni ohun gbogbo afi ni diẹ kiun, mo ha jẹ ọkan lati ba ọ jẹun lati sun lẹgbẹ rẹ, ki nma ba ọ sọrọ, eti bebe ifẹ inu rere rẹ ni mo ha wa? Bi ifẹ rẹ ko ba jubẹ lọ si mi, Portia ki ṣe aya Brutus, ale rẹ ni

*Brutus* :—Aya mi papa ni ọ, o si ṣe ọwọn fun mi gẹgẹ bi ẹkan ẹjẹ ti nṣan kakiri ara mi lọ sinu ọkan mi.

*Portia* :—Bi eyi ba ṣe otitọ, sọ aṣiri ọrọ yi fun mi. Mo gba pe obinrin ni mi, ṣugbọn obinrin ti Brutus fi ṣe aya ni mo jẹ. Mo gba pe obinrin ni mi, ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ.

Gbajumọ obinrin ni mi, ọmọbinrin Cato. O ro pe nko li ọkan ju awọn obinrin mi lọ, ti mo ni iru baba bi Cato ati ọkọ bi rẹ?

Sọ aṣiri ọkan rẹ fun mi nki yio tu fun ẹnikan. Mo ti fi iru ọkan aṣiri ti mo ni han ọ nigbati mo fi ọwọ ara mi

Da ara mi lọgbẹ ni itan mi yi. Mo ha le gbani sara pẹlu suru, ki nma si pa aṣiri ọkọ mi mọ?

*Brutus* :—Irunmọlẹ, ẹ gba mi; jẹ ki nto ẹniti nṣe ọkọ obinrin rere yi (Nwọn nkankun).

Dakẹ, o to na! Ẹnikan nkan ilẹkun. Portia ṣi wọ ile lọ na.

Nigba to ba ṣe wa mọ aṣiri ọkan mi. Gbogbo ohun ti nfẹ ṣe ni ngo la ye ọ.

Ati gbogbo ohun to wa ninu agbari buruku yi yio jade lẹnu mi werewere.

Lucius, tani nkankun yẹn?

*Lucius* :—Ọkunrin ọlọkunrin kan niyi ti o fẹ ba ọ sọrọ.

*Brutus* :—Caius Ligarius ti Mettelus ti sọrọ rẹ ni. Ọmọde yi bọ si ẹgbẹ kan. Caius Ligarius, kilo de?

*Ligarius* :—Gba karọ lẹnu olokunrun.

*Brutus* :—A! Kili o ṣe ti o jade li akoko yi, Caius, ti o fi gele bori, iba san diẹ bi o ko ṣaisan?

*Ligarius* :—Emi o si san ti Brutus ba ni iṣẹ rere kan lati ran mi, iṣẹ ti o ba mu ọla dani.

*Brutus*:—Iru işẹ ti mo ni lọwọ na ni eyini Ligarius bi eti rẹ ba lokun lati gbọ ọ.

*Ligarius*:—Mo fi gbogbo orişa ti awọn ara Romu nwolẹ fun bẹ ọ.

Pe mo pa gbogbo aisan mi ti sibiyi. Iwọ ẹmi Romu.

Akin ninu awọn ọmọ Romu, ti baba rẹ bi pẹlu ọla, iwọ bi onidan ti nji oku dide, o ti sọ ọkan mi di aye kuro ninu oku. Paşẹ fun mi pe ki nsure, ma gbdanwo şe ohun gbogbo ti ko şeşe, ma si şe daradara.

Kini ki nşe?

*Brutus*:—Ngo fun ọ ni işẹ ti yio gbọn gbogbo aisan kuro lara ololunrun.

*Ligarius*:—Awọn ti ara nwọn le miran ko ha wa ti a ni lati sọdi alaisan?

*Brutus*:—A o si şeyini pẹlu, ohun to wa nibẹ Caius

Ma sọ fun ọ ba ti nlọ yi ẹniti a o şe e si.

*Ligarius*:—Ka fẹsẹ si pẹlu ọkan to sẹ gbina ma tẹle ọ lati şe ohun na ti nko mọ

O ti tẹ mi lọrun pe Brutus ni mo ntẹle.

*Brutus*:—Njẹ ma kalọ.

## Ere Keji. Iran Keji.

---

IYARA KAN NINU AGBALA CAESAR NI ROME.

*Ara nsan, Manamana nkọ, Caesar wọle pẹlu ẹwu awọsun rẹ lọrun.*

*Caesar*:—Taiye tọrun lokun fun wahala lalẹ yi. Ẹmẹta ni

Calpurnia kigbe lati oju orun wa pe, Ẹ gba mi o

Nwọn npa Caesar. Tani wa nibẹ?

Iranṣẹ:—Ọga mi, emi niyi

*Caesar*:—Lọ sọ fun awọn Babalawo ki nwọn dẹbọ nisisiyi.

Ki a ba mọ bi ifa ma fọre.

Iranṣẹ:—Emi yio lọ, Ọga.

(*Calpurnia wọle.*)

*Calpurnia*:—Kili o ro, Caesar, o ro pe o jade loni?

O ki yio yẹsẹ kuro ni ile yi loni.

*Caesar*:—Caesar yio jade: Ohun ti yio dẹruba mi

Ko le wo mi loju afi ẹhin mi.

Ti o ba ri oju Caesar yio fẹ lọ bi atẹgun.

*Calpurnia*:—Caesar, o mọ pe nki gba nkan bi ẹbọ gbọ.

Ṣugbọn eyi dẹruba mi ohun miran tun delẹ

Lẹhin eyiti a ti gbọ ati eyiti a ti ri. A si tun gbọ nipa irikuri ti awọn aṣọde ti ri:

Abo kiniun nbimọ si arin ita.

Awọn sare oku lanu, awọn oku inu wọn sa jade;

Awọn jagunjagun bi mọnọmọnọ nja loju ọrun lọwọlọwọ ati legbelegbe bi nwọn ti nja laiye, ti ẹjẹ wọn si nkan si ori Capitol.

Ọpọ ariwo wọn nkọlu ara wọn li ofurufu.

Awọn ẹṣin nyan ati awọn oku si nke irora kakiri ita.

A! Caesar gbogbo wọnyi kọja àla, ẹru wọn si nba mi.

*Caesar*:—Tani le yẹra fun ohun ti Ọlọrun ti ṣe to o si; pẹlu gbogbo rẹ Caesar yio lọ, Nitoripe gbogbo ami wọnyi jẹmọ gbogbo aiye gẹgẹbi o ti jẹmọ Caesar.

*Calpurnia* :—T'akuşẹ ba ma ku a ki ri ohun abami kan

Ọrun tikararẹ ni ima kede iku awọn ọba.

*Caesar* :—Awọn ojo a ma ku ki akoko iku wọn to ya.

Akin enia ki ku l'ẹrinmeji ;

Ninu gbogbo iyanu ti enia ma nsọ

O jẹ ohun ajeji pupọ fun mi pe enia ma nbẹru,

Nigbati a ti mọ pe Iku ohun tu'lasi ni, yio de nigbati o ba ya.

*( Ọmọdọ pada wa. )*

Kini awọn ẹlẹbọ ti wi ?

Iranşẹ :—Nwọn ni wọn ko fẹ ki o lọ ibikan loni, nitori bi nwọn ti la ifun ẹranko kan.

Nwọn ko ri ọkan ninu ẹranko na.

*Caesar* :—Awọn irunmọlẹ şe eyi lati dojuti awọn ojo ;

Caesar ni yio jẹ ẹranko ti ko ni okan ninu bi ko ba lọ si ibikan nitori ẹru nba, ewọ, Caesar ki yio duro nile.

Ewu papa mọ daju pe Caesar li ewu lara ju ohun papa lọ. Caesar ati Ewu jẹ ọmọ kiniun meji ti a bi li ọjọ kanna. Emi li ẹgbọn ti o ni ẹru lara ju Caesar yio jade lọ.

*Calpurnia* :—O ma şe o, ọkọ mi : Igboya rẹ ti pa ọgbọn mọ ọ ninu ; jọwọ maşe lọ si ibikan loni.

Wi fun wọn pe ibẹru ti Calpurnia li o da ọ duro nile, ki i si şe tirẹ.

A o ran Mark Antony lọ si Ajọ Igbimọ, on yio si sọ pe ara rẹ ko da ;

Jọwọ, wo ikunlẹ mi ki o si gba ọrọ yi si mi lẹnu.

*Caesar* :—Mark Antony yio wipe ara mi ko da ; ati lati fi tẹ ọ lọrun emi yio gbe ile.

*( Decius wọle wa ).*

Decius, Brutus ni o de yi o; yio lọ jiṣẹ mi fun wọn.

*Decius*:—Kabiyesi o! Caesar; a o jire bi, Caesar ẹni Ọla?

Mo wa pe ọ ki a lọ si ajọ igbimọ.

*Caesar*:—O si mọ rin papa; o si rin si asiko rere lati jiṣẹ mi fun awọn agbagba.

Ki o si wi fun wọn pe emi ki yio wa loni; ti nba lọ wipe nko le wa, irọ ni yẹn yio jẹ.

Bi nba si wipe nko gbọdọ wa irọ nlanla ni yẹn. Emi ki yio wa loni; sa sọ fun wọn bẹ, Decius.

*Calpurnia*.—Wi fun wọn pe ara rẹ ko da.

*Caesar*:—O ha yẹ ki Caesar fi irọ ranṣẹ. Emi ti o ti nawọ iṣegun mi kakiri,

Ki nwa bẹru lati sọ otọ fun awọn onirungbọn funfun wọnyẹn.

Decius lọ sọ fun wọn pe Caesar ki yio wa.

*Decius*:—Caesar, alagbara julọ; sọ idi kan fun mi ki nwọn ma ba a fi mi ṣe rẹrinrẹrin nigbati mo ba njiṣẹ yi fun wọn.

*Caesar*:—Bi o ti wun mi niyẹn; emi ki yio wa.

Iyẹn to lati tẹ awọn igbimọ lọrun. Ṣugbọn fun itẹlọrun iwọ papa,

Nitoripe mo fẹran rẹ, ma sọ idi rẹ fun ọ. Calpurnia aya mi yi ni o da mi duro sile.

Ni oru ana ni o la ala pe "On ri ere mi ti o dabi orisun

Ti o ni ọgọrun ẹnu ti o ntu ẹjẹ to pọn jade;

Ati pe awọn ara Romu ti o sanra rọbọtọ rọbọtọ nrẹrin,

Nwọn si nfi ẹjẹ na wẹ ọwọ wọn." O si fi nwọnyi ṣe ikilọ fun mi, ati pe ami ibi ti o nbọ ni werewere yi ni.

Li ori ekun rẹ li o si nbẹ mi pe "Emi ki yio yẹsẹ nile loni."

*Decius* :—Nwọn tumọ ala yi fun ọ lọna to lodi; ala ti o la yi dara o si fi han pe

Iwọ yio ni ọla ati orire. Itumọ ti ere ti o ntu ẹjẹ jade ni gbogbo ara.

Ti gbogbo ara Romu pẹlu si nwẹ ọwọ wọn ninu rẹ.

Itumọ rẹ nipe lati ara rẹ ni Romu papa yio mu ọmu ajidewe ẹjẹ. Ati pe

Awọn enia nla inu rẹ yio fi ẹjẹ rẹ na kọ buje ti nwọn o fi sami

Ti nwọn o fi ṣe ohun ipamọ ati ohun iranti. Eyi ni itumọ ala Calpurnia.

*Caesar* :—Itumọ rẹ yi si dara pupọ

*Decius*:—Iwọ yio ri pe nisisiyi mo tumọ rẹ daradara nigbati o ba le gbọ ohun ti mo ma wi. Awọn agbagba ijọ ti fi ohun ṣọkan lati de Ọlọla Caesar lade loni. Bi o ba si wi fun wọn pe iwọ ki yio wa, ọkan wọn le yi pada. Jubẹlọ, bi ẹni fi awọn agbagba ṣe yẹyẹ ni yio ri, nigbati ẹnikan yio lọ sọ fun wọn pe "Ẹ tu ajọ ka di ọjọ ti aya Caesar yio la ala rere." Bi Caesar ba fi ara rẹ pamọ, njẹ wọn ko ni ma sọrọ kẹlẹkẹlẹ pe "Wo o ẹru mba Caesar?"

Dariji mi Caesar nitori ifẹ ti mo ni si ọ ati si iṣẹ rẹ ni o mu mi sọ eyi fun ọ. O si le wadi ifẹ ti mo ni si ọ yi wo.

*Caesar* :—Calpurnia, Decius ko ha sọ gbogbo ohun ti o nfo o laya di jẹbẹtẹ?

Oju ti mi ti mo gba si ọ lẹnu. Fun mi ni ẹwu mi emi yio lọ.

*( Publius, Brutus ati awọn yoku wọle ).*

Wo ibiti Publius ti wa mi wa.

*Publius* :—Karọ o, Caesar.

*Caesar* :—Ma wolẹ. Publius, kiniṣe Brutus ti o tete dide bayi? Karọ o Casca, Caius Ligarius, Caesar ko korira rẹ to arun iba to npa ọ lọ yi. Agogo melo ni?

*Brutus* :—Caesar, ago ti lu mẹjọ.

*Caesar* :—Mo dupẹ lọwọ yin fun iyọnu ati aniyan yin.

*Antony wọle.*

Ẹ wo Antony pẹlu gbogbo aisun ati ere aṣe di ọganjọ ana, ti ji dide larọ yi. Karọ o Antony.

*Antony* :—Mo ki iwọ na karọ pẹlu bẹ.

*Caesar* :—Sọ fun wọn ki nwọn mura ninu ile; emi lo jẹbi ti pipẹ ti a pẹ loni yi. Wo Cinna, wo Mettelus. A Trebobius, mo ni ọrọ ṣoki kan ba yin sọ. Ki ẹ ma gbagbe lati kesi mi loni ki ẹ si sunmọ mi ki mba niran yin.

*Trebonius* :—Caesar, mo gbọ; ( lakotan ngo sunmọ ọ ni ọna ti awọn ọrẹ rẹ yio fi wipe mba tubọ jina si ọ ).

*Caesar* :—Ẹnyin ọrẹ mi papa ẹ jẹki a wọle lọ mu Waini diẹ, ati gẹgẹ bi ọrẹ ao jumọ kẹsẹ lọ pọ nisisiyi.

*Brutus* :—( O bọ sẹgbẹ kan ) Ọkan Brutus gbọgbẹ lati ro pe gbogbo nkan to jọra wọn lode ko jọ ara wọn ninu.

## Iran Keta.

OPOPO KAN NITOSI CAPITOL.

*Artemidorus* :—Caesar, ṣọra lọdọ Brutus, ṣe kẹlẹkẹlẹ lọdọ Cassius, maṣe sunmọ Casca; loju lara Cinna,

ma f'ọkan tan Trebonius, ṣọ Mettelus Cimber daradara, Decius Brutus ko fẹran rẹ. O ti ṣẹ Caius Ligarius; ero kanna lo wa ninu awọn enia wọnyi, ero ti ko ni ṣe Caesar ni anfani. Ṣugbọn bi ẹran iku ba wa lara rẹ, wo ara rẹ yidayida. Aibikita ni o nmu ọtẹ ṣẹlẹ; ki awọn irunmọlẹ ki o ṣọ ọ.

Emi ọrẹ rẹ, Artemidorus.

Nibi ni emi yio duro titi Caesar yio fi kọja,

Ati gẹgẹ bi ẹlẹbẹ ni emi yio fun ni iwe yi;

O jẹ ohun ẹdun ọkan mi pe enia rere ko le bọ lọwọ ilepa elenini;

Bi o ba ka iwe yi, Caesar o le bọ lọwọ iku;

Bi o ko ba si ka iwe yi, mọ pe ati yan kadara rẹ pọ mọ awọn ọlọtẹ.

*Portia*:—Jọwọ mo bẹ ọ, ọmọde yi sare lọ sile igbimọ maṣe duro lati wa da mi lohun, ṣugbọn ma a lọ lẹkan. Kini o tun duro fun?

*Lucius*:—Lati mọ iṣẹ ti o ma ran mi ni. Bẹrẹ mi.

*Portia*:—Mo fẹ ko dọhun nisisiyi ki o si tun ti de bi bẹ ẹ,

Ki nto le sọ ohun ti o ṣe nibẹ fun ọ. Aimikan ṣe alatilẹhin mi majẹ ki ahọn mi tu aṣiri ọkan mi; mo ni ọkan ọkunrin ṣugbọn okun obirin, bawo li o ti ṣoro to fun obirin lati pa aṣiri mọ? O ṣi wa nibẹ sibẹ?

## Iran Kerin.

NIKORITA; NIWAJU ILE BRUTUS.

*Lucius*:—Bẹrẹ mi, ewo ni ki nṣe? Ki nsure lọ si Capitol nikan ni

Tabi ki nsi tun pada wa sibi ki nma tun ṣe nkan mi pẹlu mọ?

*Portia* :—Bẹni ; ki o si mu esi fun mi wa, ọmọ mi, bi oju ọga rẹ ba sunwọn

Nitoripe oju rẹ ko dara nigbati o ma lọ.

Ki o si ṣe akiyesi daradara ohun ti Caesar ba ṣe ati awọn ajirẹbẹ ti o ba sunmọ. Feti lelẹ ọmọde yi, ariwo wo niyẹn.

*Lucius* :—Ng ko gbọ ariwo na, iya mi.

*Portia* :—Mo bẹ ọ tẹti lelẹ daradara ;

Mo gbọ iro ariwo kan bi iro ija nla.

Atẹgun si gba wa lati Capitol.

*Lucius* :—Nitotọ ? Nko gbọ ariwo kan rara, iya mi.

*Alafọṣẹ Wọle*

*Portia* :—Wo, ẹnikeji mi, apa ibo ni o ti mbọ ?

Alafọṣẹ :—Lati ile mi ni, iya afin.

*Portia* :—Agogo melo ni nisisiyi ?

Alafọṣẹ :—O nlọ si agogo mẹsan ; iya.

*Portia* :—Njẹ Caesar ti lọ si Capitol ?

Alafọṣẹ :—Iya afin, ko ti lọ, mo nlọ duro loju ọna lati ri bi o ba nkọja lọ si Capitol.

*Portia* :—O ni nkan lati bere lọdọ Caesar, tabi bẹkọ ?

Alafọṣẹ :—Bẹrẹ mi, mo ni ohun ti mo ni lati bere. Bi inu Caesar ba dun si Caesar.

Lati gbọ mi ; ma a si bẹ ki o fẹran ara rẹ.

*Portia* :—O mọ bi wọn fẹ ṣe ni ibi kan ni ?

Alafọṣẹ :—Ngo mọ bi ibi kan le ṣe e, ṣugbọn mo mọ pe pupọ rẹ le ba a ; odigba o, ita yi ha pupọ ; awọn ero ti o ntẹle Caesar bi awọn igbimọ, awọn balẹ, ati awọn ajirẹbẹ ti wọn hamọ girigiri, wọn le fun

alailokun ninu pa. Emi yio lọ si ibiti aye wa daradara. Ati nibẹ ni emi yio ba Caesar sọrọ bi o ti nrekọja lọ.

*Portia*:—Mo ni lati wọ ile lọ. (O nikan nba ara rẹ sọrọ) Hepa! Bawo ni ọkan obirin ti ṣe alailagbara to. Ha a Brutus, ki Ọlọrun pẹlu rẹ ni ohun ti o dawọle yi o! Ye e! Ọmọde yi ti gbọrọ ti mo sọ; Brutus ni ẹjọ kan ti Caesar ko fẹ da lohun rẹ. He e! Arẹ mu mi o; sare Lucius ki o si ki ọkọ mi fun mi, ki o si wi fun pe ko si nkan, ara mi ya. Ki o si pada wa jiṣẹ rẹ fun mi.

*Gbogbo wọn tuka nikọkan.*

## Ere Keta. Iran Kini.

NI ROMU: AWỌN AJỌ IGBIMỌ NLỌ SI CAPITOL.

*Caesar*:—(Si Alafọṣẹ). Ọjọ kẹdogun oṣu March ma de o.

Alafọṣẹ:—Bẹni Caesar, ṣugbọn koi ti lọ.

*Artemidorus*:—Kabiyesi o Caesar! Ka iwe kikọ yi.

*Decius*:—Trebonius ni ko ka iwe ẹbẹ rẹ yi nigbati o ba ri aye.

*Artemidorus*:—Ha a Caesar! Ka temi yi na nitoripe temi yi ni o kan Caesar ju. Ka a Caesar nla.

*Caesar*:—Ohun ti o ba kan ni ju, ni a o kiyesi gbẹhin.

*Artemidorus*:—Ma jafara Caesar, ka a lẹkan.

*Caesar*:—Kinla! O ri ọkunrin yi ko pe ni?

*Pub*:—Ọgbẹni, jọ fun wa laye.

*Cassius*:—Emọ! Arin ita li o ma bẹrẹ? Wa si Capitol.

*(Caesar lọ si ile ajọ; awọn yoku ntẹle. Gbogbo awọn Igbimọ dide.)*

*Popilius*:—Ki Ọlọrun ki o pẹlu yin ninu ohun ti ẹ fẹ dawọle loni.

*Cassius*:—Kili ẹ fẹ ṣe? Popilius.

*Popilius*:—O digba o.

(*O lọ si ọdọ Caesar.*)

*Brutus*:—Kini Popilius Lena ti wi?

*Cassius*:—O ni ki Ọlọrun pẹlu wa loni ninu ohun ti a fẹ ṣe Mo ro pe aṣiri wa ti tu.

*Brutus*:—Wo o bi o ti sunmọ Caesar girigiri; ma ṣọ ọ re Casca, ẹ ṣe were, ki wọn ma da wa lọwọ kọ.

*Cassius*:—Brutus, kini ṣiṣe? Bi wọn ba lọ mu wa, Caesar tabi Cassius, ọkan ninu wa ko ni pada lọ sile; nitori emi yio pa ara mi.

*Brutus*:—Cassius k'ọkan duro; Popilius Lena ko sọ nipa tiwa. Sa wo o, o nrẹrin, oju Caesar ko si yi pada.

*Cassius*:—Trebonius mọ akoko to wọ; wo o, Brutus, o fa Mark Antony kuro lọna.

(*Antony ati Trebonius jade, Caesar ati awọn ajọ Igbimọ joko sipo wọn*).

*Decius*:—Mettelus Cimber da? Ẹ jẹ ki o bọ siwaju, ki o lọ fi iwe ẹbẹ rẹ fun Caesar lojukanna.

*Brutus*:—O ti mura tan; ẹ sunmọ ki ẹ si gbe e lohun.

*Cinna*:—Casca, iwọ ni ki o kọ gbọwọ soke.

*Caesar*:—Ṣe oju gbogbo pe? Kini ohun ti o yingin ti Caesar ati awọn Igbimọ rẹ ni lati tunṣe?

*Mettelus*:—Caesar, ẹni giga julọ ati alagbara julọ, Mettelus Cimber fi ọkan irẹlẹ kunlẹ niwaju rẹ (o kunlẹ).

*Caesar*:—Emi yio ni lati da ọ duro ki o ma kunlẹ, Cimber, gbogbo iba buruburu rẹ ati ikunlẹ rẹ yi le ka awọn enia ṣakala lara, a si sọ ofin aṣẹdalẹ ati ofin atijọ di ofin ọmọde. Maṣe ro pe ibajẹ ara Caesar pọ tobẹ, ti yio fi le mu ọkan rẹ yẹ kuro li ọna rere rẹ lati dapọ mọ t'awọn ti ko lọgbọn lori. Eyini ni pe ọrọ didun ati iba buruburu ati ifara pọnni bi aja; ati fi ofin wa arakunrin rẹ lọ. Bi o ba tun kunlẹ ti o mbẹ mi ti o si nfi ara pọn mi nitori rẹ, ma fẹsẹ ta ọ kuro lọna mi bi aja. Mọ daju pe Caesar ki ṣe aṣiṣe

Bi ko ba si ni idi, ki si iyi ọrọ rẹ pada.

*Mettelus*:—Ko si ohun didun kan ju ti emi lọ ti yio ka Caesar lara

Lati pe arakunrin mi ti a wa danu sile?

*Brutus*:—Caesar, mo fi ẹnu mi ko ọ lọwọ, ki nṣe fun pipọn; Ṣugbọn ki o le jẹki Publius Cimber pada wale kiakia.

*Caesar*:—Kili o ti wi Brutus!

*Cassius*:—Ẹbẹ, Caesar, ẹbẹ ni mo bẹ ọ; gẹgẹ bi emi Cassius ti wolẹ labẹ ẹsẹ rẹ lati bẹbẹ pe ki Publius Cimber ki o le pada si ipo rẹ.

*Caesar*:—Bi emi ba dabi rẹ ni emi yio gba ẹbẹ; bi nba fẹ gbọ ẹbẹ, ẹbẹ ati mu mi ṣe idariji fun ẹlomiran, ṣugbọn mo duro gbọnin bi irawọ to wa lọgangan ọrun, eyiti ko si irawọ ti o jọ ni diduro gbọnin loke ọrun. Oju ọrun kun fun ọpọlọpọ irawọ; olukuluku si ndan yinrin bi ina, gbogbo wọn si nkun fun imọlẹ; ṣugbọn ọkan ninu wọn ni ko fi ipo rẹ silẹ.

Bẹ gẹgẹ ninu aiye wa yi ti o kun fun enia.

Enia si jẹ ẹran on ẹjẹ; enia si ma nyi pada. Ṣugbọn ninu gbogbo wọn mo mọ ẹnikan ti ki ṣi ipo rẹ pada, ki mu ọkan oluwarẹ papa yi. Ẹ jẹ ki nfi

eyi ṣe apẹrẹ kekere kan fun yin pe ọkan mi duro pe ki a wa Cimber danu.

Ati pe ọkan mi si duro pe ki o wa bẹ ẹ titi.

*Cinna*:—A ! Caesar !!!

*Caesar*:—Ẹnyin ha le ṣi oke Olympius (Oke nla kan bi Olumọ ni Romu) nidi?

*Decius*:—Ha ! Caesar, ọba nla !

*Caesar*:—Njẹ Brutus ko ha kunlẹ lasan bayi?

*Casca*:—Ẹnyin arabi, ẹ ṣere ọwọ fun mi ri.

(*Casca gun Caesar lọbẹ lọrun. Casca gun li apa ; awọn ọlọtẹ yoku si gun lọbẹ. Brutus lo wa gun lọbẹ gbẹhin.*)

*Caesar*:—Ha! Brutus, Iwọ kẹ? (O ku).

*Cinna*:—Ominira de Ibọri de; (Caesar) Omuroro ku, ẹ gba ibi lọ pẹlu ere tete, ki ẹ si sọ eyi fun gbogbo aiye. Ẹ kede rẹ kiri larin ita pe, Omuroro ti ku.

*Cassius*:—Ẹ lọ lu kere larin ita ati ọja, ki ẹ si kigbe pe ominira de, ibọri de, ara Romu di ominira ara wọn

*Brutus*:—Ẹnyin enia mi ati ẹnyin Oloye, "Ẹ ma ṣe bẹru, ẹ ma ṣe salọ, ẹ duro loju kan a ti san gbese iwọra fun iwọra.

*Casca*:—Lọ lu kere na lori aga (pulpit) larin ọja, Brutus.

*Decius*:—Cassius, lọ ṣe bẹ pẹlu.

*Brutus*:—Publius da?

*Cinna*:—Iyọnu yi ti damu rẹ patapata.

*Metellus*:—Ẹ duro pọ girigiri; boya awọn ọrẹ Caesar le ṣina de ibi:

*Brutus*:—Ẹ ma sọ ti diduro; Publius tuju ka; ẹnikẹni ko jẹ hu iwa jamba si ọ tabi si ara Romu kan. Sọ fun wọn bẹ Publius.

*Cassius* :—Ma lọ Publius ki awọn enia ma ṣe ṣe jamba fun ọ pẹlu arugbo ara rẹ nigbati nwọn ba fẹ lu wa.

*Brutus* :—Ṣe bẹ gẹgẹ ki ẹnikẹni ma duro ti iṣẹ yi afi awa ti o ṣe e.

(*Trebonius wọle wa.*)

*Cassius* :—Antony da?

*Trebonius* :—O ti salọ si ilẹ rẹ pẹlu iyanu; t'ọkunrin t'obinrin ati ọmọde lo yanu wọn ti nwọn si nsare kiri, bi ẹnipe ọjọ idajọ de.

*Brutus* :—Ọlọrun o! Ewo la tun ma kan; ti pe ao ku a mọ eyini daju. Akoko wo ati ọjọ melo lo ku li a nduro de,

*Cassius* :—Ko ha jẹpe ẹniti o ba ge ogun ọdun kuro ninu ọjọ igbe aiye enia,

O ge ogun ọdun ninu eyiti yio fi bẹru iku kuro.

*Brutus* :—Bi o ba ri bẹ njẹ iku jẹ ohun anfani.

Njẹ awa na jẹ ọrẹ fun Caesar ti a ge ọjọ aiye rẹ kuru.

Ẹ bẹrẹ ẹnyin ara Romu, ẹ bẹrẹ; ẹ jẹ ki a fi ẹjẹ Caesar wẹ ọwọ wa titi de igbunka.

Ki a si fi pa ida wa; lẹhin na ki a rin lọ titi de ọja.

Ki a si ma fi ida wa ti o pọn fun ẹjẹ loke ori wa ki a si ma kigbe pe "Alafia de! Ominira de! Anfani de!!!

*Cassius* :—Ẹ bẹrẹ ninu yẹn ki ẹ si fi wẹ ọwọ yin; ọdun melo si lẹhin eyi li nwọn o ma fi ọran nla to ṣẹlẹ loni ṣere ni ilu Aimọ ati lede "Ajeji."

*Brutus* :—Nigba melo ni oku Caesar yio ma ṣubu ṣere si idi ere Pompey. Nigba melo ni ara rẹ yi ti ko sanju iyẹpẹ yi lọ yio ma tu ẹjẹ ṣere?

*Cassius*:—Niwọn igba ti nwọn ba nṣere yi, niye igba na ni nwọn yio ma sọrọ ẹgbẹ wa pe, awọn wọnyi li o mu alafia ba ilu wọn.

*Decius*:—Njẹ a le ma lọ?

*Cassius*:—Ki olukuluku ki o ma lọ; Brutus yio ṣiwaju.

Awa o si jẹki awọn gbajumọ wa fi iyi wọn tẹle e.

(*Ọmọ ọdọ rẹ wọle.*)

*Brutus*:—Ẹ dakẹ na. Tani nbọ yẹn? Ọrẹ wa Antony ni.

Iranṣẹ Antony:—Brutus, bayi ni ọga mi ni ki nkunlẹ fun ọ. Bayi ni Mark Antony ni ki ndọbalẹ.

Ti nba si dọbalẹ tan, o ni ki nwi bayi fun ọ pe, "Ọmọ ọlọla ni Brutus,

Ọlọgbọn enia ni, akin ọkunrin ati ọmọluwabi niṣe.

Caesar jẹ alagbara ati onigboya enia; ọmọ alade ni ati onifẹ enia.

O wipe, "Mo fẹran Brutus, mo si bu ọla fun un. Mo bẹru Caesar mo bu ọla fun, mo si fẹran rẹ.

Bi Brutus ba le fi aye silẹ ki Antony wa sọdọ rẹ li alafia, lati gbọ bi Caesar ti ṣe jẹbi iku,

Mark Antony ki yio fẹran Caesar ti o ku to Brutus ti o wa laye.

(Ṣugbọn yio jẹ ọmọ ẹhin Brutus ki yio si kọ lati fi ori la iku fun

Ohun rudurudu ti o delẹ yi) laimikan. Bẹni ọga mi Antony wi."

*Brutus*:—Ọga rẹ jẹ ọlọgbọn ati akin enia; emi ko fi ẹkan binti rẹ. Sọ fun pe ti o ba dun mọ lati wa sibi yi ki o wa.

Awa o si fun ni itẹlẹrun. Ki o gba mi gbọ pe era ko ni rin i

Iranṣẹ :—Yio ba mi de'bi nisisiyi.

( *O jade.* )

*Brutus* :—Emi mọ pe yio wa lẹhin wa girigiri.

*Cassius* :—Iba jẹ le ri bẹ. Sibẹsibẹ ọkan mi ko balẹ si, mo si ro pe ọkan mi ko ṣina tobẹ.

( *Antony tun wọle.* )

*Brutus* :—Antony na lo nbọ yi. Ma wo lẹ o, Mark Antony.

*Antony* :—Caesar alagbara nla, iwọ lo da bayi ? Njẹ

Bi gbogbo iṣẹgun rẹ, ogo rẹ, fukẹ rẹ ati gbogbo ikogun rẹ ti mọ niyi ? O digboṣe o. Ẹnyin ọga mi nko mọ ohun ti o ku ti ẹ fẹ ṣe.

Tani o tun ku ti ẹ o ta ẹjẹ rẹ silẹ. Tani iru eyi yio tun kan ?

Bi emi ni iku ba kan, ko si akoko ti o yẹ mi lati ku ju akoko iku ti Caesar yi lọ.

Ko si si ele na ti o mu to ida to si yẹ bi ida yin ni ti o gba ẹmi lẹnu

Ọkunrin ti o tobi julọ li aiye yi.

Mo bẹ yin, bi inu yin ko ba dun si mi

Nisisiyi ti ọwọ yin pọn fun ẹjẹ Caesar ki ẹ tẹ ifẹ yin lọrun.

Bi mo ba gbe ẹgbẹrun ọdun si, iku ki yio yẹ mi

Bi ki nku nisisiyi ko si ibi ti yio si dun mọ mi bi ki a tẹ mi ti Caesar.

Ko si si ọna iku kan ti o yẹ mi bi ki a wipe ẹnyin li ẹ pa mi.

Ẹnyin ọga ati ọbaluwaiye yi.

*Brutus*:—Ha, Antony! Ma tọrọ iku rẹ lọwọ wa.

Bi atẹlẹwọ wa mu wa wo bi oṣika ati apania nisisiyi gẹgẹ bi orukọ ti ọwọ wa yi ati ohun ti a ṣe yi sọ wa

Sibẹsibẹ ẹ kan ri ọwọ wa ni, ati iṣẹ ẹjẹ ti nwọn ṣe yi.

Ṣugbọn ẹ ko ri ọkan wa; nwọn kun fun anu, ati anu ti o kun fun ika

Ti Caesar fi ṣe Romu. Gẹgẹ bi ina ti le ina jade bẹni anu nle anu; anu Romu li o mu wa ki a ṣe iru eyi si Caesar.

Niti rẹ, Mark Antony, ida wa ti kuju si ọ, ida wa ko korira rẹ, a si fi ọkan wa pẹlu ifẹ arakunrin fa ọ mọra tifẹtifẹ, terotero ati tọwọtọwọ.

*Cassius*:—Ohun rẹ yio tolẹ bi ti ẹnikẹni, nigbati a ba ntun ipo to.

*Brutus*:—Sa mu suru titi ao fi tẹ awọn enia wọnyi lọrun, awọn ti nwọn ti fi ibẹru salọ. Nigbana ni ao sọ idi rẹ fun ọ,

Bawo ni emi ti o fẹran Caesar pupọ fi ṣe eyi nipa gigun lọbẹ.

*Antony*:—Emi ko ninkan sọ si iwa ọlọgbọn ti ẹ hu yi;

Ki olukuluku yin fi ọwọ ẹjẹ na gba mi lọwọ.

Njẹ Marcus Brutus, iwọ ni ngo kọ gba lọwọ; o kan ọ Caius Cassius.

Iwọ na gbọwọ; mọwọ rẹ wa, Decius Brutus ati tirẹ, Mettelus.

Tirẹ Cinna ati tirẹ Casca, ọkunrin na; tirẹ ni ngo gba gbẹhin,

Trebonius, ṣugbọn o ko gbẹhin ni ifẹ. Ọmọluwabi ni yin.

Tabi kini ki nwi niti ọrọ ti mo sọ yi Mo ṣorọ gbagbọ nisisiyi. Tipe mo fẹran rẹ Caesar, totọ ni. Ti oku ba nri ẹhin inu rẹ ko ni bajẹ si mi ju iku ti o ku lọ.

Lati ri pe Antony rẹ nba awọn ọta rẹ ṣọrẹ.

O mba wọn gba ọwọ to ta ẹjẹ rẹ yi silẹ.

Ọrẹ mi ọlọla julọ, niwaju oku rẹ, emi iba li oju pupọ to

Bi oju ọgbẹ rẹ ti pọ to, ki omije mi ma ṣan nibẹ

Bi ẹjẹ ti ntu jade loju ọgbẹ rẹ, eyini yio yẹ mi ju ki nlọ ba awọn ọta rẹ ṣe ọrẹ lọ.

Darijin mi, Julius, nihinyi li a ka ọ mọ iwọ akọ Igala nla.

Nihinyi lo ṣubu si. Nihinyi li awọn ọdẹ rẹ duro si.

Nihinyi li a sami si oku rẹ, nihinyi li a fi ẹjẹ rẹ wẹwọ.

Aiye o! Iwọ ni igbo ti Igala yi wo si,

Oku yi si ni ẹmi Igala na.

Wo o bi o ti dubulẹ bi abo Igala ti awọn ọlọla gun lọbẹ pa.

*Cassius*:—Mark Antony:—

*Antony*:—Jọ dariji mi, Caius Cassius; awọn ọta Caesar ni yio ro bẹ, ṣugbọn latẹ'nu ọrẹ eyi ko jamọ nkan.

*Cassius*:—Nko ba ọ wi nitori o yin Caesar bayi;

Ṣugbọn ewo lo fẹ ṣe gan : tiwa ni tabi ti awọn ọta wa ?

K'a ka ọ kun awọn ọrẹ wa ni, tabi ki a ma ṣe tiwa lọ ki a ma bikita rẹ ?

*Antony* :—Nitorina ni mo ṣe gba yin lọwọ. Ṣugbọn oku Caesar

Ti mo ri yi lo mu mi ṣi ọrọ sọ ; temi tiyin ọrẹ la jẹ, mo si fẹran gbogbo nyin ;

Mo ni ireti pe ẹ o sọ idi rẹ fun mi bawo ni,

Ati bi, Caesar ti ṣe jẹ onijamba enia.

*Brutus* :—Laisọ idi eyi fun ọ, ẹranko enia la jẹ ;

Ohun ti o mu wa pa a, o tọna tobẹ ti

Bi iwọ Antony ba tilẹ jẹ ọmọ bibi Caesar, yio tẹ ọ lọrun ti a ba sọ fun ọ.

*Antony* :—Idi ohun ti mo fẹ na ni ni. Jubẹlọ mo wa bẹ ẹ lẹbẹ

Ki nle gbe oku rẹ lọ si ori pẹpẹ larinja, ati ki nduro lori aga gẹgẹ bi ọrẹ, ki nsọrọ iku rẹ.

*Brutus* :—Ma fun ọ laye, Mark Antony.

*Cassius* :—Brutus, gbọ mi na ; (Cassius yẹ sapakan lati ba Brutus sọrọ ).

O ko mọ nkan ti o fẹ ṣe : ma gba ki Antony sọrọ nibi oku rẹ. O ko mọ bi yio tun mu awọn enia gbera si i nigbati o ba sọrọ tan

To ba si ka wọn lara.

*Brutus* :—Ṣe gafara fun mi. Emi papa ni yio kọ gun ori pẹpẹ,

Emi yio si fihan wọn ohun ti o padi iku Caesar.

Emi o wi fun wọn pe " Awa la fun Antony laye lati sọ ohun ti yio sọ. Ati pe o si tẹ wa lọrun ki awọn enia sin Caesar, ki wọn si ṣe gbogbo oro ile rẹ fun u.

Yio mu anfani pupọ fun wa lai ṣe ibi.

*Cassius*.—Emi ko ma fẹ o, emi ko mọ ohun ti o le ti idi rẹ yọ.

*Brutus*:—Mark Antony, wa gbe oku Caesar lọ. O le yin Caesar bi o ti fẹ, ṣugbọn maṣe sọrọ gbun wa; ki o wi fun wọn pe awa lo gba ọ laye rẹ.

Bi bẹkọ, o ko ni ni ọwọ ninu isinku rẹ. Ati pe, lori pẹpẹ kanna ti nba sọrọ ni iwọ yio sọrọ ti mba sọrọ tan.

*Antony*:—Eyini ti to, nko fẹ jubẹ lọ.

*Brutus*:—Lọ tẹku ki o si tẹle wa.

(*Gbogbo wọn jade afi Antony nikan*).

*Antony*:—Jọwọ dariji mi, iwọ oku ọrun yi, pe,

Mo ni inu didun si awọn agunbẹ wọnyi.

Iwọ ni oku rẹ milẹ ju, lati ijọ ti alaiye ti d'aiye lọ.

Egbe ni fun ọwọ ti o ta ẹjẹ iyebiye yi silẹ; lori awọn ọgbẹ rẹ wọnyi ti o la ẹnu ẹjẹ wọn bi odi

Ti ko si le fọhun ni mo sọ asọtẹlẹ wipe,

"Wahala nla mbọ wa de ba ọmọ enia, ija ilu ati ija igboro yio yi gbogbo Italy kakiri.

Ẹjẹ ati iparun yio pọ tobẹ, ohun ibẹru yio jẹ ohun ojojumọ tobẹ,

Ti ẹrin yio pa awọn iya nigbati ogun ba nṣa awọn ọmọ ọwọ wọn pa.

Oju anu yio fọ, ti ika ni yio ku. Ati oku Caesar pẹlu Esi (oriṣa igbẹsan) lẹgbẹ rẹ, yio ti sare jade wa nigbonagboru lati ọrun Apadi yio ma kigbe ẹsan, ati ni biri wa yi yio ma kigbe pe, ẹ pa wọn ni ipakupa, yio si dẹ awọn aja ogun rẹ sode

Ki iwa buruku yi le run jade lati inu ilẹ wa pẹlu ẹran awọn oku enia ti nfẹ sisin."

( *Iranṣẹ kan wọle* ).

Ọmọ ọdọ Octavius Caesar ha kọ ni ọ?

Iranṣẹ :—Bẹni, Mark Antony.

*Antony* :—Caesar Octavius ti Julius ti kọwe si pe ko wa si Romu.

Iranṣẹ :—O ri awọn iwe na gba, o si mbọ. O si fi ẹnu ran mi si pe—"Ye! Caesar."—lori oku rẹ

*Antony* :—Ori rẹ wule, bọ si apakan ki o lọ sunkun. Ọrọ yi nkara bọ, nitoripe ẹkun ngbọn mi nigbati mo ri oju rẹ ti nlemi. Ọga rẹ mbọ bi?

Iranṣẹ :—O ti de ibusọ mẹrindilogọta (56) si Romu nisisiyi.

*Antony* :—Yara lọ werewere ki o si sọ nkan ti o ti ṣẹlẹ fun. Romu wa ninu ọfọ nisisiyi. O si wa lewu, alafia ko ti si ni Romu fun Octavius lati wọ ọ. Yara lọ kuro nibi nisisiyi, ki o si sọ bẹ fun; tẹṣẹ duro diẹ na, ki o ma si ti lọ titi ti emi o fi gbe oku yi de arin ọja, nibẹ ni ma ri bi awọn enia yio ti ṣe si ọrọ buruku yi. O si lọ to o fun Octavius bi gbogbo nkan ti lọ. Ba mi fi ọwọ si.

( *Wọn gbe oku Caesar jade* ).

## Ere Keta. Iran Keji.

---

ILE ỌJA.

---

( *Brutus ati Cassius lo gori aga nile Ẹgbẹ ati ọpọ ninu awọn aralu* )

*Aralu Kini* :—Awa nfẹ itẹlọrun; tunmọ rẹ ko tẹ wa lọrun.

*Brutus* :—Nitorina ẹ tẹle mi, ki ẹ si tẹti lelẹ si mi ẹnyin ọrẹ mi. Cassius, lọ si odi keji ki o si pin awọn enia si meji. Awọn ti yio gbọ temi ki wọn duro nihin,

Awọn ti yio si tẹle Cassius ki wọn ba a lọ.

Ao si sọ fun nyin gbangba ohun ti o padi iku Caesar.

*Aralu Kini* :—Emi yio gbọ ti Brutus.

*Aralu Keji* :—Emi yio gbọ ti Cassius: ao si fi ọrọ wọn we ra wọn nigbati wọn ba sọ ọ lọtọtọ.

(*Cassius pẹlu awọn aralu diẹ jade*; *Brutus gun ori aga lọ*).

*Aralu Keta* :—Ẹ dakẹ o, Brutus Ọlọla ti gun ori aga.

*Brutus* :—Ẹ mu suru titi ngo fi pari ọrọ mi,

Ẹnyin ara Romu, ẹnyin ara ilu mi, ati ẹnyin olufẹ mi;

Ẹ tẹti lelẹ si ọrọ mi ki ẹ ba le gbọ.

Ẹ gbami gbọ nitori iyi mi ki ẹ ba le gbagbọ. Ẹ da ẹjọ mi bi o ti yẹ, ki ẹ si ro ori nyin wo

Ki ẹ ba le ṣe idajọ ododo. Bi ẹnikẹni ba wa ninu ajọ yi, ti o jẹ ọrẹ Caesar timọtimọ, ki oluwarẹ ki o mọ pe ifẹ ti o ni si Caesar ko ju ti emi lọ. Bi oluwarẹ na ba bere pe "Eṣe ti Brutus fi dide si i" esi mi ni eyi pe "Ki ṣe pe ifẹ mi si Caesar dinku, ṣugbọn ifẹ mi si Romu npọ si." O ha wun nyin ki Caesar wa laye, ki gbogbo nyin ku l'oko ẹru tabi ki Caesar ku ki gbogbo nyin di omnira? Bi Caesar ti fẹran mi, mo sọkun fun; nitori o ni orire, mo ba a yọ; ati nitoripe o jẹ akin ọkunrin, mo bu ọla fun.

Ṣugbọn nitoripe o ni iwọra, mo gun lọbẹ pa. Oju mi kun fun omije nitori ifẹ ti mo ni si i, inu mi kun fun ayọ nitori orire rẹ. Mo bu iyi fun nitori akikanju rẹ, mo si fi iku lọ nitori iwọra rẹ.

Tani ninu yin ti o wa nihin ti o gọ tobẹ

Ti o fẹ jẹ ẹru? Ẹniti o ba fẹ, eyini ki o wi.

Oluwarẹ ni mo ṣẹ. Tani wa nihin ti o jẹ ara oko ti ko fẹ jẹ ọmọ Romu ( Onilaju ) ?

Bi iru enia bẹ ba wa nihin ki o sọrọ lẹkan, nitoripe on ni mo ṣẹ. Tani ninu nyin ti o wa nihin ti o buru tobẹ ti ko fẹran ilu rẹ ? Bi ẹnikan bẹ ba wa nihin ki o sọrọ, nitoripe on ni mo ṣẹ. Mo dakẹ na lati gba esi.

*Gbogbo awon aralu* :—O ko ṣẹ ẹnikẹni.

*Brutus* :—( Njẹ mo yọ ) pe nko ṣẹ ẹnikẹni. Emi ko ṣe ohunkohun si Caesar ju bi ẹnyin na ti ni lati ṣe si Brutus lọ A ti dahun ibere nipa iku rẹ si inu iwe ni Capitol, ogo rẹ ko si dinku si bi o ti yẹ. A ko si ka ẹbikẹbi si l'ẹsẹ fun iku ju bi ẹbi rẹ ti mọ lọ.

( *Antony wọle ali awọn to ba gbe oku Caesar* ).

Oku rẹ ni wọn ngbe bọ yi ti Antony nki. Ẹniti o jẹ pe bi ko ti ni ọwọ ninu iku rẹ, ṣugbọn yio jẹ anfani iku na, awa yio fun li oye ni ilu—tabi tani ninu nyin ti ko ni joye ? Asọgbẹhin ọrọ mi ni yi pe gẹgẹ bi mo ti pa ọrẹ mi papa fun ire Romu, mo ni ida kanna fun ara mi nigbati o ba wun ilu mi lati mu mi tẹri gbaṣọ.

*Gbogbo awon aralu* :—Ewọ, Brutus wa pẹ, wa pẹ fun wa.

*Aralu Kini* :—Ẹ jẹki a ru lọ'le pẹlu ayọ ati ariwo nla.

*Aralu Keji* .—Ki a mọ ere iranti rẹ si ẹgbẹ ti awọn baba nla rẹ.

*Aralu Keta* :—Ẹ jẹki a gba dipo Caesar.

*Aralu Kerin* :—Ire ti Cassar ba ṣe ku, Brutus ni yio pari rẹ.

*Aralu Kini* :—Ao sin de'le rẹ pẹlu ariwo ati ilu.

*Brutus* :—Ẹnyin ara ilu mi..............

*Aralu Keji* :—Ẹ jọ, ẹ dakẹ wayi, Brutus nsọrọ.

*Aralu Kini* :—Ẹ dakẹ mbẹ; dakẹ.

*Brutus* :—Ẹnyin ara ilu mi, ẹ jẹki nma lọ nikan: ati nitori mi, ẹ duro ti Antony nihin. Ẹ buyi fun oku Caesar ki ẹ si ṣẹyẹ fun ọrọ ti Mark Antony ba sọ nipa ogo Caesar, eyi ti a fun ni aṣẹ lati sọ. Mo bẹ nyin ki ẹnikẹni maṣe yẹsẹ afi emi nikan, titi Antony yio fi sọrọ tan.

*Aralu Kini* :—Ẹ duro wayi ki ẹ gbọ ohun ti Antony ma wi.

*Aralu Keta* :—Ẹ jẹki o gori aga ki o ba ilu sọrọ, ao gbọ ohun ti yio wi. Goke Antony Ọlọla.

*Antony* :—Ọpẹlọpẹ Brutus ti o gbami l'aye lo jẹki nwa ibi lati ba nyin sọrọ.

( *O gori aga* ).

*Aralu Kerin* :—Kini o wi nipa Brutus ?

*Aralu Keta* :—O wipe nipa Brutus ni on ṣe le duro niwaju gbogbo wa.

*Aralu Kerin* :—O san fun ti ko sọrọ Brutus nibiyi.

*Aralu Kini* .—Omuroro enia ni Caesar yi.

*Aralu Keta* :—Otitọ dajudaju ti ko ni tabitabi ni eyini. Ọlọrun yọ wa ti Romu bọ lọwọ rẹ.

*Aralu Keji* :—Ẹ dakẹ, ẹ jẹki a gbọ ohun ti Antony le wi.

*Antony* :—Ẹnyin Bọkini Romu..............

*Awon aralu* :—Ẹ dakẹ, ẹ jẹki a gbọ nkan to wi.

*Antony* :—Ẹnyin ọrẹ mi, ẹnyin ara Romu ati ẹnyin ara ilu mi, ẹ tẹti nyin silẹ lati gbọ ọrọ mi. Mo wa sin Caesar ni, nko wa pọn. Iwa ika ti enia ba hu, la ma nsọrọ rẹ lẹhin iku rẹ; a si ma nsin iwa rere rẹ mọ egun rẹ; bẹni ki o ri pẹlu Caesar. Brutus ọlọla wa ti sọ fun nyin pe " Oniwọra enia ni Caesar " Ti o ba jẹ bẹni,

Arun buburu gba ni eyini; Caesar si ti san gbese yi l'asan kara.

Nihin, nipa aṣẹ Brutus ati awọn ẹgbẹ rẹ,

Nitoripe Brutus ọlọla enia ni. Bẹ si ni gbogbo wọn na, ọlọla enia ni wọn.

Agbara wọn ni mo fi wa sọrọ nibi oku Caesar. Ọrẹ mi ni Caesar nṣe, olododo ati olotọ enia ni si mi; ṣugbọn Brutus wipe oniwọra enia ni;

Ati Brutus papa ọlọla enia na ni o. O mu ẹru pupọ wa si Romu, ti ilu ta ti wọn da owo wọn si apo ilu, iru iwa Caesar yi ha jẹ iwa iwọra?

Nigbati ara ba ni oṣiṣẹ, Caesar a ba wọn kẹdun;

Iwa iwọra le ju iru iwa bawọnyi lọ, ṣugbọn Brutus wipe Caesar ni iwọra,

Ati pe Brutus papa ọlọla enia ni.

Ẹ ri pe nigbati a nṣe ọdun Lupercal, ẹrinmẹta ni mo fi ade Ọba lọ ọ;

Ẹrinmẹta lo si kọ ọ: iwọra ni eyi bi?

Sibẹsibẹ Brutus wipe o ni iwọra,

Ati nitotọ on na ọlọla enia ni. Emi ko sọrọ lati pe ọrọ Brutus ni irọ, ṣugbọn nihin mo wa lati sọ ohun ti mo mọ.

Gbogbo nyin lẹti fẹran Caesar ri, eyi ki si ṣe alainidi

Kini o ha da nyin duro lati sọkun fun? Ha! ero pipe to wa lori ẹda ti di t'ẹranko,

Ọmọ enia ko si l'ọgbọn lori mọ;

Ẹ ma binu si mi, ọkan mi wa ninu posi ni pẹlu Caesar;

Mo si ni lati fi ara balẹ titi ọkan na yio fi tun pada tọ mi wa.

*Aralu Kini* :—Ọrọ ọl gbọn lo ma sọ yi, ao ri ko danu.

*Aralu Keji* :—Bi o ba ro ọrọ na daradara, awọn arabi wa na ṣẹ Caesar lọpọlọpọ.

*Aralu Keta* :—Njẹ bẹni Janma? Ẹru ba mi pe ohun ti yio ti idi rẹ wa ko ni sunwọn.

*Aralu Kerin* :—Njẹ, ẹ kiyesi ọrọ rẹ? Ko fẹ gba ade: nitorina o daju pe ko ni iwọra.

*Aralu Kini* :—Bi eyi ba jẹ otitọ, ọpọlọpọ wọn ni yio fi ori ra.

*Aralu Keji* :—O ma ṣe o! oju rẹ pọn bi ẹṣẹ ina fun ẹkun sisun.

*Aralu Keta* :—Ko si ẹniti o l'ọla to Antony ni Romu yi.

*Aralu Kerin* :—Ẹ tun ṣakiyesi, wo o, o tun bẹrẹ si ọrọ sọ.

*Antony* :—Ṣugbọn nidayi ana, ko si ẹnikan lorilẹ to je d'aṣẹ Caesar kọja. On lo dubulẹ nibẹ yẹn.

Ko si si ẹni ti iṣẹ mu tobẹ ti yio bọwọ fun nis'siyi.

Ẹyin arabi, ti nba fẹ ki inu yin ru.

Ki o kun fun ibanujẹ,

Ki ẹ lọ ṣọtẹ si awọn enia wọnyi. Ma ṣẹ Brutus, Ma ṣẹ Cassius, awọn ti ẹ mọ pe ọlọla enia ni nwọn,

Emi ki yio ṣẹ wọn; yio wun mi ki nṣẹ oku yi, ki nṣẹ ara mi, ki nṣẹ ẹnyin papa

Ju ki nṣẹ awọn ọlọla enia wọnyi lọ.

Ṣugbọn iwe kan niyi, ti Caesar fi ami ẹdidi rẹ di;

Mo ri ni iyẹwu rẹ, iwe ipingun rẹ ni. Jẹki awọn enia ṣeṣi fi eti ba iwe ohun igbẹhin rẹ yi.

Ki ẹ ṣe gafara fun mi, nitori emi ko fẹ ka a. Nwọn o si sure lọ fẹnu ko oju ọgbẹ Caesar lẹnu.

Nwọn a si tẹ gele inuju wọn sinu ẹjẹ ọlọwọ ni; jubẹlọ,

Olukuluku wọn a ja irun rẹ kọkan pamọ fun iranti, ati, li akoko iku wọn, nwọn a fi irun yi ṣe bi ogun nla fun awọn ọmọ wọn.

*Aralu Kerin* :—Ẹ ka iwe na fun wa, Mark Antony, a fẹ gbọ ọ?

*Gbogbo awon aralu* :—Iwe ipingun Caesar ka a fun wa, ao gbọ ọ ni.

*Antony* :—Ẹ mu suru, ẹnyin ọrẹ mi, nko ni lati ka a.

Ko yẹ fun yin ki ẹ mọ bi Caesar ti fẹran yin to;

Ẹ ki ṣe igi, ẹ ki ṣe okuta, ẹda ni yin, ati gẹgẹ bi ẹda, bi ẹ ba gbọ iwe ipingun Caesar

Yio mu ọkan yin gbina yio si ko siyin lori, O dara bi ẹnyin ko ti mọ pe ẹnyin ni yio jogun rẹ;

Nitori bi ẹ ba lọ mọ, Ha! nkan a kan.

*Aralu Kerin* :—Ka iwe ipingun na, ao gbọ Antony,

Ko ka iwe ipingun na fun wa, iwe ipingun Caesar.

*Antony* :—Ẹ ki yio ha mu suru diẹ si,

Ẹ ki yio ha duro fun igba diẹ? Mo gbagbera ni mo ṣe lọ da ẹnu le e.

Nko ha ṣẹ awọn ọlọla wọnyi bayi? ti nwọn ti fi ida wọn gun Caesar pa. Aya fo mi pe mo ti ṣẹ wọn.

*Aralu Kerin* :—Ọlọtẹ ni wọn, ọlọla enia bawo?

*Gbogbo awon aralu* :—Iwe ipingun, iwe majẹmu rẹ.

*Aralu Keji* :—Enia buruku ni wọn; apania ni wọn;

Iwe ipingun, ka iwe ipingun fun wa.

*Antony*:—Ẹ ha fẹ fi agbara mu mi lati ka iwe ipingun yi? Bi o ba ṣe bẹ ni, ẹ pa agbo yi oku Caesar ka, ki nfi ẹni ti o kọ iwe yi han yin, ẹ jẹ ki nsọkalẹ. Ẹ o ha fun mi ni aye?

*Gbogbo awon aralu*:—Ma bọ silẹ.

*Aralu Keji*.—Sọkalẹ.

*Aralu Keta*:—Ao fun ọ laye.

(*O sọkalẹ.*)

*Aralu Kerin*:—Ẹ pagbo, ẹ duro yika.

*Aralu Kini*:—Ẹ sun sẹhin, ẹ jina si oku.

*Aralu Keji*:—Ẹ fun Antony laye, Antony ọlọla julọ.

*Antony*:—A! Ẹ ma ha mimọ bayi; ẹ tunbọ sun jina si.

*Awon aralu*:—Ẹ bi sẹhin, ẹ faye silẹ, ẹ rọ sẹhin.

*Antony*:—Bi omije ba wa loju yin, ẹ mura lati sun wayi o. Gbogbo yin lẹ mọ aṣọ iwọleke rẹ yi. Mo ranti igbati Caesar kọkọ wọ ọ, akoko ẹrun ni loju alẹ bayi ni, ni agọ rẹ. (Nijọna lo ṣẹgun awọn Nervii.) Ẹ wo o, nibi li ọkọ Cassius wọ ọ lọ. Ẹ wo iru ọgbẹ ti Casca onilara da si lara, lati ibiyi ni Brutus Olufẹ rẹ papa ti ọbẹ bọ, bi o si ti nfa ida rẹ yọ jade, wo bi ẹjẹ Caesar ti ntẹle ele na. Bi o si ti nsure jade lati mọ bi Brutus lo ṣe ika yi tabi on kọ. Nitoripe ẹ sa ti mọ pe ọrẹ Caesar timọtimọ ni Brutus nṣe. Ẹ sọ fun mi gbogbo ẹnyin irunmọlẹ aiye yi bi Caesar ti fẹran rẹ to, eyi ni ọgbẹ to jinlẹ ju gbogbo awọn yoku lọ, n'tori 'gbati Caesar ri pe Brutus gun on lọbẹ, aimore to mu ju ida ọlọtẹ lọ rọ ọ lapa.

Okun ọkan rẹ si ja, o si mu ẹwu awọleke rẹ fi we oju rẹ buruburu, ati ni idi ere Pompey niditi àgbará ẹjẹ nṣan nibẹ ni Caesar ọlọla ṣubu si. Ha! Iṣubu nla kili eyi, ẹnyin ara ilu mi? Nigbana ni emi ati irẹ ati gbogbo wa ti ṣubu, ti ọtẹ iku ti lagbara lori

wa ; nisisiyi, ẹ nsọkun, mo si ṣe akiyesi pe ami ikanu han loju nyin, ẹkun ikanu leyi. Ha! Ẹnyin oninure ki lẹ nsọkun fun, nitori ẹ kan ri aṣọ Caesar wa lasan ti nwọn fi ọbẹ ya. Ẹ wo ihín, ẹo ri ara rẹ bi awọn ọlọtẹ alapata ti kun un.

*Aralu Kini* :—Ha! Ko ṣe wo.

*Aralu Keji* :—Ye! Caesar Ọlọla.

*Aralu Keta* :—Ha! Ọjọ buruku ni eyi.

*Aralu Kerin* :—Ha! Ọlọtẹ, awọn eniakenia.

*Aralu Kini* :—A! Ẹjẹ yi pọju.

*Aralu Keji* :—Ao gbẹsan eyi.

*Gbogbo awon aralu* :—Ẹsan! Ẹ lọ kakiri, ẹ wa wọn kan, ẹ ki ina bọle wọn ; ẹ jo ile wọn dilẹ ; ẹ pa wọn ; ẹ ṣa wọn pa ; ẹ ma jẹki ọlọtẹ kan ye.

*Antony* :—Ẹ duro na ẹnyin ara ilu mi.

*Aralu Kini* :—Ẹ dakẹ nibẹ ; ẹ gbọ ohun ti Ọlọla Antony ma wi.

*Aralu Keji* :—Ao gbọ, ao tẹle e, on la ma ku ti.

*Antony* :—Ẹnyin ọrẹ, ẹnyin olufẹ mi, ẹ ma jẹ ki nmu nyin da

Riwo riwo ọtẹ silẹ lojiji. Ọlọla enia ni awọn ti o ṣiṣẹ yi ;

Ohun ẹdun t'omu wọn ṣe eyi, l'emi ko mọ rara. Ọlọgbọn ati Ọlọla ni nwọn.

O si daju pe nwọn yio da yin lohun bi ọlọgbọn. Nko wa s'hinyi lati ko yin laya lọ, emi ki ṣe ajisọdidun enia bi Brutus. Ṣugbọn bi gbogbo yin ti mọ mi, mo jẹ enia kan ṣa

Ti mo si fẹran ọrẹ mi. Eyiyi ni ohun ti o fun mi ni aye lati sọrọ mọ ọ.

Nitori emi ko ni ọgbọn, emi ko ni ọrọ lẹnu, nko si fuyi tobẹ, nko si ni iwa, nko si mọ ọrọ isọ; nko si gbede to lati mu ki enia binu; emi ma nsọrọ lọ ṣa ni;

Ohun ti ẹnyin papa mọ ni mo sọ fun yin. Mo fi ọgbẹ Caesar han yin, bi ahọn ti ko le sọrọ; mo si bẹ wọn ki nwọn sọrọ fun mi;

Ṣugbọn bi mo ba jẹ ajisọdidun bi Brutus, ati ki Brutus si jẹ alaimọsọ bi Antony,

Nigbana ni ẹo ri Antony ti yio ru yin ninu,

Ti yio si fi ahọn sinu gbogbo ọgbẹ Caesar

Ti yio mu okuta papa ti o wa ni ilu Romu yi lati dide ja.

*Gbogbo awon aralu* :—Ao ja.

*Aralu Kini* :—Ao sun ile Brutus.

*Aralu Keta* :—O ya kalọ; ao kọ ohun to ma da; ao wa awọn ọlọtẹ na kan.

*Antony* :—Ẹ tubọ duro gbọ temi, ẹnyin ara ilu mi.

Ẹ gbọ ohun ti ntun ma sọ.

*Gbogbo awon aralu* :—Ẹ dakẹ wayi, ẹ gbọ ohun ti Antony ma wi. Antony ọlọla julọ.

*Antony* :—Ẹnyin ara ilu mi, ẹ nlọ dawọle
Ohun ti ẹ ko mọ idi rẹ tan. Ẹ ko ti mọ ohun ti o ṣe ti ẹ ba fi fẹran Caesar; A! Ẹ ko mọ. Njẹ o yẹ ki nsọ fun yin nisisiyi?

Ẹ ti gbagbe ti iwe ipingun ti mo ti sọ fun yin.

*Gbogbo awon aralu* :—Nitotọ ẹ jẹ ki a duro gbọ ti iwe ipingun na.

*Antony* :—Iwe ipingun na niyi, o si fi edidi rẹ tẹ eyi ni pe, olukuluku bọkini ti o wa ni Romu yi ni ki a fun ni Drakima marundilọgọrun (drachma).

*Aralu Keji* :—Caesar Ọlọla, ao gbẹsan iku rẹ

*Aralu Keta* :—Caesar ọmọ alade ni papa.

*Antony* :—Ẹ fi suru gbọ mi.

*Gbogbo awon aralu* :—Ẹ dakẹ wayi.

*Antony* :—Jubẹlọ, o ti fi gbogbo papa (*walks*) rẹ,

Ati gbogbo oko rẹ (*arbours*) ati ọgba eleso ti o ṣẹṣẹ da ti o wa ni odikeji Tiber, o fi gbogbo wọn jin yin, ati awọn ọmọ-ọmọ yin. Ki ẹ ma lọ ṣire nibẹ ki ẹ si ma lọ mu faji nibẹ. Caesar na ta wi niyi; nigbawo ni ao tun ri iru Caesar bayi?

*Aralu Kini* :—Ao le ri iru rẹ lailai. Ẹ jade kalọ.

Ao jo oku rẹ ni ibi mimọ ni.

Ao si ki ogun ina na bọ ile awọn ọlọtẹ;

Ẹ ru oku na kalọ.

*Aralu Keji* :—Ẹ lọ fọn ina wa:

*Aralu Keta* :—Ẹ wo gbogbo ijoko.

*Aralu Kerin* :—Ẹ ya pẹpẹ, ẹ ya fereṣe, ẹ fa nkankinkan ya.

(*Awọn aralu gbe oku na jade*).

*Antony* :—Bilisi, o ti fi ẹsẹ si na, ma ba ṣẹ lọ.

Ipa ti o ba wun ọ ni ko mu sa.

(*Iranṣẹ kan wọ agbo wa*).

Ewo la ri to, ọmọ mi.

Iranṣẹ :—Ọgbẹni, Octavius bọ de si Romu.

*Antony* :—On da?

Iranṣẹ :—On ati Lepidus wa ni ile Caesar.

*Antony* :—Emi yio si lọ sibẹ tara lati lọ ri i.

O de si asiko. Orire, gbe wa. Pẹlu orire yi ko si ohun ti a ko ni le ṣe.

Iranṣẹ :—Mo gbọ ti o wipe, Brutus ati Cassius

Ti gun ẹṣin kọja lẹnu bode Romu, bi ẹniti ori wọn yi.

*Antony* :—O le jẹ pe nwọn ti gburo awọn ara ilu bi mo ti ta wọn nidi. Mu mi lọ si ọdọ Octavius.

(*Nwọn jade lọ*),

## Ere Keta Iran Keta.

ROMU.

NITA GBANGBA.

*Cinna akewi wọ arin awọn ero.*

*Cinna* :—Mo lala mọju pe mo nba Caesar jẹun, mo si bẹrẹ si irikuri ri. Ọkan mi ko jade rara loni, sibẹsibẹ nkankan pe ki njade.

(*Awọn aralu yọ si*).

*Aralu Kini* :—Orukọ rẹ?

*Aralu Keji* :—Nibo lo nlọ?

*Aralu Keta* :—Nibo lo ngbe?

*Aralu Kerin* :—Ọkọlobinrin ni ọ tabi Apọn?

*Aralu Keji* :—Fi esi fun olukuluku bi ibere rọ ti lọ.

*Aralu Kini* :—Da wa lohun ṣoki.

*Aralu Kerin* :—Da wa lohun laiwawawi.

*Aralu Keta* :—Da wa lohun laipurọ ki o ma ba ni ọ lara.

*Cinna* :—Kili orukọ mi? Nibo ni mo nlọ? Nibo ni mo ngbe? Ọkọlobinrin ni mi tabi apọn? Lati da olukuluku lohun bi ibere rẹ ti lọ

Tara, laiwawawi, laipurọ. Laiwawawi, apọn ni mi.

*Aralu Keji* :—Eyi ni ni pe omugọ ni awọn ti o ngbe iyawo; mo ro pe wa gba ẹṣẹ kan fun eyi ti o sọ ni. Sọ tẹnu rẹ tara.

*Cinna* :—Tara, mo nlọ si ibi oku Caesar.

*Aralu Kini* :—Bi ọrẹ tabi bi ọta?

*Cinna* :—Gẹgẹ bi ọrẹ ni.

*Aralu Keji* :—Idahun ni ṣe tara.

*Aralu Kerin* :—Nibo lo ha ngbe? sọrọ kiakia.

*Cinna* :—Ni kiakia, lẹgbẹ Capitol ni ile mi wa.

*Aralu Keta* :—Ọgbẹni, sọ orukọ rẹ ma purọ.

*Cinna* :—Ki nma purọ, Cinna li orukọ mi.

*Aralu Kini* :—Ẹ pin ni tonitoni, ọlọtẹ ni.

*Cinna* :—Cinna akewi lemi, Cinna akewi lemi.

*Aralu Kerin* :—Ẹ faya nitori orin korin rẹ. Ẹ faya nitori orin na.

*Cinna* :—Emi ki ṣe Cinna ọlọtẹ.

*Aralu Kerin* :—Eyini ko kan wa, Cinna lorukọ rẹ. Ẹ fa orukọ rẹ ya kuro laya rẹ, ki ẹ si ti nipakọ lọ.

*Aralu Keta* :—Ẹ faya, ẹ faya, ẹ wa, ẹ mu ogunna wa; ha! ẹyin ẹṣẹ ina, ẹ kalọ sile Brutus, sile Cassius ati apakan sile Ligarius. Ẹ kalọ, ẹ ma lọ.

( *Wọn jade* ).

## Ere Kerin. Iran Kini.

ROMU.

( *Yara kan ni ile Antony* ).

*Antony* :—Gbogbo awọn wọnyi ni yio ku. A ti sami si orukọ wọn silẹ.

*Octavius* :—Arakọnrin rẹ yio ku ; o gba bẹ Lẹpidus.

*Lepidus* :—Mo gba.

*Octavius* :—Kọ orukọ rẹ silẹ, Antony.

*Lepidus* :—Lori eyi, Publius ọmọ ẹgbọn rẹ na ko ni ye e pẹlu, Mark Antony.

*Antony* :—Bẹni, ko ni ye ; wo, mo sami si orukọ rẹ, mo si da ẹbi fun. Ṣugbọn Lepidus, lọ si ile Caesar, mu iwe ipingun lati ibẹ wa.

Awa yio si wa ọna bi ao ti ṣe din inawo ipingun na ku

*Lepidus* :—Kinla ! Njẹ ngo ba nyin nihin ?

*Octavius* :—O ba wa nihin tabi ni Capitol.

(*Lepidus jade lọ*).

*Antony* :—Alainilari enia kan ni yi, ti ko si tọ ka fi nkankan lọ. Iṣẹ iranṣẹ nikan lo yẹ ẹ.

O ha yẹ pe ki a fun eleyi ni ipin kan ninu ọna mẹta ti a fẹ pin ijọba wa si ?

*Octavius* :—O mọ ọ ni iru enia bayi lo da itọ rẹ mi nigbati o da'rukọ awọn ti a ma sami s'orukọ' wọn fun pipa nigbati a nṣe idajọ dudu wa ti a si nkọrukọ silẹ.

*Antony* :—Octavius, mo lọjọ lori ju ọ lọ. Nitotọ

Lo ti bu iyi fun ọkọnrin yi ati lati ba mu ẹru isọkusọ fuyẹ lọrun wa ṣugbọn yio ru iyi ipo yi bi igbati Kẹtẹkẹtẹ ru wura ni. Lati ma gbin ati lati ma lagun labẹ ẹru na ni. Ninu ki a ma tọ tabi ki a ma le si ọna

Gẹgẹ bi a ti fẹ, ati pe bi o ba si ru ẹru wa de ibiti a fẹ sọkalẹ

Ki a sọ ẹru rẹ, ki a si ti si igbẹ bi kẹtẹkẹtẹ ti ko ru ẹru,

Ki o le gbọn eti rẹ pa pa,

Ki o si lọ j'oko ni papa.

*Octavius*:—O le ṣe ifẹ inu rẹ si. Ṣugbọn jagunjagun papa ni ti a ti mọ iyi rẹ.

*Antony*:—Gẹgẹ bẹ na ni ẹṣin mi, Octavius, nitorina ni mo ṣe ni

Ki wọn ma p'oko fun u

O jẹ ẹranko ti mo ti kọ lati ja,

Lati wa awayipo, lati duro ati lati ma sure lọ;

Ati ohun ti mba ro lọkan mi, ni ara rẹ ni lati mu ṣe. Gẹgẹ bẹ si ni Lẹpidus ri bi a ba ro lọna keji.

A ni lati kọ, lati tọ, ati lati ti lọ siwaju.

Alailọgbọn lori enia kan ni, ẹni ti o njẹ epo ati ajẹku ati gbogbo ijẹkujẹ ti enia ti kọ silẹ bi onjẹ ijọ keji, ni o dun lẹnu rẹ;

Ma sọ nipa tirẹ, afi bi ohun elo wa.

Njẹ nisisiyi, Octavius, tẹtilelẹ si ohun pataki ti mo fẹ sọ fun ọ yi. Brutus ati Cassius ngba ogun jọ;

Ki a tete lọ ko wọn lọna, ki a si gba ogun awọn ọrẹ wa jọ, ki a tun lọ ba awọn ilu miran d ̣rẹ, ki a si mu awọn ihamọra ogun wa wọ

Ki a si lọ ṣe apejọ nisisiyi, bi ohun aṣiri wọnyi yio tu bi a si tilẹ le dojukọ ewu ti ko farasin yi.

*Octavius*:—Jẹ ka ṣe bẹ; nitori a ti sun kan ogiri;

Ọta pupọ lo si nwa wa lati wa gbe wa mi, ati gbogbo awọn miran to mba wa rẹrin, ni aimoye ero ika li ọkan wọn si wa, mo ro.

( *Wọn jade*).

## Ere Kerin. Iran Keji.

( *Niwaju agọ Brutus ni budogun leti Sardis* ).

*Brutus* :—Dide duro.

*Lucil* :—Daro, ki o si dide,

*Brutus* :—Lucilius, bawo lo ti ri? Njẹ Cassius wa nitosi?

*Lucil* :—Ko jina sihin; o si ran Pindarus wa lati ki ọ fun on.

*Brutus* :—Iyẹn dun bẹ; Ọga rẹ Pindarus, nipa iyipada iwa rẹ. tabi aimọwahu ti awọn olorogun rẹ ti mu mi ke abamọ ọpọlọpọ nkan ti mo ti ṣe,

Pe mba mọ nko ṣe. Ṣugbọn ti o ba wa nitosi, o tẹ mi lọrun

*Pindarus* :—Ṣugbọn o damiloju pe bi o ba ri ọga mi papa, o ba bakanna.

Iwa rẹ ko yi pada; o kun fun iyẹsi ati ibọla funni.

*Brutus* :—Emi ko jiyan eyini. Lucius, wa, ki nba ọ sọrọ kekere kan. Bawo lo ti gba ọ si? Fi ye mi daradara.

*Lucil* :—Tọwọtọwọ ati tẹyẹtẹyẹ to tọ fun mi; ṣugbọn ki ṣe pẹlu ọyaya ati ọrọ ọrẹ didun wọnni ti o ma nsọ ri.

*Brutus* :—Ọna ti o nsọrọ yi gba ni pe ifẹ wa bi ifẹ ọrẹ ti o ti gbona ri di tutu,

Kiyesi, Lucilius, nigbati ọrẹ ba nṣokunrun

Ti o ba si nku lọ, afi agbaraṣe ọrẹ nikan lo ku.

Ibi ti igbẹkẹle totọ ba wa, ọgbọn erokero ko le duro ni bẹ

Ṣugbọn awọn olofofo ti a ko le gbẹkẹle dabi ẹṣin to ja t'on sure lọ

Ti nwọn fi agbara ati ihalẹ ohun ti nwọn le ṣe han. Ṣugbọn nigbati nwọn ba gun wọn ni kẹṣẹ ni oju ija, ara wọn a rọ wẹsi ;

Ati bi ẹlẹtan ẹṣin. nwọn a ṣubu wi. Awọn jagunjagun Cassius ha mbọ bi ?

*Lucil*:—Ọpọlọpọ ninu wọn nro lati wa tẹdo si Sardis. papa awọn ẹlẹṣin wọn, nwọn pẹlu Cassius.

( *Nwọn yan wọle* ).

*Brutus* :—Sawo o, o de : ẹ to jẹjẹ lọ pade rẹ.

( *Cassius wọle ati awọn ogun rẹ* ).

*Cassius* :—Ẹ duro.

*Brutus* :—Ẹ duro ni kọkan

*Omo-ogun Kini* :—Duro !

*Omo-ogun Keji* :—Duro !

*Omo-ogun Ketá* :—Duro !

*Cassius* :—Arakunrin mi ọlọla julọ, o ti ṣẹ mi.

*Brutus* :—Ẹ ṣe idajọ mi ẹnyin irunmọlẹ, bi mba ṣẹ awọn ọta mi ri. Bi bẹkọ, bawo ni ngo ha tiṣe ṣẹ arakunrin mi ?

*Cassius* :—Brutus, oju rẹ tutu pẹsẹ yi nfi ọpọlọpọ aiṣẹtọ pamọ to ba si ṣe wọn.

*Brutus* :—Cassius, eyini to sọ ibinu rẹ sode jẹjẹ, mo mọ iru enia to jẹ. Maṣe jẹ kaṣe gbolohun asọ niwaju awọn ogun wa ta tẹ wọnyi, awọn to yẹ ki nwọn ma gbọ ọrọ miran lẹnu wa ju ọrọ ifẹ lọ. Paṣẹ ki wọn sun siwaju, ki a lọ si agọ mi, nibẹ, Cassius, ko sọ gbogbo ẹdun ọkan rẹ ; emi o si tẹti lelẹ gbọ ẹ daradara.

*Cassius* :—Pindarus, wi fun awọn ọgagun wa ki wọn mu awọn ogun wọn jina diẹ sihin.

*Brutus*:—Lucilius, iwọ na ṣe bẹ. Ki ẹnikẹni ma si sunmọ agọ wa titi ao fi sọrọ wa tan. Ki Lucilius ati Titinius ṣọ ẹnu ọna agọ wa.

## Ere Kẹrin. Iran Keta.

NIWAJU AGỌ BRUTUS.

*( Brutus ati Cassius wọle ).*

*Cassius*:—Niti pe o ṣẹ mi, o farahan gbangba ninu eyi. O ti dẹbi fun Lucius Pella, o si dojuti i ni gbangba,

Pe o gba owo ibọlẹ lọwọ awọn ara Sardis,

Nipa eyiti mo ko iwe ẹbẹ si ọ ti mo si bẹbẹ fun ọkọnrin na nitoripe mo mọ ọ.

Ṣugbọn o ko si ka iwe mi si.

*Brutus* :—Iwọ papa ṣiṣe lati kọwe nipa iru ọran bẹ.

*Cassius* :—Lakoko iru eyi, ko tọ ki o jẹ pe gbogbo nkan ti enia ba nṣe ni ao ma tan idi rẹ wo kinikini.

*Brutus*:—Jẹ ki nwi fun ọ, Cassius,
Iwọ papa jẹbi pe

O ni oju gigun. Nitoripe o ta ipo ilu ni gbanjo

Fun awọn ti ko tọ si.

*Cassius*:—Emi oloju gigun? O mọ pe Brutus to jẹ lo ṣe le sọ iru ọrọ bayi,

Bi bẹ kọ, mo fi gbogbo irunmọlẹ bura, eyi ni ibajẹ amọ rẹ.

*Brutus* :—Orukọ Cassius lo dọwọ si ibajẹ rẹ yi lara ;
Eyi lo mu ki iya rẹ fori pamọ

*Cassius*:—Iya !

*Brutus*:—Niran oṣu March ; ranti ijọ kẹdogun oṣu March, ranti.

Ki haṣe nitori are ilu

Ni ẹjẹ Julius ṣe ṣan jade lara rẹ

Ati pe ika enia wo lo fọwọkan ara rẹ ti o si gun lọbẹ.

Bi ko ṣe lori are. Kinla! o ha ma jẹ pe

Ọkan ninu wa t'o gun Ọga gbogbo aiye yi lọbẹ pa a nitoripe o pẹmọ mọ ole. Awa yi na ni yio tun wa fi owo ibọlẹ buruku mu alebu ba ara wa,

Ki a ta awọn ipo nlanla wa fun nkan ti ko kun ọwọ.

O san ki njẹ aja, ki nma gbo oṣupa

Ju ki njẹ iru ara Romu bẹ.

*Cassius*:—Brutus, ma tan mi si nkan buruku, emi ki yio gba a O gbagbe ara rẹ lati ka mi mu; jagun-jagun ni emi na bi iwọ;

Mo ti wa ninu iṣẹ na sin ọ. Mo mọ eto ṣe ju ọ lọ.

*Brutus*:—Ma ba ara rẹ lọ, Cassius, o ko to bẹ.

*Cassius*:—Mo to bẹ ẹ.

*Brutus*:—Emi ni o ko to bẹ.

*Cassius*:—Ma tun ba mi fa mọ. Emi yio gbagbe ara mi. Tọju ara rẹ. Ma fa jubẹ lọ.

*Brutus*:—Bara rẹ lọ sọhun iwọ enia lasan yi.

*Cassius*:—Ao ha le ṣe eyi?

*Brutus*:—Gbọ mi, nitoripe emi yio sọ tẹnu mi. O ha fẹ ki nfi aye silẹ fun irunu ati ibinu fufu rẹ O ha fẹ ki emi diji nigbati aṣiwere ba nran oju mọ mi?

*Cassius*:—Ẹnyin irunmọlẹ o, o ha yẹ fun mi ki ngba gbogbo iwọnyi sara?

*Brutus* :—Iwọnyi nikan ni? Wa gba jubẹ lọ. Binu titi igberaga

Ọkan rẹ yio fi rọlẹ.

Awọn ẹru nikan ni ki o lọ fihan bi o ti le binu to; ki o si jẹki awọn onde rẹ gbọn. Ki emi sa joko ki nsi ma wo ọ loju.

Ki nha duro ki nsi ma gbọn labẹ ọrọ apara rẹ,

Mo bura, iwọ a ko gbogbo ọrọ ibinu rẹ jẹ, bi o tilẹ mu ọ bẹ, nitoripe lati oni lọ ngo ma lo ọ ni akoko ti inu mi ba dun ati nigbati mba ma rẹrin ati nigbati iwọ papa ba nkanra bi agbọn.

*Cassius* :—Bi o ti tun wa da niyi?

*Brutus* :—O sọ wipe jagunjagun to yayi pupọ ni ọ, ẹ jẹ ka ka si otọ.

Njẹ mu ihalẹ rẹ ṣẹ yio si tẹmi lọrun pupọ.

Niti eyini inu mi a dun lati tubọ mọ bi iwa awọn bọkini ti ri.

*Cassius* :—Lọna gbogbo lo fi nṣẹ mi; o ṣẹ mi o, Brutus, o ṣẹ mi, mo wi bẹ nitoripe mo ṣe agba rẹ ninu iṣẹ jagunjagun yi.

*Brutus* :—Nko fẹ mọ bi o wi bẹ bi o ko wi bẹ.

*Cassius* :—Nigba aiye Caesar, on ko gbọdọ mu mi binu bayi.

*Brutus* :—O to; o to; iwọ papa ko gbọdọ mu u binu bayi.

*Cassius* :—Emi ko gbọdọ?

*Brutus* :—O ti ẹ, o ko to bẹ.

*Cassius* :—Kinla! emi ko gbọdọ mu binu?

*Brutus* :—Wa fi ẹmi rẹ wewu bo ṣe bẹ.

*Cassius*:—Ma wipe nitori mo fẹran rẹ ko sọ iru ọrọ wọnyi fun mi, ki o ma si mu mi ṣe ohun ti ma si ke abamọ rẹ.

*Brutus*:—O ti ṣe ohun ti wa ke abamọ rẹ nọ. Ko si ẹru kan ninu ihalẹ rẹ Cassius,

Nitoripe mo fi ododo iwa ṣe ihamọra mi, tobẹ ti ọrọ rẹ nbọ si mi ni eti bi atẹgun ti nko nani.

Lotọ ni mo ranṣẹ si ọ fun owo diẹ, ti o kọ lati fi ranṣẹ nitoripe emi ko le ko owo jọ lọna eru; mo fi ọrun bura pe kaka ki ngba owo eru lọwọ awọn akuṣẹ wọnyi,

Tabi ki ngba iba owo diẹ ti wọn ni li ọnakọna, o san ki nfa ọkan mi ya ki nsọ di owo

Ki nsi fi ẹkan ẹjẹ mi kankan ṣe pọnwun pọnwun.

Mo ranṣẹ si ọ pe ki o ba mi wa ọwo lati san fun

Awọn ẹgbẹ ogun mi eyi ti o kọ lati fun mi. Bi Cassius ti ima huwa nini;

Bi o ṣe emi ni mo ha jẹ kọ fun Caius Cassius bẹ?

Igbakigba ti Marcus Brutus ba di ọkanjuwa lati ti owokowo mọ apoti

Lai fẹ fun awọn ọrẹ rẹ, nigbana ni ki ṣango mura

Lati san ara pa a, ki o si faya pẹrẹpẹrẹ.

*Cassius*:—Emi ko fi owo du ọ.

*Brutus*:—O fi du mi.

*Cassius*:—Ngo fi du ọ; omugọ pa ni ẹniti o wa fun ọ

Ni iru esi bayi? Brutus ti ba mi ninu jẹ;

O yẹ ki ọrẹ le fi ara da ailera ọrẹ rẹ. Ṣugbọn Brutus jẹki ailera mi pọju bi o ti yẹ lọ.

*Brutus*:—Ngo ṣe alaifarada ọ ju igbati iwa rẹ yipada si mi.

*Cassius*:—O ko fẹran mi rara.

*Brutus*:—Awọn aṣiṣe rẹ ni ngo fẹ.

*Cassius*:—Ọrẹ totọ ko jẹ bẹjuwo aṣiṣe ọrẹ rẹ.

*Brutus*:—Apani enia ni ma a ṣe bẹ bi o ti wun ki ẹṣẹ ọrẹ rẹ na ga to.

*Cassius*:—Ẹ wa, Antony, ati Octavius, iwọ ọdọmọde, ki

Ẹ wa gbẹsan na lara Cassius nikan. Nitoripe aiye yi ṣẹ su Cassius;

Ọrẹ kanṣoṣo na ti o ni ti di ọta rẹ; arakonrin rẹ ti doju ija kọ ọ, a ti fi idena si ipa ọna rẹ bi ẹru.

Gbogbo aṣiṣe rẹ li a kiyesi, la si nkọ si lẹ ninu iwe; la kọ ti a si kọ sori kinikini

Lati fi gun mi loju.

Mo fẹrẹ le sun ẹmi mi jade bi ẹkun, ida mi re lọhun ni, aya mi re ninu igba aya yi, ọkan kan wa ti o ṣe owon ju ile iṣura Plutus lọ, o si ni iye lori ju wura lọ. Bi iwọ ti o jẹ ara Romu ba le mu igba aya na kuro, emi ti o kọ lati fun ọ ni wura yio fi ọkan mi fun ọ. Ki o gun un gẹgẹ bi o ti fi gun Caesar, nitoripe mo mọ pe irira ti o ni si Caesar o san ju ifẹ ti o ni si Cassius lọ.

*Brutus*:—Ki ọkọ rẹ bọ inu akọ rẹ.

O le binu nigbati o wun ọ; ma fun ọ ni aye rẹ.

Ṣe ohun ti o ba fẹ; ma ka iwa aibọwọ fun yi si ohun aikakun.

Ha! Cassius, a so ọ mọ ọmọ aguntan ti o ru ibanujẹ gẹgẹ bi okuta ibọn ti ru ina.

Eyiti o jẹ pe bi a ba ṣa tagbaratagbara yio yọ ina rẹ lẹkanna.

A si tun tutu lẹsẹkanna.

*Cassius* :—Cassius ha le wa laye ki o jẹ ohun yẹyẹ ati ohun rẹrinrẹrin fun Brutus rẹ,

Nigbati irunu ati ibanujẹ ba nyọ lẹnu ?

*Brutus* :—Nigbati mo sọ iyẹn, ikanra pọ fun mi.

*Cassius* :—Njẹ o tilẹ jẹwọ pupọ toyi ; gba mi lọwọ.

*Brutus* :—Mo fun ọ ni ọkan mi pẹlu.

*Cassius* :—Ha ! Brutus.

*Brutus* :—Kini ṣe o ?

*Cassius* :—O ko ni ifẹ to lati fi ara da iwa mi, nigbati iwa ikanra ti mo jogun lọdọ iya mi ba mu mi gbagbe ara.

*Brutus* :—Bẹni Cassius, ati lati oni lọ. Nigbati o ba nba Brutus rẹ sọrọ ibinu yio mọ wipe iya rẹ ni o mba ọ wi, yio si fi ọ silẹ.

*Ariwo ninu ile.*

*Akewi* :—Jẹ ki nwọle lọ wo awọn balogun wa ;

Nwọn ni asọ kan larin ara wọn ; ko si dara ki nwọn da nikan wa nibẹ.

*Lucil* ( *ninu ile* ) :—O ko ni de ibiti nwọn wa.

*Akewi* :—Afi iku ni o ma da mi duro.

( *Akewi, Lucilius, Titinius ati Lucius wọle lọ.* )

*Cassius* :—Bawo lo ti gbe, kini ṣe nyin ?

*Akewi* :—Ẹnyin balogun wa, ẹ ko ni ojuti ; kili ẹ ro. Ẹ pari ija yin ki ẹ si di ọrẹ bi o ti yẹ, ẹnyin mejeji, nitoripe mo lọjọ lori ju ẹnyin mejeji lọ ; eyini da mi loju.

*Cassius* :—Ha ! Ha ! Gbọ bi ọrọ ti dun mọ ara oko yi lẹnu.

*Brutus*:—Ma ba ara rẹ lọ. Ogboni, ma ba ara rẹ lọ, Iwọ ọyaju yi.

*Cassius*:—Ma binu si i, Brutus, iṣe rẹ ni.

*Brutus*:—Ma mọ ni iwa rẹ; bi o ba mọ ipo rẹ. Kini ogun ma fi awọn alakọra wọnyi ṣe, ẹnikeji mi? Malọ.

*Cassius*:—Ma lọ! Ma lọ! Ma lọ wayi!

(*Akewi jade lọ.*)

*Brutus*:—Lucilius ati Titinius, ẹ sọ fun awọn ọgagun pe
Ki wọn tọju ibiti awọn ẹgbẹ ogun ma wọ si lalẹ yi

*Cassius*:—Ki ẹnyin mejeji si pada bọ, ki ẹ si mu Messala wa nisisiyi.

*Brutus*:—Lucius, ife ọti waini, lọ bu kan wa.

(*Lucil ati Titinius jade lọ.*)

*Cassius*:—Ngo ro pe o le binu to yẹn.

*Brutus*:—Ha! Cassius, ibanujẹ pupọ ti di aisan si mi lara.

*Cassius*:—O ko tẹle ilana isin rẹ, ti o ba nfi aye silẹ fun ibanujẹ ti ko to nkan.

*Brutus*:—Ko si ẹnikẹni to tun le fi ara da ibanujẹ ju mi lọ. Ani Portia ti ku.

*Cassius*:—Ha! Portia?

*Brutus*:—O ma ti ku o.

*Cassius*:—Njẹ iku lọ lori mi nigbati mo mba ọ fa ọrọ lẹkan;
Ọfọ ti ko ṣe gba sara niyi; aisan wo li o pa?

*Brutus*:—Nigbati suru tan an fun aisi nile mi, ati ibanujẹ fun iro ti o gbọ pe Antony ati Octavius ti digun nla; nitori ko pẹ ti irohin yi kan mi ni o ku. Irohin yi ko si lori, o gbe ina jẹ, nigbati awọn iranṣẹ rẹ ko si lọdọ rẹ.

*Cassius* :—O si fi bẹ ku.

*Brutus* :—Bẹni o.

*Cassius* :—Ha ? Ẹnyin alaye ati irunmọlẹ.

( *Lucius pada wa ti on ti waini ati abẹla.* )

*Brutus* :—Ma sọ tirẹ mọ ; bu ife waini kan fun mi Eyi ni mo fi tẹ gbogbo aiṣedede wọnyi mọlẹ. *( O mu u)*

*Cassius* :—Emi na fẹ fi ife ọti kan pa ongbẹ. Bu ki o kun titi yio fi ṣẹ danu. Lucius, emi ko le mu amuju fun ifẹ ti mo ni si Brutus.

( *Lucius jade lọ* )

*Brutus* :—Wọ le wa Titinius.

( *Messala ati Titinius tun pada wọle* )

Ma wo lẹ, Messala ti emi.

Ki ẹ si jẹki a joko yi atupa yi ka, ki a si ṣe aṣaro ohun ti a ma ṣe.

*Cassius* :—Portia, njẹ o ku nini ?

*Brutus* :—Iyẹn to, jọ mo bẹ ọ ; Messala mo ti ri iwe kan gba pe Octavius ati Mark Antony ngbe ogun nla bọ wa ba wa ; ati pe ọna Fillipi ni wọn o gba wa

*Messala* :—Emi na ri iru iwe bẹ gba pẹlu.

*Brutus* :—Ihin wo lo tun ri gbọ pẹlu ?

*Messala* :—Eyiti mo tun gbọ nipe, Octavius, Antony ati Lepidus ti pa ọgọrun enia ninu awọn igbimọ nipa iwe ti nwọn ṣe ati ofin awọn alagba ti nwọn ṣe.

*Brutus* :—Nihinyi ni awọn iwe awa mejeji ti tase ra ; temi sọ pe adọrin enia ni nwọn fi iwe lilẹ mọ ita pa. Cicero si jẹ ọkan ninu wọn.

*Cassius* :—Cicero ọkan ?

*Messala* :—Cicero ti ku nigbati orukọ rẹ ti han ninu iwe nita. Ọga, mi o ha ri awọn iwe rẹ wọnyi gba lati ọdọ aya rẹ ni ?

*Brutus* :—Ndao, Messala

*Messala* :—Bẹni o ri nkankan gbọ nipa rẹ ninu iwe wọnyi ?

*Brutus* :—Ngo ri nkankan gbọ o, Mesasla.

*Messala* :—Iyẹn ma ṣajeji leti mi o.

*Brutus* :—Kini ṣe ti o mbere? O gburo kan nipa rẹ ninu iwe tirẹ ?

*Messala* :—Ndao, Ọga mi.

*Brutus* :—Njẹ nisisiyi, bi Octavius ọmọ Romu, sọ otitọ fun mi.

*Messala* :—Njẹ, bi ọmọ Romu, ki o gba otitọ ti nma sọ yi sara, nitori loni ko si tabitabi Portia ti ku; ọna ara lo si gba ku.

*Brutus*:—Njẹ ninu yẹn, Portia, odigboṣe; Messala, gbogbo wa lo jẹbi iku. Nigbati mo ronu pe yio sa ku nijọkan, mo ni suru lati gba irohin iku rẹ yi sara.

*Messala* :—Bayi loyẹ ki awọn en'a nla ma fi ọfọ nla rẹ ra.

*Cassius*.—Emi na ni oye yi gẹgẹ bi o ti ni, ṣugbọn emi ko ni ara rara lati gba a si bi o ti tọ.

*Brutus* :—O ya ka ma ba iṣẹ wa bọ bi alaye ki a pa

Eyini ti. Bawo li ẹ ti ro ti gbigbe ogun lọ si Fillipi lẹkan si ?

*Cassius* :—Emi ko ro pe eyini dara.

*Brutus* :—Sọ idi rẹ.

*Cassius* :—Idi rẹ na niyi: O san ki awọn ọta ma wa wa kiri; nipa bẹ yio lo gbogbo ohun ija rẹ danu, yio mu arẹ ba awọn ogun rẹ, yio si ṣe ara rẹ lọṣẹ. Nigbati awa lailọsi ibi kan yio simi daradara. Awa yio si ni ohun ija lati le wọn pada, ara wa a si ya gaga.

*Brutus*:—Imọran to dara ni lati fi aye lẹ fun imọran ti o dara julọ.

O mọ pe awọn enia to wa larin meji ilu Fillipi ati ibiti a wa yi, ọrẹ erehin ni wọn mba wa ṣe.

Nitoripe nwọn ko fẹ ran wa lọwọ nipa idawo wọn.

Bi ogun awọn ọta ba gba arin ilu wọn, nwọn a tubọ dapọ mọ ogun wọn.
Nwọn a si wa ba wa pẹlu okun tuntun ati ọmọ ogun tuntun.

Ati igbiyanju titun bi a ba le doju ija kọ wọn ni Fillipi. Wọn ko ni ri aye gbogbo nkan wọnyi nigbati awọn enia wọnyi ba wa lẹhin.

*Cassius*:—Sa gbọ eyiti emi o wi fun ọ arakunrin mi.

*Brutus*:—Ṣe gafara fun mi; mo tunbọ tọrọ gafara.

Mo fẹ ko tunbọ ṣe akiyesi pe awọn ọrẹ wa ti ṣe iranlọwọ to; ogun wa ti kun ṣọṣọ to.

Akoko ati ja wa ti doju rẹ; ẹ ni lati ṣọwọ; awọn ọta wa si npọ si lojojumọ

Ogun wa ti o kun ṣọṣọ yi, nmura lati dinku.

*Cassius*:—Njẹ bo ti ṣe ifẹ rẹ ni ki wọn lọ, jẹ ki a ma lọ.

Awa papa yio tẹle wọn, ao si pade wọn ni Fillipi.

*Brutus*:—Ọganjọ ngan ba wa lẹnu aroye wa yi;

A si ni lati fi ti ara fun ara nitoripe

Atete sun li atete ji; ọrọ ko tun ju bayi lọ mọ.

*Cassius*:—Eyi na to, o di owurọ; ni fẹrẹ kilẹmọ li ao dide ti ao si lọ kuro nibi.

*Brutus*:—Lucius o!

(*Lucius tun wọle*)

Fun mi ni ẹwu awọsun mi

*( Lucius jade )*

O darọ o. Mesala, o darọ o.

Titinius ọlọla, Cassius papa, o darọ o, ki a sun re o.

*Cassius*:—Ha! arakunrin mi ọwọn, ohun buruku li a fi bẹrẹ alẹ yi;

Iyapa bayi ko bọ si arin wa bayi ri,

Majẹ ki o ri bẹ o, Brutus.

*Brutus*:—Gbogbo nkan ti yanju.

*Cassius*:—O di owurọ o, oloye mi.

*Brutus*:—O di owurọ o, arakunrin mi ọwọn.

*Titinius ati Mesala*:—O di owurọ o, Brutus oloye.

*Brutus*:—O digba o, gbogbo yin.

*( Cassius, Titinius on Mẹsala jade, Lucius pada wa pẹlu ẹwu awọsun ).*

Mu ẹwu awọsun na fun mi; Molo rẹ da?

*Lucius*:—O wa ninu agọ nibi.

*Brutus*:—Kinla! o nsọrọ pẹlu orun li oju? Emi ko ba ọ wi, ọmọ mi; arẹ aisun lo mu ọ. Pe Claudius ati diẹ ninu awọn enia mi fun mi; mo fẹ ki wọn sun lori timutimu ninu agọ mi.

*Lucius*:—Varro o, Claudius o!

*( Varro ati Claudius wọle ).*

*Varro*:—Oluwa mi, o npe mi bi?

*Brutus*:—Mo bẹ ẹnyin janmọ, ki ẹ wa sun ninu agọ mi; o le jẹ wipe ma wa ji nyin nigbati o ba ṣe.

Emi yio si ran nyin ni iṣẹ si ọdọ Cassius arakunrin mi.

*Varro* :—Eyiti o ba wu yin ni; awa duro nibi lati ṣe ohun ti o ba fẹ.

*Brutus* :—Emi ko fẹ ki ẹ ṣe bẹ rara; ẹ lọ dubulẹ, ọmọ mi.

O le jẹ pe mo si le ro o bami. Lucius, sa wo o iwe ti mo ti nwa kiri ni eyi.

Mo ju sinu apo ẹwu awọsun mi.

( *Varro ati Claudius dubulẹ* ).

*Lucius* :—O da mi loju pe o ko fi le mi lọwọ, Ọga mi.

*Brutus* :—Jọ, o jare, mo le gbagbe pupọ ni. O ha le da orun mọju fun igba diẹ ki o si fi molo rẹ kọ orin kan tabi meji fun mi?

*Lucius* :—Gẹgẹ mi li o ṣe, bi o ba ti wun ọ si.

*Brutus* :—O tẹ mi lọrun bẹ, ọmọ mi. Mo ti fun ọ ni iyọnu pupọ nisisiyi; ṣugbọn mo ro pe o fẹ bẹ.

*Lucius* :—Iṣẹ mi ni, Ọga.

*Brutus* :—Ngo fẹ fun ọ ni iṣẹ to pọ ju agbara rẹ lọ; mo mọ pe ọmọde ma nfẹ akoko isinmi.

*Lucius* :—Oluwa mi mo ti sun.

*Brutus* :—O ṣe, iwọ yio si tun sun si, emi ko ni da ọ duro pẹ; bi Ọlọrun da mi si, ma san ore na fun ọ. Orin ọrun ni eyi. Ha! orungbe iku; o ti fi ọpa oje rẹ le ọmọ mi ti o nta molo fun ọ loju; ọmọ mi, o darọ o.

Emi ko fẹ ni kinkin ninu ẹṣẹ rẹ lọrun lati ji ọ. Bi o ba torungbe kiun, iwọ yio ṣẹ ọpa molo rẹ;

Emi yio gba lọwọ rẹ, ọmọ mi ọwọn, o darọ o. Kini yi, Kini yi? Ṣe ewe iwe yi pade nibiti iwe yi sojude nibiti mo ka a de? Mo ro pe ibi yi ni. ( *O joko* ).

( *Oku Caesar wọle* ).

Abẹla yi ko jo o re rara. Ha! tani nbọ ni? Aisun ti mo ṣe li o mu ki oju mi ma ri irikuri ti o dabi ọrọ ti o nrin bọ tọ mi wa yi? O ntọ mi bọ o. Kini iru nkan ti mbọ yi? Oriṣa wo ni ọ, tabi Maleka ni, tabi eṣu kan ni ẹ ti o fẹ jẹki otutu mu mi ti o si jẹ ki gbogbo irun ori mi dide ganwunganwun bayi? Ṣọ fun mi ohun ti o jẹ?

*Oku* :—"Eṣu lẹhin ibeji" rẹ, Brutus, ni mo nṣe."

*Brutus* :—Kini o ha wa ṣe?

*Oku* :—Lati sọ pe iwọ yio ri mi ni Fillipi.

*Brutus* :—O dara; njẹ emi yio tun ọ ri lẹkan si?

*Oku* :—Bẹni, ni Fillipi.

*Brutus* :—O dara. Ma ri ẹ ni Fillipi, ko buru. Nisisiyi, ọkan mi balẹ ti nko ri ẹ mọ.

(*Oku nu mọ loju*).

Iwin buruku. O wun mi ki ntun ma ba ọ sọrọ. Ọmọ mi Lucius, Varro ati Claudius, janmọ ẹ dide.

*Lucius* :—Ohun molo na ko dọgba, Ọga.

*Brutus* :—O ṣe bi on nta molo, Lucius, laju.

*Lucius* :—Ọga mi?

*Brutus* :—O nla'la ni, Lucius ti o fi nkigbe bẹ?

*Lucius* :—Ọga mi, emi ko mọ pe emi nkigbe.

*Brutus* :—Bẹni, o kigbe, tabi o ri nkankan?

*Lucius* :—Ọga mi, ngo ri nkankan,

*Brutus* :—Tun lọ sun Lucius, ogboni Claudius.

(*O kọju si Varro*

Ẹnikeji mi, njẹ o ji bi?

*Varro* :—Ọga mi.

*Claudius*:—Ọga mi.

*Brutus*:—Kini ṣe ti ẹ fi nkigbe tobẹ lati oju orun?

*Varro ati Claudius*:—Njẹ a kigbe bẹ, Ọga?

*Brutus*:—Bẹni. Njẹ ẹ ko ri nkankan?

*Varro*:—Ndao. Nko ri nkankan o.

*Claudius*:— Bẹ na ni, emi na pẹlu.

*Brutus*:—Ẹ lọ ki Cassius arakunrin mi fun mi. Ki ẹ wi fun pe ki o tete ran awọn ogun rẹ ṣaju; awa na yio si tẹle wọn.

*Varro ati Claudius*:—Awa yio ṣe bẹ gẹgẹ ọga wa.

( *Wọn jāde* ).

## Ere Karun. Iran Kini.

ITA GBANGBA FILIPI.

( *Octavius, **Antony** ati ogun wọn wọle* ).

*Octavius*:—Ha! Antony, ireti wa ṣẹ; o wi pe awọn ọta wa ko ni walẹ;

Ṣugbọn o ni wọn o duro lọwọ oke, ko si ri bẹ.

Wọn ti mura ogun tan, wọn si lọ pe wa nija ni Filippi nihin.

Ki a si to pe wọn nija, wọn fẹ gbe ija ko wa.

*Antony*:—Ọrọ lasan nini; mo mọ inu wọn

Mo si mọ idi rẹ ti wọn fẹ fi ṣe bẹ:

Inu mi iba dun bo bajẹ pe wọn ti lọ si ibomiran

Ki wọn wa fi abọ si ọdọ wa

Lati mu ki a ro pe wọn ni igboya, ṣugbọn ko ri bẹ.

( ***Iranṣẹ** kan wọle* ).

Iranṣẹ:—Ẹ mura, ẹ mura, ẹnyin Ọgagun Awọn ọta ti wọlu wa ba wa pẹlu ayẹyẹ nla, wọn si ti ta asiya imu ẹjẹ ni soke. O si yẹ ki a ṣe nkan kan nisisiyi.

*Antony*:—Ọctavius, dari awọn ọmọ ogun rẹ si ọwọ osi,

Ki o si jẹ ki wọn gba ibiti ọna tẹju.

*Octavius*:—Emi yio pọ si ọwọ ọtun: ki iwọ pọ si ọwọ osi.

*Antony*:—Kini ṣe ti o mba mi jiyan lakoko yi?

Kili o nṣe eyi fun, akoko jijiyan kọ ni yi?

*Octavius*:—Emi ko gbun ọ lohun rara;

Ṣugbọn bi nti ma ṣe ni mo wi ni,

*( Ilu Ologun ). Brutus, Cassius ati awọn ogun wọn wọle; Lucilius, Titinius, Messala pẹlu awọn miran.*

*Brutus*:—Nwọn duro nwọn fẹ ba wa sọrọ.

*Cassius*:—Titinius, duro soju kan nibiyi: a ni lati lọ ba wọn sọrọ.

*Octavius*:—Mark Antony, njẹ ki a pe wọn ni ija?

*Antony*:—Agbẹdọ, Caesar, ki a jẹ ki wọn kọkọ pe wa nija.

Ki a si da wọn lohun. Ma niṣo.

Awọn babalogun fẹ bawa sọrọ.

*Octavius*:—Ẹ ma yi ṣe nkan titi nwọn ma fi pe wọn nija.

*Brutus*:—Ki a sọ ni ọrọ, ki a to talu ara wa.

Abi bẹ kọ ẹnyin ara bi?

*Octavius*:—Ki nṣe pe awa ba ti ọrọ wa gẹgẹ bi ẹnyin ti ba wa.

*Brutus*:—Octavius, ohun rere san ju ọgbẹ buruku lọ.

*Antony*:—Bi o ti nda ọgbẹ buruku si eni i lara,

Bẹni o ma nfẹ ẹ; abunijẹ fẹni enia to to iwọ ko si.

Bi o ba ṣa ni ni ọ bẹ kikan tan iwọ a sọrọ didun tẹle.

Ṣakiyesi bi o ti da iho si ẹgbẹ Caesar, bẹ

Lo si ke Kabiyesilẹ Caesar, kẹpẹ.

*Cassius*:—Antony, a ko tilẹ sọ ti ọgbẹ nlanla ti iwọ da nisisiyi. Ṣugbọn fun ti ọrọ ẹnu rẹ o ti ji oyin ti o wa ninu afara wọn ni Hẹbla

Awọn afara ko si ni oyin ninu mọ

*Antony*:—Ṣugbọn wọn ko ṣ'alailoro.

*Brutus*:—Bẹni: nwọn ko tilẹ le kun mọ, nitori o ti ji agbara kikun wọn lo, Antony.

Ati bi ọlọgbọn, o tilẹ kilọ fun wọn ki o to ta.

*Antony*:—Okugbẹ; ẹnyin ko ṣe bakanna nigbati ida nyin nko ara wọn lẹgbẹ Caesar, ti ẹ fẹ ehin nyin si bi inọki, ti ẹ si fi ara pọn bi aja; ati ti ẹ si nwolẹ bi ẹru,

Ti ẹ si nfi ẹnu ko o li ẹsẹ

Ki alakọra Casca to yi sẹhin Caesar bi aja, ti o si gun lọbẹ lọrun,

A! ẹnyin alapọnpa wọnyi.

*Cassius*:—Alapọnpa! Njẹ Brutus, dupẹ lọwọ ara rẹ. Ahọn rẹ yi ki ba ti sọ isọkusọ yi loni, bi o ba jẹ pe imọran Brutus ni o tẹle nijọ kini.

*Octavius*:—Ẹ wa, ẹ wa, ẹ jẹki a sọ eyiti a ba wa. Bi o ba ṣe pe ijiyan ba mu wa lagun bayi, bi a ba fọwọ si nkọ? Ogun pupọ ni yio yọ. Ẹ ko ri i.

Mo ti fa ida mi yọ s'awọn ọlọtẹ, ki yio si wọnu akọ rẹ

Titi ọgbẹ mẹtalelọgbọn ti Caesar gba yio ri ẹsan rẹ gba pe,

Tabi titi Caesar miran yio jẹki oku miran sun pẹlu eyiti awọn ọlọtẹ pa.

*Brutus*:—Octavius, iwọ ko le ti ọwọ awọn ọlọtẹ ku, Afi bi o ba ko wọn wa fun ara rẹ.

*Octavius*:—Ireti mi li eyini; a ko da ipin mi mọ ida Brutus.

*Brutus*:—Bi o ba jẹ ọmọ atata julọ larin awọn ẹbi rẹ, iku kan ko ni yẹ ọ ju eyini lọ, ọmọ mi.

*Cassius*:—Omugọ ọmọ ile iwe kan ni eleyi, t'iru iku iyi yi ko tọ si, to ti da ara rẹ pọ mọ wọbia ati elere.

*Antony*:—Cassius, o ko yi ti fi iṣe rẹ yi silẹ?

*Octavius*:—Antony, wa, ṣe kalọ A ti pe nyin nija, ẹnyin ọlọtẹ wọnyi, a fi gun nyin loju. Bi ija ba ngba ninu nyin loni, ẹ kalọ si ibudogun, bi bẹkọ, ẹ wa nigbati o ba wun nyin.

(*Octavius, Antony ati awọn ọmọ-ogun wọn jade*).

*Cassius*:—O di ṣiṣe wayi o, k'iji ja, k'atẹgun fẹ, k'ọkọ ki'rin, omi ti daru; iṣẹ de.

*Brutus*:—Lucilius, wa ka sọrọ kekere kan.

*Lucilius*:—Mo de, o'uwa mi.

*Cassius*:—Messala o.

*Messala*:—Ewo ni ẹ wi o, Balogun mi.

*Cassius*:—Messala, oni ni ayajọ ibi mi, li ọjọ bi iru oni li

A bi Cassius: na ọwọ rẹ si mi, Messala, ki o si ṣe ẹlẹri mi pe ko dun mọ mi ninu

Gẹgẹ bi ko ti dun mọ Pompey ninu lati fi omnira Romu kọ

Si ara ogun kan ṣoṣo yi. O mọ daju pe mo gba Epicurus gbọ pupọ.

Ati gbogbo ilana ẹkọ rẹ pẹlu. Ṣugbọn nisisiyi, mo ti pa ero ọkan mi da;

Mo si gbagbọ pe a le ri ami nkan ti o mbọ. Nigbati a nti Sardis bọ, awọn ẹiyẹ idi nla meji kan fo sori igi asiya wa,

Eyiti o wa niwaju, wọn si ba sibẹ.

Wọn ngbe nkan mi, wọn si njẹun ninu ọwọ awọn jagunjagun wa.

Wọn si sin wa de Fillipi nihin. Ni owurọ yi ni wọn si fo ti wọn si lọ gba a. Lẹhinna ni a ri awọn Kanakana, Akala,

Ati awọn ẹiyẹ jokujoku miran, ti wọn nfo loke lori wa ti wọn si mbẹ wa wo nisalẹ

Bi ẹnipe awa ni ijẹ wọn ọla. Ojiji wọn lori awọn ọmọ-ogun wa

Si dabi igbokun nla iru eyiti o ma nlu aṣọ ti a ta bo awọn ti o npọka iku.

*Messala* :—Ma fi ọkan si eyini.

*Cassius* :—Emi ko fi ọkan si tobẹ; nitotipe aiya mi ko ja, Ọkan mi si duro lati fi ori la ewukewu to yi mi ka.

*Brutus* :—Bi o ti ri gan na nini, Lucilius.

*Cassius* :—Njẹ nisisiyi, Brutus mi ọwọn, awọn irunmọlẹ ṣi wa lẹhin wa

Ki awa, bi olufẹ, le dagbo ki a to ku.

Ṣugbọn bi o ti jẹ pe ninu aiye yi ao mọ ohun ti ọla le mu wa,

Jẹki a ṣe aṣaro ohun aibarade ti ọla le mu wa.

Bi ogun yi ko ba gbe wa, njẹ akoko yi ni yio jẹ igba asọmọ ọrọ

Ti ao sọpọ; bi bẹ ni, ewo ni o ha gbero lati ṣe?

*Brutus*:—Emi yio lo ọgbọn ti Cato lɔ bi ilana ẹkọ rẹ ti lọ, lori eyiti o fi pa ara rẹ, ti a si bawi fun. Ṣugbọn nko mọ bi o ti ri, nitori bi enia ba ku bẹ,

Wọn a ro si iwa ojo ati iwa enia buruku fun enia lati ku

Ki ọjọ rẹ to to. Nitorina mo fẹ fi suru gbe lati ma pa ara mi; ki nduro wo eyiti awọn ẹlẹda ati olutọju wa yio mu wa.

*Cassius*:—Njẹ bi ogun wa yi ba rọdi nkọ, wa ni itẹlọrun ki a di ọ mọ

Kẹkẹ, ki a si wọ ọ kakiri ita Romu?

*Brutus*:—Agbẹdọ o, Cassius, agbẹdọ o, iwọ ara ilu mi ọwọn;

Maṣe ro pe Brutus yio lọ si Romu bi onde:

Ọkan rẹ ga jubẹ lọ. Ṣugbọn oni oloni yi li ao fi opin si iṣẹ

Ti ọjọ kẹdogun oṣu March bẹrẹ.

Bi ao tun pade laiye yi, emi ko mọ rara. Nitorina ki a ṣe ipinya patapata loni.

Njẹ o digboṣe, Cassius, o digboṣe, lai ati lailai.

Bi a ba si tun pade—kini ṣe ti a ko ni pade—ao yọ mọ ara wa.

Ṣugbọn bi ko ba ri bẹ, awa ko ṣi ipinya wa yi ṣe.

*Cassius*:—Titi lai ati titi lailai, o digboṣe, A! Brutus;

Bi a ba tun pade, nitotọ, bi a ba tun pade, ao tun yọ mọ ra wa;

Bi bẹkọ ao ṣi ipinya wa yi ṣe.

*Brutus*:—Njẹ ninu eyini ki ogun tẹ siwaju. Enia iba jẹ mọ

Igbẹhin ogun yi ki igbẹhin na to de; ṣugbọn eyi daju pe ilẹ ọjọ oni yio ṣu

Nigbati o ba si ṣu, ao mọ igbẹhin rẹ.

Ẹ gbera! ẹ jẹki a ma lọ.

(*Wọn jade lọ*).

## Ere Karun. Iran Keji.

*Brutus*:—Gun ẹṣin rẹ, gun ẹṣin rẹ, Messala ko mu iwe wọnyi

Lọ si ọdọ ogun li odikeji: ki nwọn tako wọn lẹkan.

(*Ipe fun kikankikan.*)

Nitoripe mo ri pe irẹwẹsi mba awọn ọmọ ogun Octavius.

Ati bi o ba rọlu Octavius lẹkan yio jẹ ki ogun rẹ rọdi.

Gun ẹṣin rẹ ni kẹṣẹ, ki o si jẹki gbogbo wọn sọkalẹ wa.

(*Nwọn jade lọ.*)

## Ere Karun. Iran, Keta.

---

LODIKEJI BUDOGUN. FERE.

(*Cassius ati Titinius wọ budo.*)

*Cassius*:—Ha! Wo o Titinius, wo okugbẹ wọnni nsa; emi papa si ti di ọta si awọn temi. Alasiya mi si fẹ pẹhinda. Mo pa oku ojo na, mo si gba asiya lọwọ rẹ.

*Titinius*:—A! Cassius, Brutus tete paṣẹ ju. O si fi iwarapapa

Mu aṣẹ na ṣẹ nitori ti o ri aye diẹ lori Octavius.

Awọn ọmọ ogun rẹ si bẹrẹ si jẹ amọna.

Nigbati awọn ọmọ ogun Antony yi wa ka.

(*Pindarus wọ budo.*)

*Pindarus*:—Ma salọ siwaju ọga, ma salọ siwaju. Ogun Mark Antony ti wọ ibudo rẹ. Nitorina ma salọ siwaju, Ọlọla Cassius, ma salọ jina rere.

*Cassius*:—Oke yi jina to, Wo! Wo! Titinius, agọ mi ha ni eyini nbiti ina tan un?

*Titinius*:—Nibẹ ni, Ọga mi.

*Cassius*:—Titinius, bi iwọ ba fẹran mi, gun ẹṣin mi,

Ki o si gun ni kẹṣẹ kikankikan, titi ti on yio fi gbe ọ de

Ọdọ ogun ti o wa loke lọhun ni. Ki o si mu esi pada, ki o ba le

Dami loju bi awọn ogun ọta lo wa lọhun ni tabi ti ọrẹ ni.

*Titinius*:—Malọ kabọ n's siyi bi idan

(*O lọ.*)

*Cassius*:—Wa Pindarus, iwọ tun gun ori oke giga ọhun ni lọ.

Nko le riran jina; ṣakiyesi. Titinius, bi nkan ti ri,

ki o si pada wa sọ bi nkan tilọ logun fun mi.

(*Pindarus gun ori oke.*)

Ayajọ oni ni mo kọ laju si aiye. Akoko na ko gan.

Ibiti mo kọ gun ibẹ na l'emi yio gbe sọ. Mo ti lo igba mi tan laiye.

Ọmọ mi ewo lẹ ri gbọ?

*Pindarus*:—(*Lori oke*) Ha! Ọga mi.

*Cassius*:—Ewo l'a rigbọ o?

*Pindarus*:—Awọn ẹlẹṣin ti yi Titinius ka l'ọtun l'osi,

Kikankikan ni nwọn ngun ẹṣin wọn ni kẹṣẹ tẹle e. Bẹ ṛa si ni on na ngun ẹṣin tirẹ niwaju wọn.

Nwọn fẹrẹ ba nisisiyi.

A! Titinius, awọn diẹ sọkalẹ, on na sọkalẹ pẹlu. Nwọn mu u (*Igbe*). O gbọ wọn ho ge fun ayọ.

*Cassius*:—Sọkalẹ wa eyi ti o ri ni to.

A! Ojo enia ni mi lati ri ki ogun mu awọn oju lowo ọrẹ mi niwaju mi?

(*Pindarus sọkalẹ.*)

Sun mọ ibi yi, ọmọde yi. Ni Parthia ni mo mu ọ lẹru.

Nigbana ni mo si tun mu ọ bura pe ohunkohun ti nba ni ko ṣe fun mi ni ko ṣe.

Bi o ba fẹ gba ẹmi rẹ la, wa nisisiyi, mu ibura rẹ ṣẹ.

Ko le di ominira lati oni lọ. Mu ida mimu yi ti o tu ifun Caesar jade, ki o fi wa ifun emi na;

Ma duro fesi; kuku ida na ni eyi, mu u dani.

Bi nba si ti bo oju mi gẹgẹ bi mo ti bo yi,

Ko tọ ọ sinu rẹ.

(*Pindarus gun u lọbẹ.*)

Caesar, a ti gbẹsan rẹ

Pẹlu ida kanna papa ti a fi pa ọ. (*O ku.*)

*Pindarus*:—Njẹ mo bọ re, ṣugbọn ki ba ti ri bayi.

Bi emi ba nfẹ ṣe ifẹ ti emi papa. A! Cassius, A! Cassius,

Pindarus yio lọ jina rere de ibiti ara Romu kan ko ni ṣakiyesi rẹ.

(*O salọ.*)

*Titinius lun wọle pẹlu Messala.*

*Messala* :—Jẹ-mi-njẹ-ọ ri nwọn ta ayo ogun yi, Titinius, nitoripe ogun Brutus lo kọ ṣẹgun ti Octavius lẹhin na ni ti Antony wa ṣẹgun ti Cassius.

*Titinius* :—Irohin wọnyi yio tu Cassius ninu.

*Messala* :—Apa ibo ni o gbe fi i silẹ ?

*Titinius* :—Lori oke yi, ti on ti Pindarus ẹru rẹ pẹlu ibanujẹ.

*Messala* :—Njẹ on kọ lo wo silẹ nibẹ ni ?

*Titinius* :—Ko dubulẹ bi eyi ti o wa la'ye. A ! Ori mi o !

*Messala* :—Njẹ on na kọ ni eyi ni ?

*Titinius* :—Ndao. On ni yi, Messala. Ṣugbọn Cassius ko si mọ.

A ! Iwọ orun ti o nwọ lọ yi ; bi ilẹ rẹ ti nṣu larin awọn itanṣan rẹ,

Bẹni orun Cassius nwọ larin ẹpọn ẹjẹ.

Orun Romu ti wọ, ilẹ wa si ti ṣu.

Ma bọ, ikuku, iri, ati ewu ; a ti pari iṣẹ wa.

Aimọ ohun ti o mbọ wa ba wa lo ba eyi wa.

*Messala* :—Aimọ pe ao ba ire bọ lo ba iku yi wa.

A ! Aṣiro buruku ọmọ ibanujẹ. Ese ti o fi ero ti ko tọ si ọkan enia to tọ

A ! Aṣiṣe, iwọ ti a ki pẹ loyun rẹ, ṣugbọn a ki si bi ọ pẹlu inu didun.

Afi bi o pa iya ti o bi ọ jẹ

*Titinius* :—Kinla, Pindarus ! Nibo lo wa, Pindarus ?

*Messala* :—Wa a lọ Titinius emi na yio lọ ba Brutus, ngo si fi irohin yi bọ ọ leti. Mo le wipe, ma fi gun leti, nitoripe bakanna ni irohin yi yio ri leti Brutus, gẹgẹ bi igbati a fi ida ati ọkọ mimu gun enia lọkan.

*Titinius*:—Ma yara lọ, Messala. Emi yio si lọ wa Pindarus nisisiyi.

(*Messala jade lọ.*)

A! Cassius, kini ṣe ti o ran mi lọ jiṣẹ yi? Nko ha ko awọn ọrẹ rẹ lọna? Wọn ko ha fi mariwo ami iṣẹgun yi bọmi lowọ pe ki nfi le ọ lọwọ? O ko ha gbọ ariwo wọn bi? O ma ṣe o! O ti ṣe aṣiro ohun gbogbo. Ṣugbọn duro na ki nfi mariwo iṣẹgun yi siwaju rẹ. Brutus rẹ ni o wipe ki emi fifun ọ, emi yio si pa aṣẹ rẹ mọ. Brutus, wa sapakan, ko si ri bi mo ti fẹran Caius Cassius to. Ẹ ṣe gafara fun mi, ẹnyin irunmọlẹ. Ipa ti ọmọ Romu ni lati kọ ni eyi Wa, ida Cassius ki o si wa ọkan Titinius lọ.

(*O pa ararẹ.*)

*Fere dun, Messala pada wọle pẹlu Brutus, Cato kekere, Strato ali awọn miran.*

*Brutus*:—Nibo ni, nibo ni oku rẹ na wa, Messala?

*Messala*:—Wo o lọhun ni, ati Titinius ti nṣọfọ rẹ.

*Brutus*:—Titinius, yiju soke.

*Cato*:—Wọn ti pa a.

*Brutus*:—A! Julius Caesar, agbara ṣi kn ninu rẹ. Oku rẹ nrin kiri o si kọju ida wa si ara awa papa lati tu ifun ara wa.

(*Fere dun jẹjẹ.*)

*Cato*:—Titinius, onigboya ọkunrin. Wo o, ko ha dabi ẹnipe o fi oku ara rẹ de oku Cassius l'ade?

*Brutus*:—A ha le ri ara Romu meji miran bi awọn eleyi?

Iwọ ikẹhin Bọkini ni ọmọ Romu, O digboṣe.

O ṣoro ki a to tun ri iru rẹ ni Romu.

Ẹnyin ọrẹ mi, gbese ẹkun ti mo jẹ oku yi o pọju eyi ti mo le san lọ.

Emi yio waye san gbesan na, Cassius, ma wa aye san.

Nitorina, ẹ wa, ki a fi oku rẹ ranṣẹ si Thasos.

A ki yio sin si ibudogun wa yi, ki o ma ba bawa ninu jẹ.

Lucius wa, ati iwọ Cato kekere wa.

Ẹ jẹ kalọ si oju ija. Labeo ati Flavius. ẹ ma ko ogun wa nṣo.

Agogo mẹta ti lu ; ẹnyin ara Romu ki ilẹ to ṣu

Ka doju ija kọ wọn lẹkeji boya orire yio gbe wa.

*( Nwọn jade lọ. )*

## Ere Karun. Iran Kerin.

FERE.

*Awọn jagunjagun ọna mejeji wọle ; lẹhinna Brutus, Cato kekere, Lucilius ati awọn yoku.*

*Brutus* :—Sibẹsibẹ, ẹnyin ara ilu mi, ẹ mu ọkan yin giri.

. *Cato* :—Ọmọ ale wo ni ko ni ṣe bẹ? Tani yio tẹle mi?

Ma kede mi larin ogun pe " Emi ni ọmọ Marcus Cato: Ha!

Emi ọta awọn omuroro ọba, ati ọrẹ ilu mi. Ha! ọmọ Marcus Cato ni mi."

*( O le awọn ọta lọ. )*

*Brutus* :—Emi na Brutus; Marcus Brutus li emi na. Emi Brutus, ọrẹ ilu mi. Ki ẹ mọ mi bi Brutus.

*( O jade lọ, o kọlu ọta, nwọn bori Cato, nwọn si pa a. )*

*Lucilius* :—Ha! Cato, ẹdọmọkunrin ati ọlọla, o ti ṣubu nini?

Kinla! Iwọ ti ku loju ija bi Titinius.

Awa yio si bu ọla fun ọ nitori ọmọ Cato ni iwọ ṣe.

*Omo ogun kini*:—Tuba! Bi bẹkọ iwọ yio ku.

*Lucilius*:—Ti emi ba tuba, mọ pe mo ku nini.

Emi a fun ọ li owo pupọ bi iwọ ba pami lẹkan tara.

(*O fi owo lọ ọ*)

Pa Brutus, ki o le gba iyi nipa iku rẹ.

*Omo ogun kini*:—Awa ko gbọdọ. Ẹru ti o ni ọla lara ni.

*Omo ogun keji*:—Fi aye silẹ; sọ fun Antony pe nwọn ti mu Brutus lẹru.

*Omo ogun kini*:—Emi yio rohin na. Ha! Ọgagun na ni o mbọ yi.

(*Antony de budo.*)

A ti mu Brutus, a ti mu Brutus lẹru, Ọga mi.

*Antony*:—On da?

*Lucilius*:—O wa lalafia, Antony, nkankan ko ṣe Brutus.

Wipe o gbọ eyi lẹnu mi pe ko si ọtakọta ti o le mu Brutus lẹru laye. Ẹnyin irunmọlẹ mo bẹ yin ẹ ma jẹ ki iru iya nla bẹ ba.

Nigbati ẹo ba ri Brutus, bi l'aye ni tabi l'oku, ẹnyin yio ri bi Brutus,

Bi on papa.

*Antony*:—Eleyi ko nṣe Brutus, jọ wayi. Ṣugbọn gba mi gbọ,

Eleyi na niye lori bi rẹ,

Ẹ ma si ṣe jẹki nkankan ṣe ọkọnrin yi. Ẹ fi oju rere wo o.

Ẹ tọju rẹ daradara; o wun mi ki iru enia

Bayi jẹ ọrẹ mi ju ọta mi lọ. Rin siwaju ki o wa mọ bi Brutus ti ku

Tabi bi o wa l'aye, ki o si wa fi esi fun wa

Ninu agọ Octavius bi nkan gbogbo ti nlọ si.

APA IBOMIRAN NI IBUDOGUN.

*Brutus, Dardanius, Clitus, Strato ati Volumnius wọ bẹ wa.*

*Brutus*:—Ẹ ma bọ nihinyi, ẹnyin iba diẹ to ku ninu awọn ọrẹ wa.

Ẹ wa sinmi lori okuta yi.

*Clitus*:—Startilius ti gbe itufu ina na soke.

Ṣugbọn ko pada wa mọ, Ọga mi.

Ninu ki nwọn ti mu lẹru tabi ki nwọn ti pa ni.

*Brutus*:—Joko nihin, Clitus; ọrọ ti pipa na ni mo fẹ ba ọ sọ.

Aṣa to wa lode nisisiyi ni eyini.

Tẹtilelẹ si mi, Clitus

(*O sọ kẹlẹkẹlẹ fun pe "Fa mi."*)

*Clitus*:—Kinla! Emi, oluwa mi? Emi o jẹ ṣe e.

Bi nwọn ba fi gbogbo aiye yi fun mi.

*Brutus*:—Eyini to nipa yẹn, ma tun sọ ọrọ miran mọ.

*Clitus*:—O san fun mi ki npa ara mi.

*Brutus*:—Tẹtilelẹ si mi, Dardanius.

(*O sọrọ na wuyẹ.*)

*Dardanius*:—O ha yẹ mi ki nṣe iru nkan bayi?

*Clitus*:—Ha! Dardanius!

*Dardanius*:—Ha! Clitus!

*Clitus*:—Ẹbẹ buruku wo li Brutus nbẹ wipe ki o gba fun on ?

*Dardanius*:—O ni ki nwa pa on Clitus, wo o, o nronu.

*Clitus*:—Nisisiyi wo o bi ọkọnrin rere yi ti kun fun ibanujẹ tobẹ ti o fi nyọ ṣọnṣọ li oju rẹ.

*Brutus* :—Wa sihin, Volumnius, ọrẹ mi oninure,
Mo ni ọrọ wuyẹ kan lati ba ọ sọ.

*Volumnius* :—Ewo li o wi o, oluwa mi ?

*Brutus* :—Wa ! Ọrọ ti mo fẹ ba ọ sọ li eyi

Oku Caesar ti yọ si mi li ẹmeji li alalẹ ;

Li ẹkan ni Sardis ati li oru ana ni ibudogun ni Fillipi nibi.

Mo mọ pe ọjọ aiye mi pin wayi o.

*Volumnius*:—Ha ! Bẹkọ rara, oluwa mi.

*Brutus* :—O damiloju pe bẹni, Volumnius

Iwọ na ri bi aiye wa yi ti nlọ Volumnius ;

Awọn ọta wa ti le wa si eti koto.

(*Fere jẹjẹ*)

Ko si si aye ati sa asala mọ.

(*Fere jẹjẹ.*)

O san pupọ ki a ja sinu koto na fun ara wa

Jupe ki a duro ki nwọn ti wa si inu rẹ lọ.

Volumnius mi, o mọ wipe awa mejeji li a jọ lọ si ile-iwe ni igba kanna.

Nitorina fun ifẹ ti a ti ni si ara wa ri, mo bẹ ọ,

Mu kuku ida mi dani, nigbati emi yio fi inu pa oju ida papa.

*Volumnius* :—Ha ! Oluwa mi, iru iṣẹ ti ọrẹ nṣe fun ọrẹ kọ ni eyini.

(*Fere.*)

*Clitus* :—Salọ ! Salọ ! Ọga mi. Ko si aye iduro nihin.

*Brutus* :—Njẹ mo ki ọ, o digboṣe ati iwọ pẹlu Volumnius.
Strato iwọ ti o ti nfi gbogbo akoko yi sun,
Mo ki ọ pẹlu. Strato—Ẹnyin ara ilu mi, inu mi dun pe ninu
Gbogbo igba aiye mi ko si ẹnikan ti o ṣe olotọ si mi bi ọkọnrin yi. Ọjọ ti ogun yi rọdi yio mu ogo wa fun mi ju bi iṣẹgun lasan yi
Ti ma mu iyin wa fun Octavius ati Mark Antony lọ. Nitorina, mo ki nyin o digboṣe lẹkan,
Nitoripe ahọn Brutus fẹrẹ dakẹ lati ye pitan ara rẹ na.
Okunkun iku ṣu bo mi loju, egungun mi nfẹ isinmi.
Awọn egungun mi ti o ti se mi ro di akoko yi.

*Fere. Igbe ninu agọ. Sa ! Sa ! Sa !*

*Clitus* :—Sa, oluwa mi, salọ.

*Brutus* :—Ẹ ma lọ, emi yio tẹle nyin

(*Gbogbo wọn jade*).

Mo bẹ ọ Strato, duro ti oluwa rẹ. Ẹni-ọwọ papa ni ọ. Igba aiye rẹ ko ṣai ni ọla ninu lẹkan ri. Nitorina di ida mi mu
Ki o si gbe oju rẹ kuro. Nigbati mo ba nfi inu wọ oju ida na.
Iwọ ki yio ha ṣe bẹ, Strato?

*Strato* :—Njẹ ko gba mi lọwọ na. O digboṣe, oluwa mi.

*Brutus* :—O digboṣe, Strato mi. (*O fi inu wọ oju ida*). Caesar nisisiyi lọ gbejẹ ẹ. Emi ko pa ọ pẹlu idaji idunnu ti mo fi pa ara mi (*O ku*).

(*Octavius, Antony, Messala, Lucilius ati awọn jagunjagun wọn lọ si ibudo. Kakaki dun : wọn pada sile wọn.*

*Octavius*:—Ọkunrin wo ni eyi?

*Messala*:—Iranṣẹ Ọga mi ni; Strato, ọga rẹ da?

*Strato*:—O ti bọ lọwọ ẹru ara eyiti iwọ nru nisisiyi Messala

Awọn aṣẹgun nikan lo tọ si lati sun oku rẹ,
Nitori Brutus fi ọwọ ara rẹ gba ẹmi ara rẹ ni,
Ko si si ẹnikẹni ti o le ṣ'ogo lori iku rẹ.

*Lucilius*:—Bẹni o yẹ ki a ba Brutus; mo dupẹ lọwọ rẹ Brutus, pe o mu ọrọ Lucilius ṣẹ.

*Octavius*:—Gbogbo awọn ọmọ abẹ Brutus ni emi yio ṣe itọju. Iwọ nkọ? Ọkunrin yi, iwọ yio ha lo igba aiye rẹ yoku lọdọ mi?

*Strato*:—Emi yio ṣe bẹ, bi Messala ba ni ki nṣe bẹ.

*Octavius*:—Messala mi, ṣe bẹ gẹgẹ.

*Messala*:—Bawo ni Ọga mi ṣe ku, Strato?

*Strato*:—Mo di ida mu, o si fi inu pọn oju ida na.

*Messala*:—Octavius, mu ọkunrin yi lọ si ọdọ rẹ; ẹniti o ṣe aṣegbẹhin iṣẹ fun ọga mi.

*Antony*:—Ninu gbogbo ọmọ ibilẹ Romu, ọkunrin yi ni o jẹ ọlọla julọ; gbogbo awọn ọlọtẹ yoku li o pa Caesar nitori owu rẹ ti nwọn njẹ. On nikan ani on nikan li o pa a pẹlu ododo ọkan ati ire ilu ti o ni li akaiya rẹ. Igbesi aiye rẹ dara. Ko si si alebu kan ninu iṣe rẹ. Iwa rẹ ṣe pẹlẹ tobẹ ti t'aiye t'ọrun le dide jẹri rẹ pe, " Ọmọluwabi ni eleyi."

*Octavius*:—Bi inure rẹ ti ri bẹni ki a tẹ oku rẹ, ki a ṣe aṣa ati gbogbo oro ile rẹ fun. Oku rẹ yio sun ninu agọ mi ni alẹ yi. Ao tẹ bi jagunjagun nla pẹlu iyi ti o tọ fun u. Njẹ pe awọn ọmọ-ogun yoku si ibudo ki ẹ si jẹki a ma lọ lati ṣe ajọpin ayọ iṣẹgun nla yi.

(*Wọn lọ*).

## AWỌN ENIA TI O WA NINU ERE JULIUS CAESAR.

---

| | |
|---|---|
| Julius Caesar ... | Alaṣẹ agba gbogbo Romu. |
| Octavius Caesar,<br>Marcus Antonius,<br>M. Amilius Lepidus. | Awọn mẹta to jẹ ọga ni Romu, ti nwọn npaṣẹ lẹhin iku Caesar. |
| Marcus Brutus,<br>Cassius,<br>Casca,<br>Tribonius,<br>Caius Ligarius,<br>Decius Brutus,<br>Metellus Cimber,<br>Cinna. | Awọn ọlọtẹ si Caesar. |
| Cicero,<br>Publius,<br>Populius Lena. | Awọn agba Igbimọ ni Romu. |
| Flavius,<br>Marullus. | Awọn aṣoju ilu Cridos. |
| Artemidorus ... | Ojọgbọn ara ilu Caesar |
| Cena ... | Akewi |
| Alafọṣẹ ... | |
| Akewi miran ... | |
| Lucilius,<br>Titinius,<br>Messala,<br>Young Cato,<br>Volumnius. | Awọn ọrẹ Brutus ati Cassius. |
| Lucius,<br>Strato,<br>Varro,<br>Clitus,<br>Dardanus,<br>Claudius, | Awọn ọmọ ọdọ Brutus. |
| Ọmọ ọdọ Julius Caesar ... | |
| Ọmọ ọdọ Octavius Caesar ... | |
| Ọmọ ọdọ Mark Antony ... | |
| Pindarus ... ... ... | Ọmọ ọdọ Cassius |
| Calphurnia ... ... ... | Aya Caesar |
| Portia ... ... ... | Aya Brutus |

Bọkini, Jagunjagun, Igbimọ, Ọmọ-ọdọ ati awọn yoku.

Ibi Iworan—Romu, leti Sardis, Ibudogun Philippi.

*ALL RIGHTS RESERVED.*

